ÌWÉ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

# YOR 282
# VARIETIES OF PROSE IN YORÙBÁ (ORÍṢÌÍRÍṢÌÍ ÌTÀN YORÙBÁ)

**Ikọ̀ Abala-Ẹ̀kọ́** Abídèmí OlúṣọLá Bọ́láràìnwá B.A Hons. M.A. Ph. D
(Course Writer) – UI
Dr O.O. Adekọla (Course Editor)

**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**

© 2021 by NOUN Press
National Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone
Nnamdi Azikiwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

Published by:
National Open University of Nigeria

Printed 2021, 2023

ISBN: 978-978-058-209-8

**ÀKÓÓNÚ** **OJÚ ÌWÉ**

Ìfáàrà……………………………………………………… iv
Àfojúsùn Kọ́ọ̀sì Yìí…………………………………….. vi
Ojúṣe Akẹ́kọ̀ọ́………………………………………….. vi
Ìgbéléwọ̀n………………………………………………. vii
Ìgbéléwọ̀n Tí Olùkọ́ Yóò Máàkì……………………….. vii
Ìdánwò Àṣekágbá Àti Òṣùnwọ̀n……………………….. vii
Ìlànà Máàkì Gbígbà…………………………………….. viii

## ÌFÁÀRÀ

Àwọn Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà pàtàkì tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Tí a bá tilẹ̀ sọ pé kò sí ni ìjọ, ìjọ kò kún ni ẹ̀yà Yorùbá jẹ́, a kò jẹ́ ayò pa. Gbogbo ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan tó wà láwùjọ ni ìtàn kó ipa pàtàkì nínú ìgbésí ayé wọn, torí pé kò sí ẹ̀yà kan tí kò ní ìtàn tí ó ń sọ tàbí ṣe àfihàn wọn. Ohun tí ó dájú sáká ni pé ìtàn kì í dédé lalẹ̀ hù, àmọ́ ìhùwàsí àti ìsesí àwọn ẹ̀dá ènìyàn ní àwùjọ kan pàtó ni ó máa ń paradà di ìtàn àwùjọ bẹ́ẹ̀. Fún ìdí èyí, ó ṣe pàtàkì kí àwọn ènìyàn mọ̀ nípa ìtàn àwọn baba ńlá wọn, èyí ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń pa òwe pé bí ọmọ kò bá bá ìtàn yóò bá àrọ́bá, àti pé àrọ́bá ni baba ìtàn.

Orúkọ kọ́ọ̀sì yìí ní oríṣìíríṣìí ìtàn Yorùbá. Ọ̀kanòjọ̀kan ìtàn ni àwọn onímọ̀ tí tọ́kasí gẹ́gẹ́ bí èrò wọn torí ohun tó kojú sí enìkan, ẹ̀yin ló kọ sí ẹlòmíràn bí ìlù gángan ni ọ̀rọ̀ ìtàn jẹ́. Fún kọ́ọ̀sì yìí ọ̀nà mẹta gbòòrò ni a pín ìtàn sí láwùjọ Yorùbá. Ìpín kínní ni Ìtàn ìgbàanì, èyí tí a ṣe àtúnpín rẹ̀ sí ìtàn òrìṣà àti ìtàn Aláṣekù. Ìpín kejì ní Ìtàn àlọ́, èyí tí a tún pín sí ìtàn àlọ́, àti ìtàn àrọ̀. Ó yẹ́ kí o mọ̀ pé a lè pín ìtàn àlọ́ sí ọ̀nà méjì - àlọ́ àpamọ̀ èyí tí o ní í ṣe pẹ̀lú ewì àti àlọ́ àpagbè èyí tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ geere. Bákan náà ni a ni àrọ̀ tó jẹ́ eléwì àti èyí tí ó jẹ́ onítàn. Ìpín kẹta tí a pin ìtàn Yorùbá sí ni ìtàn àròsọ, a tún lè pín èyí náà sí ọ̀nà méjì bákan náà. Ìpín kínní nínú ìtàn àròsọ ni ìtàn àròsọ onílànà Fágúnwà èyí, tí ó jẹ mọ́ ìtàn mérìírí, nìgbà tí ìpín kejì jẹ́ ìtàn àròsọ abáyému, èyí tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa ìtàn àwùjọ òde-òní. Gbogbo àwọn ìtàn tí a pín sí ìsọ̀rí mẹ́tèẹ̀ta yìí ló ṣe pàtàkì tí o sì ń sọ̀rọ̀ nípa ìwà ọmọlúàbí àti ìgbé ayé ẹ̀dá tó ṣe ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ Yorùbá. Ohun tí ó dájú ni pé ni òpin kọ́ọ̀sì yìí, a ó le ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ nípa oríṣìíríṣìí ìtàn ni àwùjọ Yorùbá láì fi ìgbà kan bọ ọ̀kan nínú.

Módù mẹ́ta ni a pín kọ́ọ̀sì yìí sí, bẹ́ẹ̀ ni a pín módù kọ̀ọ̀kan sí ìpín márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Nínú módù kìnní, ìpín kìnní ni a ti wo ohun tí ìtàn ìgbàanì jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ, ìtàn ìgbàanì jẹ́ akitiyan àti ìgbòkègbodò àwọn akíkanjú ẹ̀dá tí wọ́n ṣe iṣẹ́ takuntakun fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Nínú ìtàn ìgbàanì ni a ti máa ń gbọ́ nípa àwọn òrìṣà àti Aláṣekù, ìgbé ayé wọn, ìwà wọn, ìṣesí, ìhùwàsí, àrímọ́ àti àwòmọ́ àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí láwùjọ títí di ìgbà tí wọ́n ju awà sílẹ̀, A tún ṣàlàyé pé ìtàn ìgbàanì kì í ṣe ìtàn àgbélẹ̀rọ, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìtàn òtítọ́ tí ó kún fún ìrírí àwọn akọni ẹ̀dá tí wọ́n tẹ ìlú, ìletò tàbí agbègbè kan dó. Ní ìkádìí módù kínní, ìpín kínní yìí, a sọ nípa pàtàkì ìtàn ìgbàanì pé ó jẹ́ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìpèníjà fún ọ̀pọ̀ ènìyàn ní ìgbà tí wọn bá gbọ́ nípa ìgbé ayé àwọn akọni yìí, wọn yóò le fi ṣe òdiwọ̀n tiwọn.

Nínú ìpín kejì módù kìnní yìí, ìsọ̀rí méjì gbòòrò ni a pín ìtàn ìgbàanì sí. Ìsọ̀rí kínní ni àwọn òrìṣà, ní ìgbà tí ìsọ̀rí kejì jẹ́ àwọn alaṣekù. Àwọn òrìṣà yìí ni a tún pín sí ọ̀nà méjì mìíràn. Èkínní ni àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀, èyí tí wọn ti ìsálú ọ̀run rọ̀ wá sí orílẹ̀ ayé. Àwọn kejì ni Ìbọ, àwọn wọ̀nyí ni àwọn tí ó gbé ayé wọ́n gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ènìyàn tí wọ́n kó ipa ribiribi gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ènìyàn ní ìgbà tí wọ́n wà lókè eèpẹ̀, ti àwọn ènìyàn sì sọ wọ́n di òrìṣà

àkúnlẹ̀bọ lẹ́yìn ikú wọn. Àwọn aláṣekù ní tiwọn jẹ́ baba-ńlá tàbí ìyá ńlá àwùjọ kan tí wọ́n kó ipa ribiribi láàrin ìlú tàbí àwùjọ, èyí tí ó mú kí àwọn tí wọ́n fi sílẹ̀ máa rántí tàbí bu ọlá fún wọ́n lẹ́yìn ìpapòdà wọn.

Nínú ìpín kẹta módù kìnní yìí ni a tún ti ṣe àgbéyẹ̀wò díẹ̀ lára àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn òrìṣà tí a sì jíròrò nípa wọn ni Ọ̀rúnmìlà, Ọbàtálá, Ògún, Sànpọ̀nná àti Yemọja.

Ní ìpín kẹrin módù kínní ni a ti jíròrò lóri àwọn aláṣekù tí wọ́n gbé ìgbé ayé wọ́n bí ènìyàn. Nípasẹ̀ àwọn ohun ribiribi tí wọ́n ṣe àti ìwà akọni wọn, wọ́n di málegbàgbé láwùjọ lẹ́yìn ikú wọn. Àpẹẹrẹ àwọn aláṣekù tí a sọ̀rọ̀ nípa wọn ni Ẹfúnróyè Tinúubú, Mọrèmi Àjàsorò, Ẹfúnṣetán Aníwúrà, Basọ̀run Ògúnmọ́lá àti Adélabú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì.

Ní ìpín karùn-ún tí ó parí módù kínní yìí ni a ti wo àwọn àbùdá àdání tí ó ya àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì sọ́tọ̀ sí àwọn ẹ̀dá yòókù ní àwùjọ. Àwọn àbùdá wọ̀nyí ni Àbímọ́/Àjẹbí, Ipò-tó-léwu, Àrímọ, Bíborí ìsòro, Ẹ̀bùn àtinúdá, Òkìkí, Kíkú ikú akọni àti Òògùn àti agbára.

Ní ìpín kínní módù kejì ẹ̀wẹ̀, a sọ̀rọ̀ lẹ́kùnrẹ́rẹ́ nípa àlọ́ onítàn ní ilẹ̀ Yorùbá. A ṣàlàyé pé àlọ́ jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń gbà láti kọ́ ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́, èyí tí ó ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìgbàgbọ́ àti ìṣesí àwọn Yorùbá hàn. Bákan náà ní a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá pàtàkì tí àlọ́ ní. Ní àkọ́kọ́ àwọn ohun tó wà ní àrọ́wọ́tó tàbí àyíká ni ó máa ń jẹyọ nínú àlọ́. A máa ń bá ènìyàn, ẹyẹ, ẹranko, iwin àti àkúdàáyá pàdé nínú ìtàn àlọ́. Èyí nìkan kọ́, àwọn ohun abẹ̀mí àti aláìlẹ́mìí náà máa ń ní àjọṣepọ̀ nínú àlọ́. Nínú ìtàn àlọ́, a kìí lo orúkọ abáyému fún àwọn ẹ̀dá ìtàn torí èyí lè dá rúgúdù sílẹ̀ láàrin ẹni tí ó ń pa àlọ́ àti ẹni tí orukọ rẹ̀ bá papọ̀. A tún sọ̀rọ̀ nípa orísun àlọ́ pé Inú ẹsẹ ifá ni àlọ́ ti jáde.

Ní ìpín kejì módù kejì ni a ti pín àlọ́ sí ìsọ̀rí. Ọ̀nà mẹ́rin tí a pín àlọ́ sí ni àlọ́ àpamọ̀, àlọ́ àpagbè, àrọ̀ àti ìmọ́. Ìpín kẹta módú kejì ni a ti sọ̀rọ̀ nípa àwọn ọ̀kanòjọ̀kan kókó tó má ń jẹyọ nínú àlọ́ bí ẹ̀kọ́ ìwà àti ìdí abájọ. Ìpín kẹrin módú kejì ni a ti jíròrò nípa àwọn onírúurú ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí ó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ bí i, ọ́gbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe, ìbánisọ̀rọ̀ tààrà, àwàdà, ìgbéniló̩kànsókè àti orin. Ní ìpín karùn-ún tí ó jẹ́ ìkádìí módú kejì a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn orísìírísìí ìwúlò tí àlọ́ ní, ní ilẹ̀ Yorùbá.

Módù kẹta dá lé ìtàn àròsọ Yorùbá. Ìpín kínní módú kẹta ni a ti sọ̀rọ̀ nípa ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbàsókè ìtàn àròsọ Yorùbá. A tún se àgbéyẹ̀wò àhunpọ̀ ìtàn nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. Èyí nìkan kọ́, a jíròrò lórí àwọn fọ́nrán tí òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ máa ń lò láti jẹ́ kí ìtàn rẹ̀ ṣe ìtẹ́wọ́gbà. Àwọn fọ́nrán náà ni ìjọ̀nilójú, àwàdà àti ìkóláyàsókè.

Ìpín kejì módú kẹta ni a ti se ìpínsísọ̀rí ìtàn àròsọ Yorùbá. A pín ìtàn àròsọ Yorùbá sí ọ̀nà méjì gbòòrò. Ìtàn àròsọ mérìírí àti ìtàn àròsọ abáyému. Ìpín

kẹta módù kẹta dá lórí ìfìwàwẹ̀dá nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. A sọ̀rọ̀ nípa oríṣìíríṣìí ẹ̀dá ìtàn àti ìgbékalẹ̀ ẹ̀dá ìtàn nínú ìtàn àròsọ Yorùbá.

Nínú ìpín kẹrin módù kẹta ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn asọ̀tàn àti ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí a máa ń bá pàdé nínú ìtàn àròsọ Yorùbá bí i: ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe, ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde, ọgbọ́n ìsọ̀tàn àlá,, ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà, ìlò àpèjúwe, ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́-ìran, ìtàn nínú ìtàn, ọgbọ́n pípadàsẹ́yìn àti ìsọníṣókí.

Ìpín karùn-ún módù kẹta ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àsàyàn ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rin. Àwọn ìwé ìtàn àròsọ tí a yẹ̀wò ni *Ọmọ Olókùn Ẹsin, Ọ̀bàyéjẹ́, Àjà ló lẹrù* àti *Ìtàn Èmi Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé*.

## ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Àfojúsùn Kọ́ọ̀sì yìí ni láti rí i pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọ̀nyí mọ nípa oríṣìíríṣìí ìtàn tí a lè bá pàdé ní àwjùjọ Yorùbá tí ó sì jẹ mọ́ ìsẹ̀dálẹ̀ àwọn baba-ńlá Yorùbá. Èyí ni yóò le jẹ́ kí wọ́n lè sọ̀rọ̀ ní àwùjọ àwọn onímọ̀ níbikíbi tí wọ́n bá bá ara wọn lọ́jọ́ iwájú.

Èyí nìkan kọ́, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le ní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn baba-ńlá Yorùbá tí a mọ̀ sí aláṣekù bẹ́ẹ̀ ni yóò rọrùn fún wọn láti walẹ̀jìn nípa àwọn ìbọ tí wọ́n gbé ìgbé ayé wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ènìyàn tí wọ́n sì kó ipa ribiribi ní ìgbà tí wọ́n wà lókè èèpẹ̀, wọn yóò tún ní ànfààní láti jíròrò nípa àwọn irúnmọ̀lẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀.

Àwọn akékọ̀ọ́ yóò le mọ pàtàkì àṣà Yorùbá àti bí àwọn oríṣìíríṣìí ìtàn Yorùbá tí a mẹ́nubà ṣe níyì tó ní àwùjọ àgbáyé gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ nínú àwọn onírúurú ìtàn tí a yẹ̀wò. A tún fẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ àwọn ìyàtọ̀ pẹ́ẹ́ pẹ̀ pẹ́ tí ó wà nínú onírúurú ìtàn kọ̀ọ̀kan láwùjọ Yorùbá.

Wọn yóò mọ̀ nípa àwọn àbùdá àdání pàtàkì tí àwọn oríṣìíríṣìí ìtàn Yorùbá ti a gbé yẹ̀wò ni àti bí wọ́n ti gbilẹ̀ tó láàrin àwùjọ́ Yorùbá láti ìgbà ìwáṣẹ̀ títí di àkókò tí a wà yìí.. Akẹ́kọ̀ọ́ yóò le mọ pé oríṣìíríṣìí ìtàn ni àwọn Yorùbá ni àti pé àwọn ìtàn tí a ń sọ wọ̀nyí ní í ṣe pẹ̀lú ìdàgbàsókè àti ìgbé ayé àwọn Yorùbá ni.

## OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́

Bí olùkọ́ ṣe ní ojúṣe tirẹ̀ láti fi yé akẹ́kọ̀ọ́ yékéyéké, kí wọ́n sì ní ìmọ̀ tí ó péye lórí ìtàn onírúurú tí a lè bá pàdé láàrin àwọn Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ fi ara balẹ̀ láti gba ìmọ̀ kún ìmọ̀ lọ́dọ̀ àwọn aṣaájú wọn nínú ìmọ̀ ìtàn, àṣà, àti ìse Yorùbá.

Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ múra láti ka àwọn ìwé tí olùkọ́ tọ́ka sí nínú ìwé ìléwọ́ yìí àti pé wọ́n ní láti máa wá ìdáhùn sí gbogbo àwọn ìbéèrè tí a gbé síwájú

wọn. Akẹ́kọ̀ọ́ kò gbọdọ̀ ṣe ọ̀lẹ nínú akitiyan rẹ̀ láti ní ìtẹ̀síwájú nínú ìmọ̀ ìtàn Yorùbá pàápàá ní àkókò ọ̀làjú tí a wà yìí.

Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ fi ara balẹ̀ láti gbọ́ ìtọ́sọ́nà àwọn olùkọ́ rẹ̀ kí o lè ṣe kóríyá nínú ẹ̀kọ́ rẹ̀. Akẹ́kọ̀ọ́ kò gbọdọ̀ rojú láti sisẹ́, ó gbọdọ̀ jẹ́ ẹni tí ó setán láti wá ìmọ̀ kún ìmọ̀ kò sì gbọdọ̀ jí iṣẹ́ oníṣẹ́ wò tàbí kí ó da iṣẹ́ oníṣẹ́ kọ. Ojúṣe mìíràn ní pé akẹ́kọ̀ọ́ ni láti wá àwọn ìwé tí wọ́n kọ fún un, kí ó sì kà wọn dáadáa. Bí kò bá le fi owó rẹ̀ rà wọ́n, kí ó máa lọ sí ilé ìyáwèé kàwé tí ó ti le rí àwọn ìwé wọ̀nyí kà. Torí Yorùbá bọ̀, wọ́n ní: “Ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n ni kìí jẹ́ kí á pe àgbà ní wèrè”.

Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ máa dá iṣẹ́ àmúrelé tàbí iṣé àmúṣe rẹ̀ padà ní àkókò tí ó yẹ, bẹ́ẹ̀ ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ fi ara hàn ní àsìkò ìdánwò àṣekágbá láìṣe àwáwí kankan.

Ní ìparí, kí akẹ́kọ̀ọ́ máa bèèrè àwọn ìbéèrè tí kò yé e nípa bíbá olùkọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀ lóòrèkóòrè

## ÌGBÉLÉWỌ̀N

Oríṣìí ọ̀nà ìgbéléwọ̀n méjì ló wà; iṣẹ́ ṣíṣe ti olùkọ́ yóò fi ọwọ́ sí àti ìdánwò alákọsílẹ̀. Èyí dá lórí iṣẹ́ àmúṣe tí yóò jẹ́ dídájọ ní ìbámu pẹ̀lú àsìkò àdápadà. Iṣẹ́ àmúṣe jẹ́ ìdá ọgbọ́n nínú ọgọ́rùn-ún. Ìrètí wà pé ìmọ̀ tí o bá gbà nínú ẹ̀kọ́ yìí yóò wúlò fún iṣẹ́ àmúṣe àti ìdánwò fún àṣeyege.

## ÌGBÉLÉWỌ̀N TÍ OLÙKỌ́ YÓÒ MÁÀKÌ

Iṣẹ́ ṣíṣe wà ní òpin ìpín kọ̀ọ̀kan. À ń fọkànsí pé kí akẹ́kọ̀ọ́ wá ìdáhùn sí gbogbo àwọn ìbéèrè tó wà níbẹ̀. Gbogbo àwọn iṣẹ́ ṣíṣe yìí ni a ó yẹ̀wò tí máàkì yóò sì wà fún mẹ́ta tó bá dára jù. Yóò jẹ́ ẹyọ kan ni módù kan. Módù kìn-ín-ní dá lórí Ìtàn Ìgbàanì, ìkejì dálórí Ìtàn Àlọ́, nígbà tí ìkẹta dá lórí Ìtàn Àròsọ.

Iṣẹ́ ṣíṣe àti ìgbéléwọ̀n yìí ni o máa fi ṣọwọ́ papọ̀ sí olùkọ́ ṣáájú ọjọ́ tí a bá dá. Bí ìdí pàtàkì bá wa láti má ṣe dá iṣẹ́ náà jọ kí ọjọ́ yìí tó pé, ó nílátí fi tó olùkọ́ létí ẹni tí ó le pinnu láti sún ọjọ́ náà síwájú. Ìdí pàtàkì ni ó lè mú kí olùkọ́ ṣe bẹ́ẹ̀.

## ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ ÀTI ÒṢÙNWỌ̀N

Ìdánwò àṣekágbá fún kọ́ọ̀sì yìí ‘oríṣìíríṣìí ìtàn Yorùbá’ jẹ àádọ́rin máàkì (70%) láàrin wákàtí méjì. Àwọn iṣẹ́ ṣíṣe àti ìgbéléwọ̀n olùkọ́ yóò jẹ ìfòyegbe irú ìbéèrè tí o máa ba pàdé nínú ìdánwò. Gbogbo ìpín kọ̀ọ̀kan kọ́ọ̀sì yìí ló yẹ ní gbígbọ̀n yẹ́bẹ́yẹ́bẹ́. O lè lo àǹfààní àsìkò tó wà láàrin ìparí kọ́ọ̀sì yìí sí ìgbà tí ìdánwò yóò bẹ̀rẹ̀ láti ṣe àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́. Wíwá

ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè lábẹ́ iṣẹ́ ṣíṣe àti èyí tí olùkọ́ yóò yẹ̀wò yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ dáadáa fún ọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́.

## ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ

Àte̩ ìsàlẹ̀ yìí ṣàlàyé bí máàkì gbígbà yóò ṣe wáyé.

| Ìgbéléwọ̀n | Máàkì |
|---|---|
| Iṣẹ́ àmúṣe 1-3<br>Mé̩ta tó ba dára jù ni a ó ṣe àkọṣílẹ̀ máàkì rè̩. | Ogójì (30%) |
| Ìdánwò àṣekágbá | Ọgọ́ta (70%) |
| Àròpọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

## MAIN COURSE


| **ÀKÓÓNÚ** | | **OJÚ-ÌWÉ** |
|---|---|---|
| **Módù Kínní** | **Ìtàn Ìgbàanì……………………..** | **1** |
| Ìpín Kìnní | Ohun tí Ìtàn Ìgbàanì jẹ́………….. | 1 |
| Ìpín Kejì | Ìpínṣíṣọ̀rí Ìtàn Ìgbàanì…………... | 5 |
| Ìpín Kẹta | Àwọn Òrìṣà……………………... | 8 |
| Ìpín Kẹrin | Àwọn Aláṣekù………………….. | 14 |
| Ìpín Karùn-ún | Àbùdá Àdání Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn Ìgbàanì................................ | 21 |
| **Módù Kejì** | **Ìtàn Àlọ́…………………………** | 26 |
| Ìpín Kìnní | Ohun tí Àlọ́ jẹ́…………………... | 26 |
| Ìpín Kejì | Ìpínṣíṣọ̀rí Àlọ́…………………… | 31 |
| Ìpín Kẹta | Kókó tó Máa ń jẹyọ Nínú Àlọ́….. | 40 |
| Ìpín Kẹrin | Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Àlọ́....................... | 43 |
| Ìpín Karùn-un | Ìwúlò Àlọ́………………………. | 48 |
| **Módù Kẹta** | **Ìtàn Àròsọ Yorùbá……………** | **51** |
| Ìpín Kìnní | Ìdìdelẹ̀ àti Ìdàgbàsókè Ìtàn Àròsọ Yorùbá……………… | 51 |
| Ìpín Kejì | Ìpínsísọ̀rí Ìtàn Àròsọ Yorùbá…..... | 58 |
| Ìpín Kẹta | Ìfìwàwẹ̀dá Nínú Ìtàn Àròsọ Yorùbá…………………... | 62 |
| Ìpín Kẹrin | Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Nínú Ìtàn Àròsọ Yorùbá…………………... | 67 |
| Ìpín karùn-ún | Àgbéyẹ̀wò Àsàyàn Ìwé Ìtàn Àròsọ Yorùbá……………..... | 73 |

## MÓDÙ KÌNNÍ ITAN ÌGBÀANÌ

Nínú módùlù kínní yìí ni a ó ti máa sọ̀rọ̀ ní kíkún nípa ìtàn ìgbàani èyí tí ó jẹ́ irúfẹ́ ìtan kan láàrin àwọn ẹ̀yà Yorùbá. A o sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ìtàn ìgbàani jẹ́, bẹ́ẹ̀ ni a ó ṣe ìpínsísọ̀rí ìtàn ìgbàanì. Lẹ́yìn èyí, ni a o ṣe atótónu nípa àwọn òrìṣà àti àwọn aláṣekù gẹ́gẹ́ bí oríṣìí ẹ̀yà ìtàn ìgbàanì. Àwọn kókó ọlọ́kanòjọ̀kan tí ó máa ń jẹyọ nínú ìtàn ìgbàanì ni a ó tún ṣe àlàyé kíkún nípa wọn. Ní ìparí, a ó jíròrò lórí àwọn àbùdá àdáni tí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ni.

Ìpín Kìnní Ohun tí Ìtàn Ìgbàanì jẹ́
Ìpín Kejì Ìpínsíṣọ̀rí Ìtàn Ìgbàanì
Ìpín Kẹta Àwọn Òrìṣà
Ìpín Kẹrin Àwọn Aláṣekù
Ìpín Karùn-ún Àbùdá Àdání Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn Ìgbàanì

## ÌPÍN KÌNNÍ OHUN TÍ ÌTÀN ÌGBÀANÌ JẸ

**Àkòónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́ẹ̀kọ́
 4.1 Ìtàn Ìgbàanì
 4.2 Pàtàkì ìtàn ìgbàanì
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kìnní, módù kìnní yìí ni a o ti máa sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ìtàn ìgbàanì jẹ, bákan náà ni a ó tún ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ohun tó mú ìtàn ìgbàanì ṣe pàtàkì láàrin Yorùbá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- Sọ ohun tí ìtàn ìgbàanì jẹ́
- Jíròrò lórí pàtàkì ìtàn ìgbàanì

## 3.0 IBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Sọ ìtàn ìgbàani kan tí o ti gbọ́ rí
2. Ṣe agbéyẹ̀wò àwọn ẹ̀kọ́ tí ó wà nínú ìtàn ìgbàanì tí o sọ

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìtàn Ìgbàanì

Ìtàn ìgbàanì jẹ́ akitiyan àti ìgbòkègbodò àwọn akíkanjú ẹ̀dá tí wọ́n ṣe iṣẹ́ takuntakun fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Nínú ìtàn ìgbàanì ni a ti máa ń gbọ́ nípa àwọn òrìṣà àti Aláṣekù. A máa ń gbọ́ nípa ìgbé ayé wọn tító di ìgbà tí wọ́n fi ayé sílẹ̀. A máa ń gbọ́ nípa ìwà, ìṣesí, ìhùwàsí, àrímọ̀ àti àwòmọ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí láwùjọ. Ìtàn ìgbàanì kì í ṣe ìtàn àgbélẹ̀rọ, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìtàn òtítọ́ tí ó kún fún ìrírí àwọn akọni ẹ̀dá tí wọ́n tẹ ìlú, ìletò tàbí agbègbè kan dó.

Ìjìnlẹ̀ èdè tí ó tayọ èdè ojoojúmọ́ ní a máa ń lo láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn ìgbàanì. Ìtàn ìgbàanì kò ní àjọṣepọ̀ kankan pẹ̀lú awo, ètùtù tàbí ohun mérìírí. Ohun tó jẹ́ pàtàkì nínú ìtàn ìgbàanì ni ètò mọ̀lẹ́bí, ọrọ̀-ajé ìlú, ètò amúlùúdùn àti ọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ ọwọ́ àti okòwò. Ìtàn ìgbàanì jẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó bá ojú ayé mu tó sì máa ń dáni lẹ́kọ̀ọ́ tààrà. Àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì pín sí oríṣìí méjì, ní ìgbà tí àwọn ẹ̀dá ìtàn kan jẹ́ èyí tí a dá mọ̀ tí a sì mọ àsìkò tí a bí wọn, àwọn mìíràn jẹ́ ẹ̀dá ìtàn tí a kò dá mọ̀ tàbí mọ ìgbà tí a bí wọn. Bóyá a dá àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì yìí mọ̀ tàbí a kò dá wọn mọ̀, ohun tí ó dájú sáká ni pé akọni àti alágbára ni àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì.

### 4.2 Pàtàkì Ìtàn Ìgbàanì

Ìtàn ìgbàanì máa ń fún àwọn ènìyàn ni àǹfààní láti mọ̀ nípa àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá àti àwọn baba-ńlá wọn ti wọ́n ti kú. Ní ìgbà mìíràn, àwọn àgbà tó sì wà lókè eèpẹ̀ yóò máa fi ìtàn àwọn akọni ìgbàanì wọ̀nyí gbe ọ̀rọ̀ wọn lẹ́sẹ̀ àti nípa ṣíṣe bẹ́ẹ̀, mú wá sí ìrántí iṣẹ́ àwọn akọni wọn.

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni ọ̀pọ̀ àwọn ìtàn ìgbàanì yìí jẹ́ fún ọ̀pọ̀ ènìyàn ní ìgbà tí wọn bá gbọ́ nípa ìgbé ayé àwọn akọni yìí, wọn yóò fi ìgbé ayé wọn ṣe òdiwọ̀n ti wọn, wọn yóò sì làkàkà láti rí i pé àwọn kò ṣe irúfẹ́ àsìṣe tí wọ́n bá ṣe, Yorùbá bọ̀, wọ́n ni ọ̀rọ̀ Olórò la fi í ṣe àríkọ́gbọ́n, ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n la fi í kọ́ ara ẹni.

Ìtàn ìgbàanì tún jẹ́ ìtanijí fún àwọn ènìyàn àwùjọ. Àwọn àgbà máa ń sọ ìtàn ìgbàanì fún àwọn ọmọdé láti gún wọ ní kẹ́ṣẹ́ àti láti ta wọ́n jí. Ṣe Yorùbá bọ̀, wọn ni, "Ẹsin iwájú ni tẹ̀yìn ń wò sáré. Ìwúrí tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ni ìtàn ìgbàanì máa ń fún àwọn tí ó bá gbọ́ ọ ní ilẹ̀ Yorùbá.

Ìtàn ìgbàanì máa ń jẹ́ kí ìmọ̀ àwọn ènìyàn tí ó bá gbọ́ ọ gbòòrò sí i nípa àwọn òrìṣà àti akọni tí wọ́n ti papòdà. Èyí ni pé bí ìmọ̀ ẹ̀dá ènìyàn bá ṣe gbòòrò sí bẹ́ẹ̀ ni òye yóò yé e sí nípa ìbágbépọ̀ ẹ̀dá láwùjọ.

Nípa sísọ ìtàn ìgbàanì wọ̀nyí fún àwọn ọmọdé tó sẹ̀sẹ̀ ń dìdelẹ̀, ìdánilójú wà pé iṣẹ́ àwọn akọni wọ̀nyí ti ní àkọsílẹ̀, nípa bẹ́ẹ̀, ìrántí wọ́n kò le parun, torí àwọn ìràn tí ó ń bọ̀ pẹ̀lú yóò kà nípa ipa ribiribi tí wọ́n ko nínú ìdàgbàsókè àti ìtẹ̀síwájú àwùjọ wọn, èyí yóò si jẹ́ àwòkọ́ṣe rere fún wọn, torí àwọn Yorùbá yóò bá àrọ́bá, àrọ́bá sì ni baba ìtàn.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín kínní, módùlù kínní, a ti jíròrò nípa ohun tí ìtàn ìgbàanì jẹ́, a pe ìtàn ìgbàanì ni akitiyan àti ìgbòkègbodò àwọn akíkanjú ẹ̀dá tí wọ́n ṣe iṣẹ́ takuntakun fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Bákan náà a sọ̀rọ̀ nípa àwọn ohun tí ó mú ìtàn ìgbàanì ṣe pàtàkì. Ohun tí ó dájú ni pé ni báyìí o tí mọ̀ ohun tí ìtàn ìgbàanì jẹ́ àti pàtàkì rẹ̀.

Ní ìpín kínní, módù kínní yìí a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé:

- Akitiyan àti ìgbòkègbodò àwọn akíkanjú ẹ̀dá tí wọ́n ṣe iṣẹ́ takuntakun fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn ni ìtàn ìgbàanì jẹ́.
- Ìtàn ìgbàanì kì í ṣe ìtàn àgbélẹ̀rọ
- Ìtàn ìgbàanì kún fún ìrírí àwọn akọni ẹ̀dá tí wọ́n tẹ ìlú ìletò tàbí agbègbè kan dó.
- Ìjìnlẹ̀ èdè tí ó tayọ ẹ̀dè ojoojúmọ́ ni a máa ń lò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn ìgbàanì
- Àwọn ohun pàtàkì tí ó máa ń jẹyọ nínú ìtàn ìgbàanì ni ètò mọ̀lẹ́bí, ọrọ̀ ajé ìlú, ètò amúlùúdùn àti ọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ ọwọ́ àti okòwò.
- Ìtàn ìgbàanì jẹ́ èyí tí ó bá ojú ayé mu, tí ó sì ń dáni lẹ́kọ̀ọ́, tààrà
- Akọni alágbára ni àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì
- Ìtàn ìgbàanì máa ń jẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ̀ nípa òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá àti àwọn bàbáńlá wọn tó ti papòdà.
- Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni ìtàn ìgbàanì jẹ́
- Ìtàn ìgbàanì máa ń tanijí
- Ìtàn ìgbàaní jẹ́ àwòkọ́se fún àwọn tó ń dìdèlẹ̀

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé lórí ohun tí ìtàn ìgbàanì jẹ́
2. Kí ní láríjà ìtàn ìgbàanì
3. Kọ ìtàn ìgbàanì kan tí o mọ̀

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adéoyè, C.L. (1979) Àṣà àti ìṣe Yorùbá. Ibadan: O.U.P.

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). Àwọn àṣà àti òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ibadan: Oníbọn-Òjé Press & Book Industries (Nig) Ltd.

Ládélé, T.A.A et. al (2006). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

## ÌPÍN KEJÌ ÌPÍNSÍSỌ̀RÍ ÌTÀN ÌGBÀANÌ

**Àkòónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ìpínsísọ̀rí Ìtàn Ìgbàanì
 4.2 Àwọn Òrìṣà
 4.3 Àwọn Aláseкù
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Ní ìpín kejì módù kínní yìí, a ó máa ṣe ìpínsísọ̀rí fún ìtàn ìgbàanì láti lè jẹ́ kí o yé ọ pé àwọn ìsọ̀rí kan wà tí a lè pín ìtàn ìgbàanì sí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí o lè:

- Pín ìtàn ìgbàanì sí ìsọ̀rí tí ó yẹ
- Ṣàlàyé kíkún nípa ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan
- Ṣe àfiwé àwọn ìsọ̀rí ìtàn ìgbàanì
- Pààlà láàrin àwọn ìsọ̀rí ìtàn ìgbàanì

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ṣàlàyé kíkún nípa ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan tí a lè pín ìtàn ìgbàanì sí
2. Ṣe àfiwé àwọn ìsọ̀rí ìtàn ìgbàanì tí o mọ̀

## 4.0 ÌDÁNÍLẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìpínsísọ̀rí ìtàn Ìgbàanì

Ìtàn ìgbàanì gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣaájú ní ìpín kìnní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jẹ́ akitiyan àti ìgbòkègbodò àwọn akíkanjú ẹ̀dá tí wọ́n ṣe iṣẹ́ takuntakun fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Ìsọ̀rí méjì gbòòrò ni a lè pín ìtàn ìgbàanì sí. Ìsọ̀rí kínní ni àwọn òrìṣà ní ìgbà tí ìsọ̀rí kejì jẹ́ àwọn aláṣekù.

## 4.2 Àwọn òrìṣà

Àwọn òrìṣà yìí ni a tún lè pín sí ọ̀nà méjì mìíràn ìkínní ni àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ èyí tí wọn ti ìsálú ọ̀run rọ̀ wá sí orílẹ̀ ayé. Àwọn kejì ni Ìbọ, àwọn wọ̀nyí ni àwọn tí ó gbé ìgbé ayé wọ́n gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ènìyàn tí wọ́n kó ipa ribiribi ní ìgbà tí wọ́n wà loke eèpẹ̀, lẹ́yìn ikú wọn, àwọn ènìyàn tí wọ́n ṣe ohun pàtàkì kan tàbí òmíràn fún sọ wọ́n di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ.

## 4.3 Àwọn Aláṣekù

Àwọn alásekù tàbí òkú ọ̀run ni àwọn baba-ńlá tàbí ìyá ńlá àwùjọ kan tí wọ́n ko ipa ribiribi láàrin ìlú tàbí àwùjọ, fún àwọn iṣẹ́ takuntakun tí wọn ṣe nínú ayé, àwọn tí wọ́n fi sílẹ̀ máa ń rántí tàbí bu ọlá fún wọ́n lẹ́yìn ìpapòdà wọn.

Díẹ̀ lára àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá ni ìwọ̀nyí Ṣàngó, Ọbàtálá, Ọ̀rúnmìlà, Ògún, Èsù, Yemọja, Ṣànpọ̀nná àti àwọn mìíràn. Àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀ lára àwọn alásekù ni Efúnsetán Animwúrà, Mọremí àjásóro, Ẹfúnróyè Tinúubú, Basọ̀run ògúnmọ́lá, Ògèdèngbé Agbógungbórò, Adélabú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì àti àwọn mìíràn. Àwọn ènìyàn ìlú Ìbàdàn kọ̀ gbàgbé Ẹfúnsetán, bẹ́ẹ̀ ni Basọ̀run Ògúnmọ́lá náà kó ipa mánigbàgbé nínú ìtàn Ìbàdàn. Tinúubú ṣe bẹbẹ ní ìlú èkó, èyí tí ó jẹ́ kí wọ́n ṣe gbàgede kan ni ìrántí rẹ̀.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìpín kejì módù kìnní yìí a ti ṣe ìpínsísọ̀rí fún ìtàn ìgbàanì lẹ́yìn tí a ti fún ìtàn ìgbàanì ni oríkì. Kò sí àníàní pé o ti lè ṣe ìpínsísọ̀rí tó péye fún ìtàn ìgbàanì. Èyí nìkan kọ, ó tún ti lè fun ìtàn ìgbàanì ni oríkì.

Ní ìpín kejì, módù kìnní yìí a ti rí:

- Akitiyan àti ìgbòkègbodò àwọn akíkanjú ẹ̀dá tó ṣe iṣé takuntakun fún àwùjọ wọn ni ìtàn ìgbàanì.
- Ìsọ̀rí méjì gbòòrò ni a lè pín ìtàn ìgbàanì sí. Àwọn òrí̀ṣà àti Aláṣekù
- A lè pín àwọn òrìṣà sí ọ̀nà méjì mìíràn: àwọn Irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ àti àwọn Ìbọ.
- Àwọn irúnmọlẹ̀ rọ̀ láti ọ̀run wá sóde ayé ni
- Àwọn Ìbọ gbé ìgbé ayé wọn bí ènìyàn lẹ́yìn ikú wọn, a sọ wọ́n di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ torí iṣẹ́ takuntakun tí wọ́n ṣe.
- Àwọn aláṣekù ni babańlá tàbí ìyá-ńlá wà ti wọn ti kú ṣùgbọ́n tí a ń ṣe ìrántí wọ́n lọ́jọ́ gbogbo fún ohun ribiribi ti wọn ṣe nígbà tí wọ́n wà láàyè.

## 6.0 IṢẸ́ SÍṢE

1. Se ìpínsísọ̀rí tó gbòòrò fún ìtàn ìgbàanì
2. Jíròrò nípa àwọn ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà nínú oríṣìí ìtàn ìgbàanì
3. Sọ ìtàn nípa aláseкù kan nínú ìdílé rẹ̀

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adéoyè, C.L. (1999) Àṣà àti ìṣe Yorùbá. Ibadan: O.U.P

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). Àwọn àṣà àti òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ibadan: Oníbọn-Òjé Press & Book Industries (NIG) Ltd.

Ládélé, T.A.A et. Al (2006). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

# ÌPÍN KẸTA ÀWỌN ÒRÌṢÀ

## Àkòónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  4.1 Àwọn òrìṣà
  4.2 Ọ̀rúnmìlà
  4.3 Ọbàtálá
  4.4 Ògún
  4.5 Sànpọ̀nná
  4.6 Yemọja
5.0 Ìsọnisókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kẹtà, módù kìnní yìí, a máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa díẹ̀ lára àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn òrìṣà tí a ó sì máa jíròrò nípa wọn ni Ọ̀rúnmìlà, Ọbàtálá, Ògún, Sànpọ̀nná àti Yemọja.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó lè,

- Ṣàlàyé kíkún nípa àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá kan
- Ìdí tí a fi ń pe Ọ̀rúnmìlà ni Ẹlẹ́rìí-ìpín
- Pààlà láàrin Ọ̀rúnmìlà àti àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá mìíràn
- Ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbésí ayé Òrìṣà-ńlá
- Jíròrò lórí irúfẹ́ òrìṣà tí Ògún jẹ́
- Ṣàlàyé kíkún nípa òrìṣà alápadúpẹ́
- Ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé nípa òrìṣà alágbo-ọ̀fẹ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Dárúkọ àwọn òrìṣà tí wọ́n ń bọ ní agbègbè rẹ.
2. Ìgbà/Àkókò wo, ni wọ́n ń bọ òrìṣà wọ̀nyí?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àwọn òrìṣà

### 4.2 Ọ̀rúnmìlà

Ọ̀rúnmìlà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ tí ó rọ̀ láti ìsálú ọ̀run wá sí òde ayé ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Ìtàn fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Ọ̀rúnmìlà wà pẹ̀lú Olódùmarè láti ìgbà ìwásẹ̀ àti pé ó wà pẹ̀lú Olódùmarè ní ìgbà tí a ń ṣẹ̀dá ènìyàn àti igbà tí ẹ̀dá ènìyàn yan ìpín rẹ̀. Ìdí nìyí tí a fi máa ń ki Ọ̀rúnmìlà báyìí:

Ẹlẹ́rìí ìpín
Akérefinúsọgbọ́n
Akọ́nilọ́ràn bi ìyekan ẹni
Òpìtàn Ilẹ̀ ẹ fẹ̀

Olódùmarè fún Ọ̀rúnmìlà ní ọgbọ́n àti òye èyí tí ó tayọ tí ẹ̀dá àti òrìṣà yòókù. Ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye yìí ni Ọ̀rúnmìlà máa ń lò láti fi ran ẹ̀dá ènìyàn àti àwọn òrìṣà lọ́wọ́ ní ìgbàkugbà tí wọ́n bá wà nínú ìṣòro. Àwọn àbùdá Ọ̀rúnmìlà yìí wà lára ìdí tí a fi fún un ní oríkì tí a fi ń kì í. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìtumọ̀ ni a ti fun orúkọ yìí (Ọ̀rúnmìlà). Nígbà tí àwọn kan sọ pé "Ọ̀run ló mọ ẹni tí yóò là" ni orúkọ yìí túmọ̀ sí, àwọn mìíràn sọ pé "Ọ̀run ló mọ àtilà" ni ó jẹ́. Ṣùgbọ́n ju gbogbo rẹ̀ lọ, Ọ̀rúnmìlà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn òrìṣà tí ó wà ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, òun ni a sì fi iṣẹ́ àtimáa wo ọjọ́ iwájú ẹ̀dá lé lọ́wọ́.

Àríyànjiyàn máa ń wáyé ní ìgbà mìíràn nípa pé bóyá Ọ̀rúnmìlà náà ni à ń pè ni Ifá tàbí òrìṣà mìíràn. Ohun tí Ọ̀rúnmìlà máa ń lò láti mọ ọjọ́ iwájú ènìyàn ni Ifá. Ifá yìí jẹ́ èkùrọ́ àti pé èkùrọ́ yìí ni gbogbo ènìyàn mọ̀ sí Ọ̀rúnmìlà. Èyí ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń pa òwe pé "Ẹni tí ó bá fi ojú èkùrọ́ wo Ọ̀rúnmìlà, Ifá á pa á. Ní ìgbà tí babaláwo bá ti dá Ifá tán, odù tí ó bá ti jáde nínú Ifá náà ni ó gbọdọ̀ rọ fún ẹni tí a bá dá Ifá fún.

Ìtàn àtẹnudẹ́nu mìíràn tún sọ pé gbàrà tí a dá ilé ayé tán ni àwọn òrìṣà rọ̀ láti ìsálú ọ̀run sí òde ayé. Ibi tí wọ́n rọ̀ sí náà ni a ǹ pè ní Ilé-Ifẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni lẹ́yìn èyí ni àwọn òrìṣà kọ̀ọ̀kan pínyà. Ìtàn sọ pé Ṣàngó lọ sí Kòso, Ọya lọ sí Irá, Ògún lọ sí Ìrè, Òrìṣà-Oko lọ sí Ìràwọ̀-àgbà nígbà tí Ọ̀rúnmìlà lọ sí Adó. Lẹ́yìn èyí ni Ọ̀rúnmìlà bí ọmọ mẹ́jọ ṣùgbọ́n èyí tí ó jẹ́ àbíkẹ́yìn ṣe àìgbọ́ràn sí bàba wọn èyí ni o sì mú Ọ̀rúnmìlà padà sí ọ̀run lójijì.

### 4.3 Ọbàtálá

Ọ̀kan nínú àwọn irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ náà ni Ọbàtála jẹ́. O wà pẹ̀lú Olódùmarè ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Òun ni Olódùmarè fún ni àǹfààní láti mọ ẹ̀dá ènìyàn kí ó tó di pé Ọlọ́run fi èémí sí ènìyàn lára. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni a máa ń tọ́ka sí Ọbàtálá gẹ́gẹ́ bí olórí àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù, èyí ni a fi máa ń pè é ní òrìṣà-ńlá, ẹni tí ó ṣe ojú, ṣe imú tí ó sì mọ gbogbo ara ènìyàn. Ìtàn

àtẹnudénu kan sọ pé nígbà mìíràn bí ó bá ṣe wu òrìṣà-ńlá ni ó máa ń mọ ẹ̀dá ènìyàn. Àwọn kan tilẹ̀ sọ pé ni ìgbà tí ó bá rẹ̀ ẹ́ tán, ó lè dá ẹlòmíràn kí ó suké, ó sì lè dá ẹlòmíràn kí ó rọ lọ́wọ́ rẹ lẹ́sẹ̀. Ẹlòmíràn lè ya àfín, ẹlòmíràn sì lè yọ gẹ̀gẹ̀ lọ́rùn. Ìdí sì nìyí tí a fi ń pe òrìṣà-ńlá ni "Adánibótirí". Òun ló dá eléyín gan-ngan tí kò rí ètè bò ó, ṣùgbọ́n a kò gbọdọ̀ fi àwọn ẹ̀dá wọ̀nyí sẹ̀fẹ̀ bí a kò bá fẹ́ rí ìbínú Òrìṣà-ńlá. Òrìṣa-ńlá yìí kan náà ni ìtàn sọ pé Olódùmarè fún ni àǹfààní láti sẹ̀dá ilé ayé ti a wà yìí ni ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Olódùmarè fún Ọbàtálá ni ohun èlò láti lọ dá ilẹ̀ gbígbẹ ṣùgbọ́n ní ìgbà tí ó ń bọ̀, ó mu emu yó, ó sì sùn sí ojú ọ̀nà. Ní ìgbà tí Olódùmarè àti àwọn òrìṣà yòókù retí rẹ̀ tí kò sì dé, wọ́n rán Odùduwà láti lọ wo ohun tí ó sẹlẹ̀. Odùduwà bá òrìṣà-ńlá ni ibi tí ó sùn sí ni ojú ọ̀nà tí ó sì ti mẹmu yó. Odùduwà kó àwọn irinṣẹ́ ọ̀dọ̀ rẹ̀, ó sì lọ gba iṣẹ́ náà ṣe mọ́ ọn lọ́wọ́. Ìdí èyí ni àwọn olùsìn Ọbàtálá kò fi gbọdọ̀ mu ẹmu títí di òní yìí. Iyán àti ìgbín funfun ni wọ́n fi máa n bọ Ọbàtálá. Oríṣìíríṣìí orúkọ ni a ń pe Ọbàtálá láti agbègbè kan sí òmíràn. Ọbalùfọ́n ni a mọ̀ Ọbàtálá sí ní ìlú Ifọ́n. Òun ni òrìṣà Ìtàpá ní Ilé-Ifẹ̀. Òrìṣà Ìkirè ni àwọn ènìyàn ìlú Ìkirè máa ń pè é. Òun ni Ògìyán ní ìlú Èjìgbò. Ìdìta ni àwọn ènìyàn ilú Ifẹ̀-Ọ̀dàn àti Ògbómọ̀ṣọ́ máa ń pè é. Ní ìgbà tí àwọn ará ìlú Ìbàdàn mọ̀ ọ́n sí òrìṣà Gbẹ̀gbẹ̀kún-ẹ̀gbẹ̀.

**Oríkì Ọbàtálá**

Ikú tí í ba ni gbé ilé f'ọlá ranni
Aláṣẹ! O sọ ẹnìkan soso di igbà ènìyàn
Sọ mí di'run, Sọ mí d'igba
Sọ mi d'ọ̀tàlé-légbèje ènìyàn
Òrìṣà eti ẹni ọlá
O fi gbogbo ọjọ́ t'obi
Ó tóbi láìṣeégbé
Bàǹtà banta nínú àlà
Ó sùn nínú àlà
Ó jí nínú àlà
Ó ti inú àlà dìde
Baba ńlá, oko Yémowó!
Òrìṣà wù mí ní ibùdó
Ibi rere l'òrìṣà kalẹ̀
Òrìṣà ńlá, Ọ̀ṣẹ̀rẹ̀màgbò
Ẹni tí wọn bí l'óde Ìgbò
Tó lọ jọba l'óde Ìrànje
Òrìṣà ńlá alàbàláṣẹ
Òrìṣà ńlá atẹ́rẹrẹ k'áyé
Ò gbe ọmọ rẹ̀, ó sọ ọ́ dàjẹ́
Òrìṣà ńlá Àdìmúlà
Olójú kára bí ajere
Òbàba arúgbó
Òrìṣà gbìngbinnìkìn

## 4.4 Ògún

Ọ̀kan lára àwọn irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ ni Ògún jẹ́. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé Ògún ni a fi iṣẹ́ irin lé lọ́wọ́ tí ó sì ń ṣe àkóso ohun gbogbo tí ó bá jẹ mọ́ irin. Gbogbo àwọn tí ó bá ń ṣe iṣẹ́ irin ni ilẹ̀ Yorùbá àti àwọn tí ó bá ń ṣiṣẹ́ tó jẹ mọ́ irin ni ó máa ń bọ Ògún. Ògún yìí kan náà ni òrìṣà àwọn ọdẹ àti àwọn tí ó ń kọ́lé. Èyí ni wọn ṣe máa ń kìí báyìí:

Ògún Lákáayé
Onílé kángunkàngun ọ̀nà ọ̀run
Òlómi nílé fẹ̀jẹ̀ wẹ
Ò lásọ nílé fi imọ̀kímọ̀ bora

Ní igbà tí àwọn irúnmọlẹ̀ rọ̀ láti ìsálú ọ̀run wá sí ilé ayé, Òrìṣà-ńlá ni ìtàn sọ pé ó ṣaájú àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù tí ó sì la ọ̀nà fún wọn pẹ̀lú àdá bàbá rẹ̀ ṣùgbọ́n ní ìgbà tí àdá Òrìṣà-ńlá bẹ̀rẹ̀ sí i tẹ̀, Ògún ni ó bọ́ síwájú pẹ̀lú àdá irin rẹ̀ tí ó sì la ọ̀nà fún àwọm irúnmọlẹ̀ dé Ifẹ̀ Oòdáyé. Ifẹ̀ Oòdáye yìí ni àwọn irúnmọlẹ̀ kọ̀ọ̀kan ti gba ọ̀nà ìrìnàjò wọn lọ. Ògún ni tirẹ̀ gba inú igbó lọ láti lọ sọdẹ. Àkókò yìí ni a gbọ́ pé ó tẹ ìlú Ìrè dó. Ògún sọdẹ títí tí gbogbo aṣọ rẹ̀ fi gbó mọ́ ọn lára. Ní ìgbà tí yóò fi padà sí Ifẹ̀ Oòdáyé ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé ìhòhò ni ó wà. Ògún padà sí inú igbó ó lọ wá imọ̀ bora, èyí ni wọn ṣe máa ń kì í ní: "Ò láṣọ nílé fi ìmọ̀kímọ̀ bora bí aṣọ. Ní ìgbà tí ògún bá ń sọ ìrírí rẹ̀ nínú igbó, lílà tí ó bá la ẹnú rẹ ìjálá ni yóò bẹ̀rẹ̀ sí í sun, ṣùgbọ́n ní ìgbà tí ó bá ń sọ ìrírí rẹ̀ tí kò bójúmu, ìrèmọ̀jé ni ó máa ń sun.

## 4.5 Sànpọ̀nná

Sànpọ̀nná jẹ́ ọ̀kan lára irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ tí o ti wà láti ìgbàanì. Òrìṣà yìí jẹ́ èyí tí ó bani lẹ́rù gidigidi, bẹ́ẹ̀ ni ó máa ń fi ìgbóná àti ọdẹ orí jà ní ìgbà tí inú bá ń bí i tàbí ní ìgbà tí wọn bá tàpá sí òfin rẹ̀. Bíbọ Sànpọ̀nná kò ní àkókò kan pàtàkì bí kò ṣe ìgbàkígbà tí àìsàn Sànpọ̀nná bá ṣe ẹnìkan láàrin ìlú. Lẹ́yìn tí ara aláìsàn Sànpọ̀nná yìí bá ti ya, àwọn olùbọ rẹ̀ yóò mu èérún ara aláìsàn náà, aṣọ tí ó wọ̀ lákòókò àìsàn tí wọn yóò ko o sí inú ìkòkò dúdú náà, wọn ó tún wa eku méjì, ẹja méjì, ìgbín méjì, obì funfun pupa àti adìyẹ, wọn yóò kó gbogbo wọn lọ sí igbó dúdú mínrínmínrín kan níbi tí wọn o ti ṣe ètùtù nípa aláìsàn náà. Bí ó bá sì jẹ́ pé àìsàn náà pa ènìyàn ni bẹ́ẹ̀ náà ni wọn yóò ra gbogbo nǹkan tí a tò sí òkè yìí, wọn yóò ko òkú ẹni tí ó kú yìí pẹ̀lú gbogbo ohun tí wọn ra lọ igbó dúdú tàbí igbó awo tí ó bá wà nítòsí fún ìsìnkú.

Ara àwọn èèwọ̀ Sànpọ̀nná ni pé ènìyàn kò gbọdọ̀ wọ aṣọ pupa ni agbègbè ibi ti Sànpọ̀nná bá ti ń jà. Bákan náà ènìyàn kò gbọdọ̀ fi ọwọ̀ gbálẹ̀ ní ibi tí Sànpọ̀nná bá ti ń jà bí kò ṣe ọ̀ṣẹ̀pòtu. Ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ sun ẹkún níbi tí Sànpọ̀nná bá ti pa ènìyàn kan, àwọn ẹbí àti aládùúgbò ẹni náà gbọdọ̀ máa dúpẹ́ lọ́wọ́ Sànpọ̀nná ni, wọn kò gbọdọ̀ fajúro rárá. Èyí ni wọ́n ṣe ń pe Sànpọ̀nná ni "Alápadúpẹ́". Sànpọ̀nná lè fi ìgbóná tàbí wèrè bá ènìyàn jà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òrìṣà líle ni Sànpọ̀nná jẹ́ síbẹ̀ o máa ń mú kí irè oko dára, ó

sì máa ń pèsè fún àwọn olùsìn rẹ̀. Onírúurú orúkọ ni àwọn Yorùbá máa ń pe Sànpọ̀nná. Lára àwọn orúkọ yìí ni: Olóde, Ọbalúayé àti baba.

## 4.6 Yemọja

Obìnrin ni Yemọja, ó sì tún jẹ ọ̀kan lára àwọn irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀. Ìtàn fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́ ni Yemọja àti Ṣàngó ní ìgbà tí wọ́n wà lóde ọ̀run. Ipò asíwájú ni Yemọja wà láàrin àwọn obìnrin. Ohun tí ìtàn sọ ni pé "Yèyé ọmọ ẹja" ni a gé kúrú sí Yemọja. Ní ìgbà tí ìtàn mìíràn sọ pé "Ìká Ẹlẹ́ja" ni odù ti Yemọja tọ̀ wáyé. Òrìṣà yìí jẹ́ oníwàpẹ̀lẹ́, onísùúrù àti ọlọgbọ́n. Fún ìdí èyí àwọn irúmọlẹ̀ yòókù máa ń fún un ní iyì àti ẹ̀yẹ. Lẹ́yìn tí ó dé ilé ayé, òun àti Ṣàngó tún pàdé, wọ́n sì di tọkọtaya. Ìyàwó méjì, Ọ̀sun àti Yemọja ni Ṣàngó ti fẹ́ ṣaájú Yemọja. Òrìṣà omi ni Yemọja òun sì ni alákòóso gbogbo àwọn ẹ̀dá inú omi, ìtàn fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ó pẹ̀lú àwọn ìyáálé rẹ̀ binu wọlẹ́, tí wọ́n sì di omi ńlá.

Àwọn ohun tí àwọn olùsìn Yemọja fi ń bọ ọ́ ni èkuru funfun, ẹ̀fọ́ yánrin, ègbo, obì ifin, obì ipa aláwẹ́ mẹ́rin mẹ́rin, wọ́n tún máa ń fi ọbẹ̀ ọ̀sìnsìn bọ ọ. Àwọn ohun tí a fi máa ń dá ojúbọ Yemọja mọ̀ ni pèrẹ̀gún, igi ìyeyè, aṣọ iyemọja, àti eésan èkùrọ́. Etí odò ni wọ́n ti máa ń bọ ọ́. Ìyáyì ni olórí àwọn tí ó ń bọ ọ́, ó sì jẹ́ ẹni tí ó ti kúrò lọ́wọ́ ọmọ bíbí tí kò sì ṣe nǹkan oṣù mọ́. Àwọn olùsìn Yemọja kò gbọdọ̀ jẹ ẹja àti ọkà bàbà, bẹ̀ẹ̀ ni wọn kò gbọdọ̀ bọ Yemọja pẹ̀lú orógbó nítorí ó jẹ́ ti Ṣàngó.

Ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn rẹ̀ ni pé ó máa ń fi ọmọ dá àwọn tó bá bèèrè lọ́wọ́ rẹ̀ lọ́lá. Ó sì tún máa ń ṣe ìtọ́jú àwọn ọmọ àti òbí wọn náà, èyí ni wọ́n ṣe máa ń pe Yemọja ni Alágbo-ọ̀fẹ́.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín kẹta módù kìnní yìí ni a ti jíròrò nípa àwọn òrìṣà kan ni ilẹ̀ Yorùbá. A sọ̀rọ̀ nípa ìgbé ayé àwọn òrìṣà yìí àti àbùdá àdání wọn. Àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá pọ̀, fún ìdí èyí a kò lè sọ̀rọ̀ nípa gbogbo wọn tán. Àwọn òrìṣà ti a ń ṣàṣàrò nípa wọn ni Ọ̀rúnmìlà, Ọbàtálá, Ògún, Sànpọ̀nná àti Yemọja. Ohun tí ó dájú ni pé ó ti lè sọ nípa àwọn òrìṣà wọ̀nyí láìfepo bọyọ̀.

Ní ìpín kẹta módù kìnní yìí ni a ti kọ́ pé:

- Ọ̀kan lára àwọn irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ ni Ọ̀rúnmìlà jẹ́
- Ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye tí Ẹlẹ́dàá fún Ọ̀rúnmìlà tayọ tí àwọn òrìṣà yòókù
- Ohun tí Ọ̀rúnmìlà máa ń lo láti mọ ọjọ́ iwájú ènìyàn ni a mọ̀ sí Ifá
- Ọbàtálá/Òrìṣà-Ńlá ni ó mọ ẹ̀dá ènìyàn
- Orúkọ mìíràn fún Ọbàtálá ni Òrìṣà-Ńlá, Ọbalùfọ̀n, Òrìṣà Ìtàpá, Òrìṣà Ìkirè, Ògìyán àti Gbẹ̀gbẹ̀kún-ẹ̀gbẹ̀
- Ògún ni alákòóso ohun gbogbo tí ó bá jẹ mọ́ irin

- Nígbà tí Ògún bá ń sọ ìrírí rẹ̀ tí kò bójú mu, ìrèmọ̀jé ni ó máa ń sun.
- Sànpọ̀nná ni a tún mọ̀ sí baba tàbí alápadúpẹ́
- Sànpọ̀nná máa ń pèsè fún àwọn olùsìn rẹ̀
- "Ìká ẹlẹ́ja" ni odù ti Yemọja tọ̀ wá ayé
- Obìnrin ni gbogbo àwọn tó n bọ òrìṣà Yemọja.
- Ìyayì ni Olórí fún àwọn tó ń bọ Yemọja, ó sì jẹ́ ẹni tí kò ṣe nǹkan oṣù mọ́, tí ó ti kúrò lọ́wọ́ ọmọ bíbí.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣe òrínkínniwín àlàyé lórí mẹ́ta nínú àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá tí o kẹ́kọ̀ọ́ nípa wọn
2. Ṣe lóòótọ́ ni pé Ọ̀rúnmìlà náà ni Ifá?
3. Jíròrò lórí òrìṣà alápadúpẹ́
4. Sọ ohun tí o mọ̀ nípa òrìṣà alágbo-ọ̀fẹ́

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adéoyè, C.L. (1999) *Àṣà àti ìṣe Yorùbá*. Ibadan: O.U.P

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn àṣà àti òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ibadan: Oníbọn-Òjé Press & Book Industries (NIG) Ltd.

Ládélé, T.A.A et. Al (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

# ÌPÍN KẸRIN ÀWỌN ALÁṢEKÙ

## Àkòónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́ẹ̀kó
 4.1 Àwọn Aláṣekù
 4.2 Ẹfúnróyè Tinúubú
 4.3 Mọrèmí Àjàsorò
 4.4 Ẹfúnṣetán Aníwúra
 4.5 Basọ̀run Ògúnmọ́lá
 4.6 Adélabú Pẹnkẹlẹméèsì
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kẹrin módù kìnní yìí ohun tí a ó máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ ni àwọn aláṣekù ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn aláṣekù yìí ni àwọn akíkanjú àti baba-ńlá tàbí ìyá-ńlá àwọn àwùjọ kan tí wọ́n ti kópa ribiribi kí wọn tó fayé sílẹ̀. Ohun tí ó dájú ni pé, ó le ṣàlàyé ni kíkún nípa àwọn kan lára àwọn aláṣekù lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o lè:

- Sọ̀rọ̀ nípa àwọn aláṣekù ní ilẹ̀ Yorùbá
- Jíròrò nípa ìgbé ayé Tinúubú
- Sọ irúfẹ́ ẹ̀dá tí Mọrèmi Àjàsorò jẹ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Dárúkọ́ àwọn akíkanjú akọni tí wọ́n gbajúgbajà ní agbègbè rẹ
2. Ṣe àgbéyẹ̀wò aláṣekù kan ní agbègbè rẹ

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àwọn Aláṣekù

Àwọn aláṣekù ni àwọn tí wọ́n ti gbé ìgbé ayé wọ́n bí ènìyàn. Tí wọ́n jẹ́ akọni àti baba-ńlá àti ìyá-ńlá fún àwọn ènìyàn kan ṣùgbọ́n nípasẹ̀ àwọn ohun ribiribi tí wọ́n ṣe àti ìwà akọni wọn, àwọn ènìyàn wọ̀nyí kò le gbàgbé

wọn ni ìgbà tí wọn kú tán. Sebí Yorùbá bọ̀ wọ́n ní "Ọjọ́ a kú là á dère, ènìyàn kò sunwọ̀n láàyè.

## 4.2 Ẹfúnróyè Tinúubú

Ẹfúnróyè Tinúubú (ẹni tí orúkọ àpètán rẹ̀ ń jẹ́ Ẹfúnporóyè Ọ̀súntinúubú) ni a bí sí agbègbè Ìjokòdó ni Ẹ̀gbá, ní ọdún 1805. Olúmọ̀sà ni bàbá rẹ̀, ìyá rẹ̀ sì ni Níjeedé. Ìdílé Ọlọ́bàtálá ni Níjeedé tí ó jẹ́ ìyá Ẹfúnróyè ti wá, èyí ni ó jẹ́ kí ó sọ ọmọ rẹ̀ ní Ẹfúnporóyè. Orúkọ kejì tí a fún un ni Tinúubú èyí tí o ń ṣe àfihàn pé Ọsun ni o ti inú ibú wá ṣe ìyá rẹ̀ lóore, tí ó sì fún un lọ́mọ, torí inú ọkọ̀ ojú omi ni ìyá Tinúubú bí i sí ní ìgbà tí ó ń rin ìrìnàjò. Oníṣòwò ńlá ni ìyá Tinúubú, èyí ló sì fà á tí Ẹfúnróyè Tinúubú fi jẹ́ onísòwò ńlá fúnra rẹ̀. Gbogbo ohun tí Tinúubú bá dáwọ́lé ni ó máa ń yọrí sí rere nítorí ó já fáfá lẹ́nu iṣẹ́ yòówù tí ó bá ń ṣe. Ìlú Abẹ́òkúta ni Tinúubú lọ́kọ sí, ó sì bí ọmọkùnrin méjì fún ọkọ rẹ̀, ṣùgbọ́n ó seni láàánú pé ó pàdánù ọkọ rẹ̀ lẹ́yìn ọdún díẹ̀ tí wọ́n ṣe ìgbéyàwó. Tinúubú ń bá kárà kátà rẹ̀ lọ́ ní ìlú Abẹ́òkúta lẹ́yìn ikú ọkọ rẹ, bẹ́ẹ̀ nikò pẹ́ sí àsìkò yìí ni Àdèlé wà sí Abẹ́òkúta ó denu ìfẹ́ kọ Tinúubú ní ìgbà tí àwọn méjèèjì sì ti fẹnukò tan, wọ́n ṣe ìgbéyàwó, wọ́n sì lọ sí Àgbádárìgì. Ibí yìí ni wọ́n wà tí àwọn ọmọkùnrin méjèèjì tí Tinúubú bí fún ọkọ rẹ̀ àárọ̀ fi kú. Ọba jíjẹ kan Àdèlé ni Èkó, òun àti Tinúubú sì kúrò ni Àgbádárìgì wá sí ìlú Èkó. Àdèlé kò pẹ́ púpọ̀ lórí ìtẹ́ tí o fi wàjà, lẹ́yìn ikú rẹ̀ Tinúubú tún fẹ́ ọkùnrin méjì mìíràn, Yésúfù Badà, tí ó jẹ́ jagunjagun àti Momoh Bukar Onímọ̀ nínú ẹ̀sìn Mùsùlùmí ṣùgbọ́n kò bí ọmọ kankan fún àwọn ọkọ rẹ̀ méjèèjì yìí. Lẹ́yìn ikú àwọn ọkùnrin méjì ti Tinúubú fẹ́ yìí o pinnu pé òun kò lọ́kọ mọ́, o sì gbájú mọ iṣẹ́ rẹ̀ láì fààyè gba ìdíwọ́ kankan. Oníṣòwò pàtàkì ni Tinúubú, bẹ́ẹ̀ ni lára àwọn nǹkan tí Tinúubú ń tà ni iyọ̀, tábà, ẹní. Èyí nìkan kọ́, bí o ṣe ń ra ilẹ̀ bẹ́ẹ̀ náà ni ó ń ta ilẹ̀. Ojoojúmọ́ ni òwò rẹ̀ ń gbèrú sí i tí o sì di gbajúmọ̀ káàkiri ìlú Èkó àti agbègbè rẹ̀.

Yàtọ̀ sí pé Tinúubú mú iṣẹ́ rẹ̀ ni òkúnkúndùn, o tún jẹ́ ajìjàgbara àti asẹ̀tọ́fábo, torí ó ṣe gudugudu méje àti yàáyàà mẹ́fà nínú òṣèlú Èkó. Gbogbo ìgbà ló ń jà fún ẹ̀tọ́ àwọn ọmọ Èkó, kò sì fún àwọn Òyìnbó amúnisìn láàyè láti jẹ́ gàba tàbí gba ọ̀nà ẹ̀rọ́ ṣe ìjọba ní ìlú Èkó.

Níní ìfẹ́ ìlú ẹni àti ìjàjàgbara Tinúubú ní ìlú Èkó ló jẹ́ kí àwọn ọmọ Èkó mọ rírì Tinúubú tí wọ́n sì ṣe gbàgede kan fún ìrántí àti ìdánilọ́lá rẹ̀, èyí ti wọ́n pè ni Gbàgede Tinúubú ní ìlú Èkó. Torí Yorùbá bọ̀, wọ́n ní dídùn ni ìrántí Olódodo, torí iṣẹ́ wọn ń tọ̀ wọn lẹ́yìn. Ẹfúnróyè Tinúubú gbé ìgbé ayé ìrọ̀rùn àti àlàáfíà, ó sì dàgbére fáyé ní ọjọ́ kìn-ín-ní oṣù kejìlá ọdún 1887 lẹ́yìn àìsàn ránpẹ́. A sin òkú rẹ̀ sí ìlú Abẹ́òkúta ní agboolé ìyá rẹ̀.

## 4.3 Mọ́remí Àjàsorò

Ọ̀fà ni wọn ti bí Àjàsorò ni agboolé Ẹjẹmu, èyí tí ó jẹ́ ìdílé oyè kan pàtàkì ní ìlú Ọ̀fà. Àkọ́bí bàbá Mọ́remí ni Onírà tí ó jẹ́ ọba ìlú Ìrà ní ìtòsí Ọ̀fà;

orúkọ bàbá Mọ́remí ni Akínnuko. Mọ́remí Àjàsorò ni ó jẹ́ ọmọ kejì nínú àwọn ọmọ ìyá rẹ̀, òun ni wọ́n bí tẹ̀lé Onírà, lẹ́yìn rẹ̀ ni wọ́n tún bí àwọn ìbejì méjì lé Mọ́remí. Iṣẹ́ aró dída ni ìyá bàbá Àjàsorò ń ṣe, èyí ni ó sì fi kọ́ ọ. Ìlú Ìkìrun ni a ti bí ìyà Àjàsorò, ìlẹ̀kẹ̀ ni ó sì máa ń tà ní ọjà Èjìgbòmẹkùn àti àwọn ọjà ńlá mìíràn káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Àjàsorò ni ọmọbìnrin kanṣoṣo tí ìyá àti bàbá rẹ̀ ní, èyí ló sì ṣe okùnfà bí ó ṣe padà yan iṣẹ́ ìlẹ̀kẹ̀ lílò láàyò nígbẹ̀yìn. Àbíkẹ́hìn ọmọ Odùduwà, Ọ̀rànmíyàn pàdé ìyá Àjàsorò lọ́jà Èjìgbòmẹkùn níbẹ̀ ni ó sì ti fẹ́ Mọ́remí lọ sí ààfin rẹ̀ ní Ọ̀yọ́. Ọ̀rànmíyàn ló fún Mọ́remí lórúkọ tó di èyí tí gbogbo ayé mọ̀ ọ́n mọ̀. Èdè Ifẹ̀ ni Ọ̀rànmíyàn lò láti fún Mọ́remí lórúkọ “Mọ́wùmí tàbí ọmọ-rè-mí tàbí ọmọ +wù mí’. Ní ìgbà tí ìròyìn kan Ọ̀rànmíyàn pé ìlú bàbá rẹ̀ tí í ṣe Ilé-Ifẹ̀ kò tòrò, ó pinnu láti padà sí ibẹ̀ láti lọ jẹ́ Olúfẹ̀. Ní kété tí Ọ̀rànmíyàn wọ Ilé-Ifẹ̀ ni Ọbalùfọ̀n tí ó jẹ́ adelé Olúfẹ̀ fi orí àpèré sílẹ̀ fún Ọ̀rànmíyàn. Gbogbo ìlàkàkà Ọ̀rànmíyàn láti ṣẹ́gun àwọn ẹ̀yà Ùgbo tó ń kó wọn lẹ́rú pàbó ló já sí. Èyí ló mú Mọ́remí pinnu láti rìn ìrìnàjò lọ sí ilẹ̀ Ùgbo láti lè gba àwọn ènìyàn rẹ̀ sílẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ọ̀rànmíyàn kò faramọ́ ìpinnu yìí ní ìbẹ̀rẹ̀, ní ìgbà tí ó yá, ó fọwọ́ sí i. Mọ́remí sì jọ̀wọ́ ara rẹ̀ fún àwọn Ùgbo láti kó o lẹ́rú. Ní kété tí Mọ́remí dé ìlú àwọn Ùgbo tí Olú-Ùgbò sì fojú kan an, ló ti sọ ọ́ di ayaba rẹ̀. Gbogbo ọgbọ́n àti ète ni Mọ́remí pa láti mọ àsírí àwọn Ùgbò lẹ́yìn èyí ló padà sí Ilé-Ifẹ̀. Pẹ̀lú gbogbo àṣírí àwọn Ùgbò tí ó ti hàn sí Mọ́remí yìí, àwọn ara Ifẹ̀ rẹ́yìn àwọn ẹ̀yà Ùgbò tí ó ń kó wọn lẹ́rú. Kí Mọ́remí tó lọ ìrìnàjò rẹ̀ ló ti kọ́kọ́ lọ sí ọ̀dọ̀ odò Ẹ̀sìnmìrìn láti bèèrè fún àtìlẹ́hìn rẹ̀, ó sì jẹ́jẹ̀ẹ́ pé tí òun bá padà láyọ̀, òun yóò wa rúbọ sí odò Ẹ̀sìnmìnrìn. Láti lè san ẹ̀jẹ́ rẹ̀, Mọ́remí ko ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan lọ láti rúbọ sí Ẹ̀sìnmìnrìn, ṣùgbọ́n sí ìyàlẹ́nu gbogbo ènìyàn Olú-Orogbo tí ó jẹ́ àrẹ̀mọ Mọ́remí ni odò Ẹ̀sìnmìnrìn bèèrè fún. Ní ìkẹyìn a fi Olú-orogbo tí a tún mọ̀ sí ẹ̀là rúbọ sí odò Ẹ̀sìnmìnrìn, àwọn Ifẹ̀ kò sì lè gbàgbé Mọ́remí àti Olú-Orogbo ọmọ rẹ̀ fún ipa ribiribi tí wọ́n kó láti gbà wọ́n sílẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ẹ̀yà Ùgbò.

## 4.4 Ẹfúnṣetán Aníwúrà

Ọmọ Ẹ̀gbá Òkè-Ọnà ni ìpínlẹ̀ Ògùn ni Ẹfúnṣetán Aníwùrà jẹ́. Orúkọ bàbá rẹ̀ ni Ògúnrìndé, nígbà tí ìyá rẹ̀ sì jẹ́ Subúọ̀lá. Ìyàwo àkọ́kọ́ tí Ògúnrìndé fẹ́ kò bímọ fún ọdún mọ́kànlá. Lẹ́yìn èyí ni Ògúnrìndé pàdé Subúọla tí ó sì fẹ́ ẹ. Kò pẹ́ púpọ̀ tí Subúọ̀lá wọ ilé Ògúnrìndé tí o fi bí ọmọbìnrin kan fún uń, èyí tí ó sọ orúkọ rẹ̀ ni, Ẹfúnsèyítán. Ọ̀ṣùpá mẹ́fà lẹ́yìn èyí náà ni Ọsùọ̀lálẹ̀ ìyàwó àkọ́kọ́ tí Ògúnrìndé fẹ náà lóyún, inú Ògúnrìndé dùn pé Subúọ̀lá ló lànà fún ìyàwó àkọ́kọ́, èyí ló sì mú kí ó máa kẹ Subúọ̀lá lójú àti imú, bí o tilẹ̀ jẹ́ pe, ọmọ mẹ́rin ni Subúọ̀lá bí fún Ògúnrìndé, méjì kú, ó sì ku Ẹfúnṣetán àti Akíntúndé, àbíkẹ́yìn tí ó jẹ́ ọkùnrin. Onísòwò obìnrin kan tí ó máa ń wà láti ilẹ̀ Ìjẹ̀ṣà si Ẹ̀gbá ló fi ọ̀nà okòwò hàn Subúọ̀lá, èyí tí ó sọ ọ́ di onísọ̀wò pàtàkì. Ilé ọkọ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Ẹfúnṣetán lọ ṣùgbọ́n tí kò lóyún ààrọ̀ dalẹ́ níbẹ̀. Lẹ́yìn ikú bàbá rẹ̀, Ògúnrìndé, ó lọ bá ìyá rẹ̀ ní ìlú Ìbàdàn, ibẹ̀ ló sì ti pàdé àkọ́bí Oyèsílẹ̀, Oyèbọ̀dé tí í ṣe Abẹṣẹ̀ Balógun, Ẹfúnṣetán sì bí ọmọbìnrin kan fún un. Subúọ̀lá dàgbà, ó sì re ibi àgbà ń

rè, wọ́n sin okú rẹ̀ pẹ̀lú iyì àti ẹ̀yẹ. Gbogbo ipá ni Ẹfúnṣetán sa láti ri pé bàbá ọkọ òun di Baálẹ̀ lẹ́yìn ikú Ọpẹ̀àgbé, lọ́nà àtifi ìmoore hàn sí Ẹfúnṣetán. Lẹ́yìn tí ó di Baálẹ̀, ó sọ Ẹfúnṣetán dii ìyálóde Ìbàdàn. Òkìkí Ẹfúnṣetán ń tan káàkiri ilẹ̀ Yorùbá torí o ti di onísòwò pàtàkì. Ẹfúnṣetán fi ọmọ rẹ̀ obìnrin, Ìyábọ̀dé fún àrẹ̀mọ Balógun Ìbíkúnlé. Lẹ́yìn ikú Ìbíkúnlé, ìjà ńlá bẹ sílẹ̀ láàrin Ẹfúnṣetán àti Akéré tó jẹ Balógun tuntun lórí ẹrú tí Ìyálóde Ẹfúnṣetán tà, gbogbo ìlàkàkà àwọn ènìyàn láti parí ìjà yìí, pàbó ló ń já sí. Èyí mú kí iná ọ̀tẹ̀ máa jó láàrin àwọn olóyè Ìbàdàn àti Akéré, wọ́n si kọ láti bá a lọ si ogun Ìjẹ̀ṣà kejì. Oyèwọ̀ ọmọ Ìbíkúnlé gbà láti tẹ̀lé Akéré lọ sí ogun yìí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àna rẹ, ìyálóde, kì í nílọ̀ pé kò gbọdọ̀ lọ. Kété tí Oyèwọ̀ lọ sógun pẹ̀lú Akéré ni Ẹfúnṣetán ti lọ mú, ọmọ rẹ̀, ìyábọ̀dé kúrò ní ilé Oyèwọ̀. Orí Afárá-Jẹ́gẹ́dẹ́ ni wọ́n pa Oyèwọ̀ àti Akéré sí bẹ́ẹ̀ ni ìròyìn ikú Oyèwọ̀ náà ló sì pa Ìyábọ̀dé ọmọ Ẹfúnṣetán toyúntoyún.

Lẹ́yìn ikú ọmọ rẹ̀, Ẹfúnṣetán di ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ sí ìlú Ìbàdàn lọ́run. Gbogbo àwọn olóyè ìlú pín sí méjì. Kò sí ẹni tó fẹ jẹ Balógun tàbí Basọ̀run Ìbàdàn mọ́. Níkẹyìn Aláàfin Adélù fi Látòóṣa jẹ Ààrẹ-ọ̀nà-kakaǹfò, gbogbo ipá ni Látòóṣà sà láti kápá ìyálóde Ẹfúnṣetán. Ogun ti Ààrẹ Látòóṣà gbé sí àwọn mọ̀lẹ́bí ìyá tó bí bàbá Ẹfúnṣetán ni Òsíẹ̀lẹ̀ Ẹ̀gbá ló fa aáwọ̀ láàrin Ààrẹ Látòóṣà àti Ẹfúnṣetán Aníwúrà, nínú làásìgbò yìí sì ni ìyálóde Ẹfúnṣetán kú sí.

## 4.5 Basọ̀run Ògúnmọ́lá

Ògúnmọ́lá ọmọ Òrìṣàgúnna ni a bí ni Féésú, ìletò kékeré kan lẹ́bàá ìlú Ìwó ni ọdún 1865. Babaláwo ni Ògúnmọ́lá, ìbátan rẹ̀ kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Sùnmọ́lá Láàmọ, tí ó ti kọ́kọ́ tẹ̀dó sí ìlú Ìbàdàn ni ó mú un wá sí Ìbàdàn. Ó tẹ̀dó sí agboolé Láàmọ. Iṣẹ́ babaláwo tí ó ń ṣe ran àwọn jagunjagun ìgbà náà lọ́wọ́. Ó kọ́ iṣẹ́ jagunjagun lábẹ́ Fádáíyà, ẹni tí ó jẹ́ olórí, pàtàkì fún àwọn jagunjagun ní ìlú Ìbàdàn, nígbà náà. Láìpẹ́ ni Ògúnmọ́lá mọ iṣẹ́ ju ọ̀gá rẹ̀ lọ. Ènìyàn kúkúrú, alágbára àti onígboyà ẹ̀dá ni Ògúnmọ́lá. Ìrí Ògúnmọ́lá bani lẹ́rù, gbogbo ènìyàn ló sì bẹ̀rù rẹ̀. Gbogbo àwọn jagunjagun ẹlẹgbẹ́ rẹ ló nífẹ̀ẹ́ rẹ̀, èyí nìkan kọ́, wọn máa ń bọ̀wọ̀ fún un pẹ̀lú ọ̀kan kan. Kì í ṣe pé àwọn ènìyàn dédé fẹ́ràn Ògúnmọ́lá, ó jẹ́ ẹni tí gbogbo ènìyàn fọkàn tán tí wọ̀n nífẹ̀ẹ́, torí ó mọ bí a ṣe ń gbóríyìn tàbí kan sárá fún ẹni tó bá tẹpá mọ́ṣẹ́. Bẹ́ẹ̀ ni gbogbo ènìyàn máa ń gbóríyìn fún Basọ̀run Ògúnmọ́lá fún ọgbọ́n tí ó máa ń lò láti yanjú ọ̀rọ̀ tàbí aáwọ̀ láàrin àwọn jagunjagun láìṣègbè, èyí ló sì mú un gbajúmọ̀ nílé àti lẹ́yìn odi. Jagunjagun tó gbójú gbónu, tí ó sì tún gbóyà ni Ògúnmọ́lá. Nínú ìgbìyànjú rẹ̀ láti jẹ́ kí Ìbàdàn gòkè àgbà kí ó sì lókìkí jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá, Ògúnmọ́lá ja ọ̀pọ̀lọpọ̀ ogun pẹ̀lú ìpinnu ọkan àti akíkanjú. Lára àwọn ogun tí Ògúnmọ́lá lọ tó jà takuntakun tó sì ṣẹ́gun ni Ogun Ìjàyè 1859-1862, ogun kútújẹ̀ 1862-1864, àti ogun Ìjẹ̀bú Ẹrẹ̀ (èyí tí ó ti di Ìjẹ̀bú-Jẹ̀sà) báyìí. Nípasẹ̀ gbogbo ogun tí o ti jà takuntakun tó sì borí ló mú kí àwọn Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀sà, Ẹ̀gbá, Ìjàyè, Òwu, Ìlọrin, Fúlàní àti Ẹ̀fọ̀n bẹ̀rù rẹ̀. Ìwà akíkanjú rẹ̀

láàrin àwọn olórí yòókù ló ṣe okùnfà bí ilẹ̀ Ìbàdàn ṣe lókìkí tí àwọn ìlú Yorùbá yòókù sì ń jowú rẹ̀ títí di òní. Lọ́nà àti dẹ́rubà àwọn alátakò rẹ̀, gbogbo ìgbà ni àwọn onílù rẹ̀ máa ń fi ìlù sọ ohun tí yóò pá àwọn alátakò rẹ̀ láyà. Gẹ́gẹ́ bí olùfẹ́ àlàáfíà àti aṣaájú rere ó bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìjẹkújẹ àti ìwà ìbàjẹ́ Baálẹ̀ Àrẹàgò Aríkúyẹrí tí ó sì dójútì í ní gbangba. Bákan náà, ni ó fòpin sí ìwà àìdara àwọn olùsìn Ṣàngó àti Ṣànpọ̀nná tí wọ́n ń ṣe okùnfà bí àárá ṣe ń pa àwọn ènìyàn tí ó sì ń jó ilé wọn àti àìsàn ilẹ̀ gbígbóná tó di gbajú gbajà lásìkò ìjọba rẹ̀. Gbbogbo ìgbà ló máa ń dífá láti ṣe ìpèsè lọ́nà àti-tu àwọn òrìṣà lójú, kí àlàáfíà àti ìfọ̀kànbalẹ̀ lè wà fún àwọn ènìyàn rẹ̀. Nítorí ìgboyà àti akíkanjú Ògúnmọ́lá, ìgbéga rẹ̀ yá kańnkán láti ipò ọ̀tún Balógun sí Basọ̀run. Basọ̀run Ògúnmọ́lá kú lọ́nà ìyanu àti gẹ́gẹ́ bí akọni ni ọjọ́ kejìdínlọ́gbọ̀n oṣù kejì ọdún 1867. Àwọn tó fi sílẹ̀ sáyé ti sọ ọ́ di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ. Ọdọọdún ni wọ́n máa ń rántí rẹ̀ tí wọ́n sì máa ń rúbọ tí wọ́n sì wúre ní ibojì rẹ̀. Onídàájọ́ òdodo àti olóòótọ́ ènìyàn ni Ògúnmọ́lá, èyí ló sì mú kí àwọn ènìyàn fẹ́ràn rẹ ní ìgbà tó wà láyé àti lẹ́yìn ikú rẹ̀.

## 4.6 Adélabú Pẹnkẹlẹméẹ̀sì

Agboolé Olúòkun ni ìlú Ìbàdàn ni a ti bí Gbàdàmọ́sí Adégòkè Adélabú. Ó jẹ́ ọ̀kan lára díẹ̀ nínú àwọn ọmọ Mùsùlùmí tó ni àǹfààní ẹ̀kọ́ ìwé. Ó lọ sí ilé ẹ̀kọ́ Saint David, Kúdetì, Ìbàdàn àti Yaba College ní ìlú Èkó. Ó jẹ́ ẹ̀dá tí kò ga, tó sì kúrú. Ìdí èyí ni wọn ṣe máa ń kì í "pẹ́ńpẹ́-bí-àṣá, ọkọ Awólọ́wọ̀'. O ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyàwó àti ọmọ. Adélabú jẹ́ ẹni jẹ́jẹ́, ó jáfáfá, bẹ́ẹ̀ ni o jẹ́ ẹni tí ó lawọ́ èyí ni ó sì jẹ́ kí gbogbo ènìyàn fẹ́ràn rẹ̀, pàápàá àwọn mẹ̀kúnù àti àwọn àgbẹ̀. Gbogbo ìgbà ló jẹ́ pé ẹgbẹ́ alátakò ni ó máa ń wà pẹ̀lú àwọn olówó tó kàwé láwùjọ. Adélabú jẹ́ onígboyà, àti ẹni tí ẹnu rẹ̀ gbọ̀rọ̀. Gbogbo ìgbà ni ó máa ń wàyá ìjà pẹ̀lú ìjọba. Ó lè sọ èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Yorùbá dáadáa. Adélabú kì í ṣe ẹlẹ́yàmẹ̀yà. Gbogbo ìgbà tí o bá ń jáde lọ fún ìpàdé ẹgbẹ́ òṣèlú ni àwọn olórin Mùsùlùmí àti ìbílẹ̀ máa ń bá a jáde. Ìfẹ́ gbogbo ènìyàn tí ó ní, tí ó sì kó wọn mọ́ra ló jẹ́ kí o di gbajúmọ̀ káàkiri ilẹ̀ Yorùbá.

Adélabú wà lára àwọn olóṣèlú àkọ́kọ́ ni Orílẹ̀èdè Nàìjíríà tí wọ́n dá ẹgbẹ́ olóṣèlú sílẹ̀ lásìkò ìjàjàgbara kí orílẹ̀èdè Nàìjíríà tó gba òmìnira. Ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ti àwọn aṣáájú bíi Marculay àti Azikwe nífẹ̀ẹ́ sí, ó sì darapọ̀ mọ́ wọn gẹ́gẹ́ bí ikọ̀ alágbára láti jà fún òmìnira Nàìjíríà. Ó tún jẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọniyàn àti ọlọ́gbọn dorí ẹja mú tí ó máa ń fàyà rán ìṣòro àti wàhálà pẹ̀lú àwọn olórí tó ń ṣe ìjọ̀ba. Adélabú jẹ́ ẹni tí ó ní ìmọ̀ púpọ̀ nípa ìtàn ó sì tún jẹ́ sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀. Ó ka ìtàn ìbàdàn, ó sì yé e, ó sì mọ bí ó ti ṣe lè ṣàmúlò ìtàn Yorùbá láti ṣe àǹfààní fún ìlépa rẹ̀ nínú òṣèlu. Ó lo ìkórìíra àti owú tí ó wà láàrin Ìbàdàn àti Ìjẹ̀bú, èyí tí ó jẹ́ àyọrísí ogun àti ìjà tí ó wáyé láàrin àwọn jagunjagun bí i Ibíkúnlé, Ògúnmọ́lá àti àwọn mìíràn fún àǹfààní ara rẹ̀. Olóṣelú àti àgbàọ̀jẹ̀ ni Adélabú jẹ́; èyí ló sì mú gbajúmọ́, pàápàá nínú ẹgbẹ́ rẹ̀ N.C.N.C àti gbogbo ilẹ̀ Yorùbá. Adélabú jẹ́ olùfẹ́ àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá, gbogbo ipá rẹ̀ ló sì máa ń sà láti rí i pé Yorùbá kò parun. Adélabú lawọ́,

bẹ́ẹ̀ ni o kóni mọ́ra. Kò lójúkòkòrò bẹ́ẹ̀ ni kò kó ọrọ̀ ayé mọ́yà. Adélabú kú nínú ìjàm̀bá mọ́tò ni ìrọ̀lẹ́ ọjọ́ ìsẹ́gun, ọjọ́ karùndínlọ́gbọ̀n oṣù kẹta ọdún 1958. Títí di òní olónìí ni àwọn ọmọ Ìbàdàn àti àwọn ọmọ Yorùbá ń ṣe ìrántí Adélabú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìpín kẹrin, módù kìnní yìí, a ti sọ̀rọ̀ nípa àwọn aláṣekù tí wọ́n kó ipa ribiribi nígbà tí wọ́n wà láàyè, èyí tí ó sì jẹ́ kí àwọn ẹbí, ará àti ọ̀rẹ́ pẹ̀lú àwọn ènìyàn ìlú wọn máa ṣe ìrántí wọn lẹ́yìn tí wọ́n ti papòdà. Ṣebí Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ọjọ́ a kú là á dère, ènìyàn kò sunwọ̀n láàyè. Àwọn aláṣekù tàbí òkú ọ̀run tí a sọ̀rọ̀ nípa wọn ni Ẹfúnróyè Tinúubú, Mọ́remí Àjásorò, Ẹfúnsetán Aníwúrà, Basọ̀run Ògúnmọ́lá àti Adélabú Adégòkè Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì

Nínú ìpín kẹrin módù kìnní, a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé:

- Àwọn aláṣekù jẹ́ àwọn baba-ńlá tàbí ìyá-ńlá ìran kan tó kó ipa ribiribi ní ìgbà tí wọ́n wà láàyè
- Ọdún 1805 ni a bi Ẹfúnróyè Tinúubú
- Ìlú Abẹ́òkúta ni Tinúubú lọ́kọ sí
- Oníṣòwò Iyọ̀, Tábà àti Ẹni ni Tinúubú
- Tinúubú dágbére fáyé ni ọjọ́ kìnní oṣù kejìlá ọdún 1887.
- Mọrèmi ló gba àwọn Ifẹ̀ lọ́wọ́ ẹ̀yà Ùgbò tí ó ń kó wọn lẹ́rú
- Mọrèmi fi ọmọ rẹ̀ kanṣoṣo, Olú-Orogbo rúbọ sí odò Ẹ̀sìnmìrìn
- Ọmọ Ẹ̀gbá Òkè-Ọnà ni Ẹfúnṣetán Aníwwúrà jẹ́
- Bàbá ọkọ Ẹfúnṣetán ló fi jẹ oyè Ìyálóde Ìbàdàn
- Nínú làásìgbò tó wáyé láàrin ààrẹ Látòósà àti Ẹfúnṣetán ni ó ti dágbére fáyé
- Ní ìletò kan nítòsí Ìwó ni wọn ti bi Basọ̀run Ògúnmọ̀lá ní ọdún 1865
- Alágbára, Olóòótọ́, onídàájọ́ òdodo àti akọni ni Ògúnmọ̀lá
- Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ogun ni Ògúnmọ́lá jà, tí ó sì ṣẹ́gun
- Akitiyan àti ìgbòkègbodò Basọ̀run Ògúnmọ̀lá ló sọ ìlú Ìbàdàn di gbajú-gbajà káàkiri ilẹ̀ Yorùbá
- Ọdọọdún ni àwọn ènìyàn ìlú Ìbàdàn máa ń gbàdúrà, tí wọ́n si máa ń rúbọ ní ibojì Basọ̀run Ògúnmọ̀lá.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣàlàyé kíkún nípa àwọn aláṣekù ní ilẹ̀ Yorùbá
2. Jíròrò nípa irúfẹ́ ẹ̀dá ti Mọrèmi jẹ́
3. Irúfẹ́ ìgbé ayé wo ni Ẹfúnróyè gbé ni ìgbà tó wà láyé

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adéoyè, C.L. (1999) Àṣà àti ìṣe Yorùbá. Ibadan: O.U.P

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). Àwọn àṣà àti òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ibadan: Oníbọn-Òjé Press & Book Industries (NIG) Ltd.

Ládélé, T.A.A et. Al (2006). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

## ÌPÍN KARÙN-ÚN ÀBÙDÁ ÀDÁNI ÀWỌN ẸDÁ ÌTÀN ÌGBÀANÌ

**Àkòónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àbùdá Àdáni Àwọn Ẹdá Ìtàn Ìgbàanì
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín karùn-ún módu kìnní yìí, ohun tí ó máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ ní àbùdá àdáni àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì tí a sọ̀rọ̀ nípa ìgbé ayé ìtàn ìgbàanì tí a sọ̀rọ̀ nípa ìgbé ayé wọn. Ohun tí ó dájú ni pé àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì yìí ní àwọn àbùdá kan tàbí òmíràn tí ó yà wọ́n sọ́tọ̀, èyí tí wọ́n fi di gbajúmọ̀ àti mánigbàgbé ni àwùjọ.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó lè:

- Sọ̀rọ̀ nípa àbùdá àdáni àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì tí a gbé yẹ̀wò
- Pààlà láàrin àbùdá àdáni ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì kan sí èkejì

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Sọ àwọn àbùdá àdání ti ẹ̀dá ìtàn ìgbàani kan ni agbègbè rẹ ní
2. Ṣe àfiwé àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàani méjì tí o mọ̀

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àwọn àbùdá àdáni àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì.

Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì kọ̀ọ̀kan tí a ti ṣe àgbéyẹ̀wò wọn nínú módù kìnní yìí ló ní àbùdá àdáni wọn tí ó yà wọ́n sọ́tọ̀ sí àwọn ẹ̀dá yòókù nínú àwùjọ. Ní báyìí, a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá wọ̀nyí, a ó sì máa tọ́ka sí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì kọ̀ọ̀kan bí ó ṣe yẹ.

**i.** **Àbímọ̀/Àjẹbí –** Ọ̀rúnmìlà gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì jẹ́ ọlọ́gbọ́n. A tilẹ̀ fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ nínú ìtàn ẹ̀dá ìtàn yìí pé ọgbọ́n àti ìmọ̀ ẹ̀dá ìtàn yìí tayọ tí àwọn ẹ̀dá àti òrìṣà mìíràn. Ìmọ̀ àti òye tí ó

jẹ́ àbímọ́ fún Ọ̀rúnmìlà yìí ló sọ ọ́ di pàtàkì tí àwọn ẹ̀dá yòókù sì ń tọ̀ ọ́ lọ fún ìmọ̀ràn nípa ìgbé ayé wọn. Ọ̀rìṣà-Ńlá náà bí ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ni o mọ gbogbo ẹ̀dá ènìyàn bí o ti wù ú, kì í ṣe gbogbo ènìyàn ló le ṣe irúfẹ́ iṣẹ́ báyìí. Ọ̀rìṣà ṣànpọ̀nná jẹ́ ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì tí àwọn ènìyàn ń wárìrì fún nítorí agbára tí ó ní láti pa àwọ̀ ènìyàn dà. Ẹfúnṣetán Aníwúrà, Tinúubú àti Mọ́remí jẹ́ akọni obìnrin tí wọ́n ni ìmọ̀ àjẹmọ kan tàbí òmíràn tí ó mú wọ́n tayọ láàrin àwọn ẹgbẹ́ wọn yòókù.

**ii.** **Ipò tó léwu –** ọ̀pọ̀ àwọn aláṣekù tí a ṣe àgbéyẹ̀wò wọn nínú ìtàn ìgbàanì ló la ipò kan tàbí òmíràn tí ó léwu kọjá. Mọrèmi Àjàsorò fi ara rẹ̀ sílẹ̀ fún àwọn ẹ̀yà Ùgbò láti kó o lẹ́rú, nítorí ìfẹ́ pàtàkì tí ó ni sí àwùjọ tí ó wà àti ìfẹ́ inú rẹ̀ láti rí í pé àwọn Ifẹ̀ bọ́ lọ́wọ́ ìkónilẹ́rú àti ìfìyàjẹni àwọn ẹ̀yà ùgbò. Bákan náà, Tinúbú ja fitafita nítorí àwọn ará Èkó kò fi ààyè gba àwọn òyìnbò amúnisìn láti jẹ́ gàba le àwọn ará Èkó lórí bẹ́ẹ̀ ni kò jẹ́ kí àwọn amúnisìn yìí gba ọ̀nà ẹ̀rọ̀ láti ṣe ìjọba ní ìlú Èkó. Oríṣìíríṣìí ewu ni Basọ̀run Ògúnmọ́lá là kọjá láti wá ìfọ̀kànbalẹ̀ fún àwọn ènìyàn ìlú Ìbàdàn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ogun ló jà lọ́nà àtirí í dájú pé Ìbàdàn gòkè àgbà, ó sì lókìkí jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá. Kèrémì kọ́ ni ewu ti Basọ̀run Ògúnmọ́lá là kọjá kí ó tó fòpin sí ìwà àìdára tí àwọn olùsìn Ṣàngó àti Ṣànpọ̀nná ń hù nípa fífi ààrá pa àwọn ènìyàn tí wọ́n sì ń jó ilé wọn pẹ̀lú.

**iii.** **Àrímọ́-** Àwọn Yorùbá bọ̀, wọ́n ni “ìrí tí a bá rí ọmọ, làá ṣe àna rẹ̀” àti pé “bí a ṣe rìn làá koni”. Èyí túmọ̀ sí pé ìrí ènìyàn ní ọ̀pọ̀ ìgbà á máa ṣe àfihàn irúfẹ́ ẹ̀dá tí ènìyàn jẹ́. Ògún gẹ́gẹ́ bí òrìṣà jẹ́ ẹni tí ìrírí rẹ̀ bani lẹ́rù, àwọn ènìyàn máa ń gbàdúrà ni gbogbo ìgbà pé kí àwọn máṣe rí ìbínú Ògún, torí àrímọ́ rẹ̀ bani lẹ́rù púpọ̀ àti pé ìsọwọ́jà rẹ̀ máa ń le. Bákan náà ni Ṣànpọ̀nná máa ń bani lẹ́rù, torí bí ó bá bínú tán, ó máa ń fi ìgbóná àti ọdẹ-orí bá àwọn tí ó bá bínú sí jà; bẹ́ẹ̀ ni bi Ṣànpọ̀nná bá pa ènìyàn, wọ́n kò gbọdọ̀ sunkún, ṣe ni wọn yóò máa dúpẹ́ lọ́wọ́ Ṣànpọ̀nná. Ìdí èyí ni wọ́n sì fi máa ń pè é ní alápadúpẹ́.

**iv.** **Bíborí Ìṣòro –** Kò sí ọ̀kan nínú àwọn òrìṣà tàbí aláṣekù tí a sọ̀rọ̀ nípa wọn tí wọn ko kojú ìṣòro ṣùgbọ́n nípa ìforítì àti ìfàyàrán wọn, wọn borí ọ̀pọ̀ nínú àwọn ìṣòro wọ̀nyí, àwọn ènìyàn àwùjọ sì kan sáárá sí wọn. Ògún ni ó fi àdá bàbà rẹ̀ la ọ̀nà fún àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù dé Ifẹ̀ Oòdáyé. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìsòro ni Ògún kojú nígbà tí ó lọ sọdẹ tí gbogbo aṣọ rẹ̀ sì fi gbó mọ́ ọn lára. Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé ìhòhò ní ó wà kí ó tó padà sí inú ìlú, èyí ló sì sọ ọ́ di ẹni tí ó ń fi imọ̀kímọ̀ bora, síbẹ̀ Ògún borí gbogbo ìlàkọjá rẹ̀. Ẹfúnṣetán Aníwùrà, ìyálóde Ìbàdàn kojú ọ̀pọ̀lọpọ̀ wàhálà àti inúnibíni torí pé ọlá àti ọrọ̀ rẹ̀ ju ti ọ̀pọ̀ àwọn ìjòyè lọ. Èyí nìkan kọ́, ilé ọkọ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Ẹfúnṣetán lọ tí kò lóyún ààrọ̀ dalẹ̀ níbẹ̀. Pẹ̀lú àforítì àti ìlàkàkà rẹ̀,

ó bí ọmọbìnrin kan nígbẹ̀yìn. Ṣebí Yorùbá bọ̀, wọ́n ni, "Sùúrù lè ṣe òkúta jinná". Sùúrù àti ìpamọ́ra tí Mọremí Àjàsorò ní náà ni o jẹ́ kí o lè rí àsírí àwọn ẹ̀yà Ùgbò tí ó ń kó wọn lẹ́rú, èyí ló sí mú àwọn Ifẹ̀ borí ìṣòro wọ́n, tí wọ́n sì tipa bẹ́ẹ̀ ní ìfọ̀kànbalẹ̀.

v. **Ẹ̀bùn Àtinúdá –** Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú Ọ̀rúnmìlà ni ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye èyí tí ó tayọ tí ẹ̀dá tàbí òrìṣà yòókù. Ọgbọ́n tí Ọ̀rúnmìlà ní yìí ló sì máa ń lò láti ran àwọn ènìyàn lọ́wọ́ ní ìgbà tí wọ́n bá ní ìṣòro kan tàbí òmíràn. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń kì í ni "Akérefinúsọgbọ́n". Ọbàtálá ni tirẹ̀ ni Olódùmarè fún ni àǹfààní láti fi erùpẹ̀ mọ ẹ̀dá ènìyàn. Bí ó bá ṣe wu Òrìṣà-ńlá ni ó máa ń dá ènìyàn, ó lè dá ẹlòmíràn kí ó suké, ya ààfin tàbí kó yọ gẹ̀gẹ̀ lọ́rùn. Ẹ̀bùn àtinúdá tí Ọbàtálá ní yìí jẹ́ èyí tí ẹnikẹ́ni kò le è bi í lẹ́jọ́ pé báwo ló ṣe da òun. Bí Ọbàtálá bá ṣe dáni bẹ́ẹ̀ náà ni ènìyàn yóò gbà. Ìdí èyí ni wọ́n ṣe ń pè é ni "Adánibótirí. Òrìṣà Ṣànpọ̀nná náà lágbára láti yí àwọ̀ ènìyàn padà nípasẹ̀ ìgbóná, irúfẹ́ àwọn tí ọwọ́jà Ṣànpọ̀nná bá bà ni wọ́n máa ń kì ni "Ẹni baba ṣe lọ́sọ̀ọ́". Bí ó bá tún wú Ṣànpọ̀nná, o lè ya ẹni tí ó bá bínú sí ní wèrè kí Olúwarẹ̀ sì máa ṣe kántankàntan. Nítori gbogbo ẹ̀bùn àtinúdá tí a ti mẹ́nubà lókè yìí, àwọn ènìyàn bẹ̀rù àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì wọ̀nyí.

vi. **Òkìkí –** Èyí ló jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá àdáni tí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ní. ọ̀rúnmìlà tí ó jẹ́ Ẹlẹ́rìí-ìpín jẹ́ olókìkí ẹ̀dá nítorí pé láti ìgbàanì títí di òní olónìí ni àwọn ènìyàn tí ó bá ní ìsòro kan tàbí òmíràn máa ń lọ̀ sí ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmílá. Àwọn tí ó bà tún fẹ́ ní ìmọ̀ nípa ọjọ́ iwájú wọn pẹ̀lú máa ń tọ Ọ̀rúnmìlà lọ́ fún ìtọ́sọ́nà. Gbogbo ẹ̀dá ènìyàn tí ó bá ni ohun kan tàbí òmíràn láti ṣe pẹ̀lú ìrìn ló máa ń wárí àti sín Ògún, èyí sì jẹ́ kí òkìkí rẹ gbilẹ̀ ní ilé àti oko. Títí ayé ni àwọn olùgbé àti ọmọ ìlú Ìbàdàn yóò máa rántí Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà fún gbogbo ìgbòkègbodò rẹ̀ àti ìgbésẹ̀ tí ó gbé kí ó tó di ìyálóde ilẹ̀ Ìbàdàn. Basọ̀run Ògúnmọ́lá àti Adélabú Adégòkè Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì jẹ́ jagunjagun àti Ajàfẹ́tọ̀ọ́ tí ó ṣiṣẹ́ láì sàárẹ̀, èyí sì fún un ni òkìkí ní Ìbàdàn àti káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Tinúubú gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì náà jẹ́ olókìkí ẹ̀dá, ipa àti ipò rẹ̀ ní ìlú Èkó àti agbègbè rẹ̀ ní a sì ń ṣe ìrántí títí di òní. Mọremí Àjàsorò lókìkí ní ilé-Ifẹ̀ àti láàrin àwọn Yorùbá nítorí pé ó fi ọmọ rẹ̀ kanṣoṣo rúbọ fún odò Ẹ̀sínmìnrìn fún ìdáǹdè àwọn ènìyàn Ifẹ̀. Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì tí a sọ̀rọ̀ nípa wọn ni wọ́n jẹ́ olókìkí ẹ̀dá.

vii. **Kíkú Ikú Akọni –** Yemọja, ọ̀kan lára àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì jẹ́ alágbára àti alákòóso gbogbo àwọn ẹ̀dá inú omi, ó kú ikú akọni, nítorí ó bínú wọlẹ̀ ni, tí ó sì dí omi ńlá. Ẹfúnṣetán Aníwúra náà kú ikú akọni ni, ó subú lójú ìjà, nínú làásìgbò tó wáyé láàrin òun àti Ààrẹ Látóòsà ló ti dágbére fáyé. Basọ̀run Ògúnmọ́lá gẹ́gẹ́ bí jagunjagun náà ju awà sílẹ̀ lọ́nà ìyanu àti gẹ́gẹ́ bí akọni. Adélabú Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì náà gẹ́gẹ́ bí ajafẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn kú ikú akọni, àwọn

ọmọ ìlú Ìbàdàn kò sì le gbàgbé rẹ̀ láéláé. Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì wọ̀nyí ni wọn kò ro ti ẹ̀mi wọn, wọ́n forí la ikú ní ọ̀pọ̀ ìgbà wọn kò sì rẹ̀wẹ̀sì láti já fún àwọn ènìyàn wọn títí dé ojú ikú.

**viii. Oògùn àti Agbára –** Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ni wọ́n gbójú, gbónu, gbóyà, tí wọ́n sì lóògùn. Gbogbo agbára àti oògùn ni Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà lò láti kápá àwọn ọ̀tá àyíká rẹ̀. Èyí nìkan kọ́, ó lo agbára àti òògùn láti lè kojú Ààrẹ Látóòsà, ó sì hàn gbangba pé alágbára obìnrin ni Ẹfúnṣetán, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó padà subú lójú ìjà. Jagunjagun ògúnná gbòǹgbò tí ó ń játọ́ lẹ́nu ìgbín ni Basọ̀run Ògúnmọ́lá ní ìgbà ayé rẹ̀, nípa òògun àti agbára àìrí, O jà, o sì ṣẹ́ ogun Ìjàyè, Kútúje àti ògun Ìjẹ̀bú. Adélabú Adégòkè Pẹnkẹlẹmẹ́ẹ̀sì náà ṣàmúlò òògùn àti agbára púpọ̀- púpọ̀. Èyí ló sì jẹ́ kí àwọn ènìyàn máa bẹ̀rù rẹ nítorí pé wọ́n gbàgbọ́ pé kò sí ohun tí kò lè ṣe tàbí ara tí kò lè dá pẹ̀lú òògùn àti agbára rẹ̀, èyí ló sì sọ ọ́ di ẹni tí gbogbo ènìyàn ń wárí fún, kì í ṣe ní ìlú Ìbàdàn nìkan, ṣùgbọ́n ní gbogbo ilẹ̀ káàárò-oò-jíire.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Àwọn àbùdá àdáni àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ni a ṣàlàyé nípa wọn ní ìpín karùn-ún módù kínní yìí. Àwọn àbùdá àdáni tí a sọ̀rọ̀ nípa wọn ni àbímọ́/àjẹbí, wíwà ni ipò tó léwu, Àrímọ, bíborí ìsòro, níní ẹ̀bùn àtinúdá, kíkú ikú akọni àti níní agbára àti òògùn.

Nínú ìpín karùn-ún módùù kínní yìí a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé

- Àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ni àwọn àbùdá àdáni tó yà wọn sọ́tọ̀ sí àwọn ẹ̀dá mìíràn láwùjọ
- Àbímọ́ tàbí àjẹbí ni àwọn ọgbọ́n, ìmọ̀ tàbí oyè tí àwọn ẹ̀dá ìtàn kan ní
- Àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì máa ń wà ní ipò tó léwu lọ́pọ̀ ìgbà
- Ìrí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì wọ̀nyí a máa bani lẹ́rù
- Àwọn ẹ̀dá-ìtàn ìgbàanì wọ̀nyí máa ń la ọ̀pọ̀ ìsòro kọjá ṣùgbọ́n wọ́n máa ń borí rẹ̀
- Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀bùn àtinúdá tí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì wọ̀nyí ni máa ń ràn wọ́n lọ́wọ́
- Òkìkí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì máa ń tàn káàkiri fún ìṣe akọni wọn
- Ikú akọni ni àwọn ẹ̀dá ìtàn yìí sábà máa ń kú
- Àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì máa ń ní òògùn àti agbára

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣe ọ̀rínkíniwín àlàyé nípa àwọn àbùdá àdáni tí àwọn ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì ní
2. Jíròrò nípa àwọn àbùdá àdání yìí bí o ti hàn nínú ayé ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì kan
3. Pàálà láàrin àbùdá ẹ̀dá ìtàn ìgbàanì méjì tí ó wù ọ

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adéoyè, C.L. (1999) Àṣà àti ìṣe Yorùbá. Ibadan: O.U.P

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). Àwọn àṣà àti òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ibadan: Oníbọn-Òjé Press & Book Industries (NIG) Ltd.

Ládélé, T.A.A et. Al (2006). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

## MÓDÙ KEJÌ ÌTÀN ÀLỌ́

Ohun tí a ó máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ nínú módù kejì yìí ní ìtàn àlọ́ èyí tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀yà ìtàn Yorùbá. A ó sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ìtàn àlọ́ jẹ́, bẹ́ẹ̀ ní a ó tún tẹ̀síwájú láti ṣe ìpínsísọ̀rí ìtàn àlọ́. Èyí ni onírúurú ọ̀nà tí a lè pín ìtàn àlọ́ sí. Àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ tún jẹ́ ohun mìíràn tí a o tún máa mẹ́nubà nítorí pé ìtàn àlọ́ ní ìlànà tí a ń gbà gbé e kalẹ̀. Àwọn ẹ̀dá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá nínú ìtàn àlọ́ ṣe kókó a ó sì rí i dájú pé a rí àlàyé kíkún gbà nípa rẹ̀. Ní ìparí, a o ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣìí ìwúlò tí ìtàn àlọ́ ní.

Ìpín Kìnní Ohun tí Àlọ́ jẹ́
Ìpín Kejì Ìpínṣíṣọ̀rí Àlọ́
Ìpín Kẹta Kókó tó Máa ń jẹyọ Nínú Àlọ́
Ìpín Kẹrin Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Àlọ́
Ìpín Karùn-un Ìwúlò Àlọ́

## ÌPÍN KÌNNÍ OHUN TI ÌTÀN ÀLỌ́ JẸ́

### Àkòónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́ẹ̀kọ́
    4.1 Ohun tí ìtàn àlọ́ jẹ́
    4.2 Àbùdá Àlọ́
    4.3 Orísun Àlọ́
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtókasí

### 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kìnní, módù kejì yìí ni a ti mọ ohun tí ìtàn àlọ́ jẹ́, àwọn àbùdá ọlọ́kanòjọ̀kan tí ìtàn àlọ́ ní àti orísun àlọ́, nítorí pé okùn kò le gùn gùn ká má mọ orísun rẹ̀

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó lè:

- Ṣàlàyé ní kíkún ohun tí ìtàn àlọ́ jẹ́
- Sọ àwon àbùdá tí àlọ́ ni
- Ṣe àgbéyẹ̀wò orísun àlọ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Jíròrò lórí àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ méjì tó jẹ́ gbajúgbajà láwùjọ Yorùbá
2. Sọ àlọ́ onítàn kan tí o ti gbọ́ rí

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ohun tí ítàn àlọ́ jẹ́

Àlọ́ jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń gbà láti kọ́ ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ èyí tí ó ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìgbàgbọ́ àti ìṣesí àwọn Yorùbá hàn. Àlọ́ ni a lè pè ní ọmọ ìtàn, èyí tí a máa ń pa láti sọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ní ọjọ́ pípẹ́ séyìn láti lè fi eléyìí kọ́ ọmọdé bí a ṣe ń ronú jinlẹ̀ fún ìmọ̀ àtinúdá àti láti dárayá lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́ wọn. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni àwọn Yorùbá máa ń sọ pé "Ọmọdé ló ni àlọ́, àgbà ló nìtàn". Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé àgbà ló máa ń pá àlọ́ fún àwọn ọmọdé. Asúfèé yàgbàdo, fara jole, fara jolóko ni àlọ́ jẹ́ nínú ewì àtẹnudẹ́nu Yorùbá. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé àlọ́ máa ń yàtọ̀ sí àwọn ewì àtẹnudénu Yorùbá yòókù. Ní ìgbà mìíràn, ìbẹ̀rẹ̀ àlọ́ máa ń dàbí ìgbà tí a ń ke ewì, ìgbà mìíràn ó sì lè jẹ́ ọ̀rọ̀ wuuru.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni àwọn onímọ̀ ti o ti fún àlọ́ ní oríkì kan tàbí òmíràn. Ní èrò Ọ̀pádọ̀tun (1994:1) àlọ́ jẹ́ oríṣìí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí a máa ń lò fún ìdárayá, ìgbádùn àti ìkónilẹ́kọ̀ọ́. Àlọ́ ìjàpá àti àlọ́ àpagbè ni àwọn onímọ̀ bíi Òjó (2005) àti Babalọlá (1978) pé àlọ̀ tẹ̀lẹ̀ ṣùgbọ́n ó dájú pé orúkọ yìí kò kógojá nítorí kì í ṣe ìjàpá nìkan ni ẹ̀dá ìtàn tí ìtàn àlọ́ máa ń dá lé lórí. Àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn bí ẹyẹ, kòkòrò, iwin àti àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn náá máa ń kópa nínú ìtàn àlọ́. Fún ìdí èyí, ìtàn àlọ́ ni orúkọ tí ó ṣe ìtẹ́wọ́gbà yálà ó jẹ́ nípa ìjàpá tàbí àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn tàbí èyí tí ó ni orin ègbè tàbí èyí tí kò ní.

### 4.2 Àbùdá àlọ́

Àbùdá kan pàtàkì tí àlọ́ ní ni pé àwọn ohun tó wà ní àrọ́wótó tàbí àyíká ni ó máa ń jẹyọ nínú àlọ́. A máa ń bá ènìyàn, ẹyẹ, ẹranko, iwin àti àkúdàáyá pàdé nínú ìtàn àlọ́. Èyí nìkan kọ́, àwọn ohun abẹ̀mí àti aláìlẹ́mìí náà máa ń ní àjọṣepọ̀ nínú àlọ́. Nínú ìtàn àlọ́, a kìí lo orúkọ abáyému fún àwọn ẹ̀dá ìtàn nítorí pé èyí lè dá rúgúdù sílẹ̀ láàrin ẹni tí ó ń pa àlọ́ àti ẹni tí orukọ rẹ̀ bá papọ̀ pẹ̀lú ti ẹ̀dá ìtàn tí a bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà àìdára tí ó hù. Èyí nìkan kọ́, bí ẹni tí ó ń pa àlọ́ bá tún lo orúkọ ajẹmẹ́sìn fún ẹ̀dá ìtàn tí ó hu ìwà ìbàjẹ́ nínú àlọ́, àwọn ẹlẹ́sìn bẹ́ẹ̀ lè máa fi apá jánú pé ẹni tí ó ń pa àlọ́ náà ń tàbùkù ẹ̀sìn àwọn ni. Lọ́nà àti yàgò fún wàhálà tàbí dúkùú apàlọ́ kì í lo orúkọ abáyému fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹ̀yà ewì alohùn yòókù, àlọ́ náà ní àgbékalẹ̀ tirẹ̀., àlọ́ ìsàlẹ̀ yìí jẹ́ àpẹẹrẹ ọ̀nà ìgbé àlọ́ kalẹ̀:

Apàlọ́: Ààlọ́ o
Agbálọ̀ọ́: Ààlọ̀
Apàlọ́: Ní ìgbà láéláé, iyá kán wà tí ó bí ọmọbìnrin kan.

Ọmọ náà dúdú bíi kóró isin. Ó sì rẹwà bí ọ̀sùngbàgbá etí odò. Ọmọ náà dára ju ayaba tí ó wà ní ààfin lọ. Ṣùgbọ́n kọ́kọ́rọ́ kan wá ba ẹyín ajá jẹ́. À ní eyín dára, àìní ojú ni ó bà á jẹ́. Bẹ́ẹ̀ sì ni ejò dára, ìwà-ìkà ni àléébù ejò. À ní bí ajá Òyìnbó ṣe dára tó, àléébù rẹ̀ ni àìlè ṣe ọdẹ. Bi ọmọ yìí ṣe dára tó, kò ni eyín ẹyọ kan ṣoṣo lẹ́nu. Ṣe ẹ̀gbin pátá fi ara pámọ́ sí ibi kọ́lọ́fín, ẹ̀gbin ṣòkòtò wà ní ibi tó ṣóòkùn. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni àléébù ọmọbìnrin yìí kò hàn sí. Ohun tí gbogbo ayé ṣá à mọ̀ ni pé kì í rẹ́rìn-ín. Èrò ọ̀pọ̀ ènìyàn ni pé kò rẹ́rìn-ín nítorí pé kò tẹ́ ẹ lọ́rùn láti fi àwọn tó wá ṣe ọkọ ni.

Lẹ́yìn tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ti pòòyì láti fi ọmọ náà ṣe ìyàwó, ó gbà láti fẹ́ Ọba ìlú kan. Ọba náà fi ilé pọntí, ó fi ọ̀nà rokà, ó sì fi gbogbo agbada dinran ni ọjọ́ ìgbéyàwó. Ó náwó náà bí ẹlẹ́dà, àfi bí ẹni pé kò ni ìyàwó rí, èyí ló sì kọ́ ń bí àwọn Olórí mẹ́fà yòókù nínú, ṣùgbọ́n ìbínú wọn túbọ̀ ga sí i nígbà tí wọ́n rí ọmọ náà sójú tí wọn sì rí i pé ó dára bí egbin. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, 'ẹni tí à ń sọ́ kò ṣoro í mú', báyìí ni wọn bẹ̀rẹ̀ sí í wá àléébù Olórí tó dè tí kò pọ́ṣù tí ó fi di ààyò Ọba. Ibi tí wọn ti ń wádìí rẹ̀ ni wọ́n ti gbọ́ pé kò ni eyín ni kì í jẹ́ kí ó rẹ́rìn-ín. Wọ́n sún ọ̀rọ̀ yìí sí Ọba létí. Ọba sì rò ó pé àléébù ni yóò jẹ́ fún òun láti fẹ́ ìyàwó tí kò léyín. Ó wà dá ọjọ́ méje fún ìyàwó náà pé òun yóò pé kí ó ṣí eyín ẹnu rẹ̀. Ó ní bí ìyàwó kò bá ni eyín, òun yóò pa á. Ṣùgbọ́n bí ó bá ni eyín òun yóò pa ẹni tí ó wà fún òun ni ìròyìn kàyééfì.

Àfi bi ẹni tí ó gba ìdájọ́ ikú ni àyà Olori tuntun náà ṣe bẹ̀rẹ̀ sí í já lọ́jọ́ tí Ọba sọ̀rọ̀ yìí létí rẹ̀. Ìdí nìyí tí ó fi kọrí sínú igbó lóru ọjọ́ kejì tí ó gbọ́ ọ̀rọ̀ yìí; Iwin tí ó bá pàdé níbí tí ó gbé ń sunkún fi i lọ́kàn balẹ̀ nígbà tí ó gbọ́ ìṣòro rẹ̀. Iwin náà fún un ni ewé tí ó gbo láti fi ra èrìgì òkè àti tilẹ̀. Bí ó ṣe fi ewé náà ra èrìgì òkè àti ti ilẹ̀ ni eyín hù ní ẹnu rẹ̀. Ṣùgbọ́n Iwin náà kìlọ̀ fún un pé kò gbọdọ̀ rẹ́rìn-ín títí di ọjọ́ tí Ọba dá.

Bí ọjọ́ tí Ọba dá ti pé ni àwọn ayaba mẹ́fẹ̀ẹ̀fà tí wọn jẹ́ ìyáálé fún un ti pẹ́jù sí ààfin, tí wọn sì ń retí ẹlẹ́yà rẹ̀. Olorì kìn-ín-nì bọ́ síbẹ̀, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í kọrin peé:

Apàlọ́: Ìyàwó, ìyàwó ṣíyín fún mi wò
Agbálọ̀ọ́: Ṣíyín Ọsáárá
Apàlọ́: Eléyín afẹ́
Agbálọ̀ọ́: Ṣíyín Ọ̀sáárá
Apálọ́: Òrèkelẹ́wà
Agbálọ̀ọ́: Ṣíyín Ọ̀sáárá
Apàlọ́: Ìbàdí-àrán
Agbálọ̀ọ́: Ṣíyín Ọ̀sáárá

Ṣùgbọ́n ìyàwó yìí kò la ẹnu rẹ̀ títí tí àwọn ayaba mẹ́fẹ̀ẹ̀fà fi kọrin yìí tán. Ní ìkẹyìn ni Ọba náà kọ orin yìí. Kí Ọba tó parí orin yìí ni ìyàwó ti bẹ̀rẹ̀ sí í rẹ́rìn-ín. Ẹnu sì ya gbogbo ènìyàn láti ri eyín rẹ̀ tí ó funfun pin-in bí ẹ̀gbọ̀n-òwú. Báyìí ni Ọba ṣe pa Olorì tí ó wá fún ni ìròyìn kàyéèfì tí ó wà túbọ̀ ni ìfẹ́ Olorí tuntun náà sí i.

Ìtàn yìí kọ́ wa pé kí á má ṣe ìlara ọmọnìkejì wa.

Apàlọ́: Ìdí àlọ́ mi rèé gbángbáláká
Ìdí àlọ́ mi rèé gbàngbàlàkà
Kí ọ̀fọ́n-ọ̀n ó gun àjà
Kí ó gbẹ́gbàá kò mí
Ki n fi lu agogo ẹnu pópó
Ogbó orógbó ni ki n gbó
Kí n má ṣe gbó ogbó obi
Nítorí orógbó ni í gbó wọn sáyé
Obí ni í bi wọ́n sọ́rùn
Bí n bá parọ́
Kí agogo ẹnu mi ma ṣe ró lẹ́ẹ̀mẹta
Ó di pó! Pó! Pó!
Ó ró tàbí kò ró?
Agbálọ̀ọ́: Ó ró!

## 4.3 Orísun Àlọ́

Inú ẹsẹ ifá ni àlọ́ ti jáde. A tilẹ̀ gbọ́ pé àlọ́ jẹ́ ọmọ Odùduwà nípasẹ̀ ifá. A ní láti mọ̀ pé ní ilẹ̀ Yorùbá babaláwo kì í pa àlọ́ nítorí wọn gbàgbọ́ pé ifá tí wọ́n dá ni ọjọ́ ọjọ́un ló padà wá di àlọ́ nípà báyìí àwọn òtítọ́ inú ifá ti sọnù, àyọkúrò àti àfikún sì ti pọ̀ rẹpẹtẹ àti pé orísìírísìí ọ̀rọ̀ àtinúdá ló ti wọ inú àlọ́.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín kìnní ni módù kejì yìí o ti kẹ́kọ̀ọ́ nípa àlọ́. A ti sọ ohun tí àlọ́ jẹ́ bẹ́ẹ̀ ni a ṣàlàyé nípa àwọn àbùdá, orísìírísìí tí àlọ́ ni. Ní ìparí a sọ̀rọ̀ nípa orísun àlọ́ gẹ́gẹ́ bi ìtàn àtẹnudẹ́nu ṣe sọ.

Ní ìpín kìnní ni abẹ́ módù kejì o ti kọ́ pé;

- Àlọ́ jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń gbà láti kọ ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ èyí tí ó ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìgbàgbọ́ àti ìṣesí àwọn Yorùbá hàn.
- Àlọ́ jẹ́ ọmọ ìtàn èyí tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ó ń sẹlẹ̀ séyìn
- Lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́ ni àwọn Yorùbá máa ń pa àlọ́
- Àwọn àgbà ni ó máa ń pa àlọ́ fún ọmọdé
- Àwọn onimọ̀ tí ó ti fún àlọ́ ni oríkì ni: Ọ̀pádọ̀tun (1994), Òjó (2005), Babalọlá (1978).

- Àwọn ohun tí ó wà ní àyíká tàbí àrọ́wọ́tó ló máa ń sẹlẹ̀ nínú àlọ́
- A máa ń bá ènìyàn, ẹranko, ẹyẹ, iwin àti òkú pàdé nínú ìtàn àlọ́
- Àjọsepọ̀ máa ń wáyé láàrin ohun abẹ̀mí àti aláìlẹ́mìí nínú ìtàn àlọ́
- A kìí lo orúkọ abáyému fún àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́
- Inú ẹsẹ ifá ni àlọ́ ti jáde

## 6.0 IṢẸ́ SÍṢE

1. Fún àlọ́ ni oríkì.
2. Àwọn àbùdá wo ni àlọ́ ní?
3. Jíròrò nípa orísun àlọ́.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Adéoyè, C.L (1980). *Àṣà àti ìṣe Yorùbá.* University Press Ltd.

Amọo, (2010). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè.* Òṣogbo: Mabol Trust publishers.

Babalọlá, A. (1973). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá*. Ibadan: University Press Limited.

Ládélé, T. AA, et al (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Garima Press Ltd.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994). *Àlọ́ Onítàn*. Y Books

Yemitan, O. (1979). *Ojú Òṣùpá.* Ìbàdàn University Press Limited.

# ÌPÍN KEJÌ ÌPÍNSÍSỌ̀RÍ ÀLỌ́

**Àkòónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  4.1 Ìpínsísọ̀rí Àlọ́
  4.2 Àlọ́ Àpamọ̀
  4.3 Àlọ́ Àpagbè
  4.4 Àrọ̀
  4.5 Ìmọ́
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kejì módù kejì yìí ni a ó ti máa ṣe ìpínsísọ̀rí tó péye fún àlọ́. Lẹ́yìn èyí ni a ó wá ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé lórí àwọn ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀nà tí a pín àlọ́ sí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí o lè:
i. Fún àlọ́ ní oríkì tó múnádóko
ii. Ṣe ìpínsísọ̀rí àlọ́ gẹ́gẹ́ bó ṣe yẹ
iii. Ṣàlàyé kíkún nípa orísun àlọ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Ṣàlàyé kíkún nípa bí a ṣe ń pa àlọ́ ni agbègbè rẹ
ii. Jíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ́ tí ó jẹyọ nínú àlọ́ kan tí o gbọ́ rí

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìpínsísọ̀rí àlọ́

Àlọ́ pípa jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì láti kọ àwọn ọmọdé ní àṣà, ìwà ọmọlúàbí, àwọn ohun tó tọ́ láti ṣe àti àwọn ìwà tí àwùjọ korò ojú sí. Lára àwọn ìwà ti àlọ́ fi n kọni ní ìwà Iforítì, ìsoore, ìgboyà, ìsẹra-ẹni àti ìfé. Ọ̀nà mẹ́rin gbòòrò ni a lè pín àlọ́ sí. Àwọn ìsọ̀rí náà ni: àlọ́ Àpamọ̀, Àlọ́ Àpagbè, Àrọ̀ àti Ìmọ́.

## 4.2 Àlọ́ àpamọ̀

Àlọ́ àpamọ̀ jẹ́ àdììtú ọgbọ́n àgbà tí a ń fi ìbéèrè kúkurú gbé kalẹ̀ lọ́nà atimọ bí ìrònú ẹni ṣe jinlẹ̀ sí. Ewì ni a ka àlọ́ àpamọ̀ sí nítorí pé gbogbo èròjà ewì ló wà nínú rẹ̀. Ifáàrà tàbí ìdárayá saájú àlọ́ onítàn ni àlọ́ àpamọ̀ jẹ́. Ó máa ń pèsè ọkàn àwọn olùgbọ́ àlọ́ sílẹ̀ fún àlọ́ onítàn ni. Bákan náà ni àlọ́ àpamọ̀ wà fún ìgbélọ́kànró àwọn olùgbọ́ àlọ́ títí tí agbo yóò fi kún. Apá méjì ni àlọ́ àpamọ̀ ní. Apá kìnní jẹ́ ìbéèrè apàlọ́ nígbà tí ìdáhùn olùgbọ́ jẹ́ apá kejì àlọ́ àpamọ̀. Àpẹẹrẹ apá kìnní àti ìkejì àlọ́ ló wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

Apàlọ́: Àlọ́ o
Olùgbọ́: Ààlọ̀
Apàlọ́: Èsìsì ìdí ìrókò, a jóni, má farahan ni
Olùgbọ́: Ebi
Apàlọ́: Àlọ́ o
Olùgbọ́: Ààlọ̀
Apàlọ́: Ìkòkò dúdú fẹ̀yìn ti igbó
Olùgbọ́: Ìgbín
Apàlọ́: Àlọ́ o
Olùgbọ́: Ààlọ̀
Apàlọ́: Awẹ́ obì kan àjẹ dỌ̀yọ́
Oludgbọ́: Ahọ́n

Àwọn àpẹẹrẹ àlọ́ àpamọ̀ mìíràn fún akẹ́kọ̀ọ́ ló wà ni ìsàlẹ̀ yìí.

a. Apàlọ́: Àkùkọ baba mi kan láéláé
Àkùkọ baba mi kan laélaé
Ewe kan ló ni, egbò kan ló ta
Olùgbọ́: Olú

b. Apàlọ́: Òrúkú tindí tindí
òrúkú tindì tindì
òrúkú bígba ọmọ
Gbogbo wọn ló lé tìróò fún
Olùgbọ́: Ẹ̀wà

d. Apàlọ́: Òkun ń ho ye e
Ọ̀sà ń hò gùdùgùdù
Olórí burúkú torí bọ̀ ọ́
Olùgbọ́: Orógùn ọkà

e. Apàlọ́: Ọ̀sùn gbàgbá etí odò
Ẹni tó gbìn ín
Kò gbọ́dọ̀ jẹ ẹ́
Olùgbọ́: Ọmú/ọyàn

ẹ. Apàlọ́: Ọpa tẹ́ẹ́rẹ́ kan ilẹ̀
Ó kan ọ̀run o
Olùgbọ́: Ọ̀jọ̀

Àlọ́ àpamọ̀ jẹ́ amóríyá, ó máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé jáfáfá, èyí sì máa ń jẹ́ kí wọ́n tètè ronú jinlẹ̀ àti láti ṣe àkíyèsí àyíká wọn.

## 4.3 Àlọ́ Àpagbè

Àlọ́ onítàn ni àlọ́ àpagbè jẹ́ oríṣìíríṣìí nǹkan ni àlọ́ yìí máa ń dálé. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé àlọ́ onítàn kì í ṣe òótọ́, o le dálé ènìyàn, ẹranko, iwin, ẹyẹ tàtí igi. Àlọ́ onítàn lè jẹ́ èyí tí ó ni orin ègbè tàbí èyí tí kò ní. Gẹ́gẹ́ bí Àkàngbé (2016) ṣe sọ, "àlọ́ onítàn ni àwọn Yorùbá máa ń lò láti kọ́ àwọn ọmọ wọn ní ẹ̀kọ́, àwọn àgbà máa ń rí ẹ̀kọ́ kọ́ nínú àlọ́ onítàn pẹ̀lú. Àwọn àgbà tó ní ọ̀pọ̀ ìrírí ni ó máa ń pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé. Ní ilẹ̀ Yorùbá alẹ́ ni wọ́n máa ń pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé, ẹni tí ó bá pa àlọ́ ní ọ̀san tàbí òwúrọ̀ ni ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n mọ̀ sí olóòraye nítorí pé àwọn ẹ̀yà Yorùbá gbàgbọ́ pé àárọ̀ lọjọ́, àti pé iṣẹ́ ni a fi ń ṣe. Gbàgede tàbí àgbàlá ni àlọ́ pípa ti máa ń wáye. Orí ẹní tàbí àpótí kékeré ni àwọn ọmọdé máa ń jókòó sí láti gbọ́ àlọ́. Àwọn ọmọdé náà máa n pa àlọ́ láàrin ara wọn, bí àgbàlagbà kò bá sí ni itòsí.

Àpẹẹrẹ àlọ́ onítàn ló wà ní ìsàlẹ̀ yìí

**Ìdí ti orí ìjàpá fi pá**
Ní ìgbà kan àbúrò ìyàwó Ìjàpá kan fẹ́ ṣe ìgbéyàwó. Àwọn òbí ọmọkùnrin yi filé pọn'tí, nwọ́n fọ̀nà rokà, nwọ́n fi gbogbo agbada dín'ran. Nwọ́n pe onílé, nwọ́n pe àlejò, nwọ́n pe ọmọ-ìlú, nwọ́n pè àbùlẹ̀dó ìlú, àwọn olóyè àwọn ọlọ́lá àti àwọn t'ó lórúkọ nílùú gbogbo, síbi ìgbéyàwó alárinrin yìí. Ìjàpa náa gbárùkù ti ìyàwó rẹ̀, ó dúró gẹ́gẹ́ bí ọkọlóbìnrin; gbogbo ìnáwó tí ìyàwó rẹ̀ ń ṣe, ìjàpá ló ń gbọ́ ọ. Nígbà tí ìgbéyàwó ku bí ọjọ́ méje ni Yánníbo ti lọ sí ilé rẹ̀ láti lọ bá àbúrò rẹ̀ mójútó gbogbo ètò ìgbéyàwó , pàápàá oúnjẹ-gbígbọ́ fún àwọn àlejò ti yóò wá kí wọn. Ìjàpá máa ń lọ síbẹ̀ lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan lọ kí wọn ni, ṣùgbọ́n nígbà ti ọjọ́ ìgbéyàwó kò, ó lọ sí ilé àwọn àna rẹ̀ láti bá wọn ṣe ìpalẹ̀mọ́ t'ó yẹ. Wọ́n to ìjokòó, wọ́n kọ́ àtíbàbà, wọ́n ṣe ètò àwọn onílù. Àwọn obìnrin ń ṣè, wọ́n ń sọ̀, léyìnkùlé. Ẹ̀bẹ, ẹ̀wà, àkàrà, ẹran-díndín, wọ́n gún iyán, wọ́n ro ọkà, wọ́n ṣe iṣu, wọ́n pọ́n ẹ̀kọ, wọ́n tẹ ẹ̀bá, wọ́n dín dúǹdú, wọ́n dín dòdò – oríṣìíríṣìí ohun t'ẹ́nu ń jẹ ni wọ́n pèsè sílẹ̀.

Nígbà tí Ìjàpá ṣiṣẹ́ tán, ó wẹ̀, wọ́n sì fún un ni yàrá kan ti ó kángun sí ilé tí wọ́n kò oúnjẹ sí, níbẹ̀ ni wọ́n sọ pé k'ó sinmi, k'ó nara díẹ̀ kí àìsùn ti ìgbéyàwó tóó bẹ̀rẹ̀ lálẹ́.

Bí Ìjàpá ti wọlé tí wọ́n fún un yìí, t'ó dùbúlẹ̀ s'órí ibùsùn kan, ni orùn títasánsán oúnjẹ ti wọ́n kó s'ínú ilé yẹn ń fẹ́ sí i nímú, l'ó f'imú fá á, l'ó ń

gbádùn rẹ̀. Ẹ̀bẹ ni oúnjẹ t'ó fẹ́ràn jùlọ; èyí ni wọ́n ṣi ń sè l'órí iná, ṣùgbọ́n wọ́n ti fẹ́ sọ̀ ọ́ kalẹ̀. Ìjàpá ń fi ọkàn rẹ̀ gbàdúrà pé ki Ọlọ́run jẹ́ kí obìnrin tí ń ṣe ẹ̀bẹ yi tètè sọ̀ ọ́ kí ó gbé e wọnú yàrá, k'ó jáde lọ. Ṣe wọn kò kúkú fi kọ́kọ́rọ́ ti yàrá nítorí ìgbà gbogbo ni nwọ́n ń kó oúnjẹ s'ínú ilé. Tí obìnrin yìí bá ti lè jáde, Ìjàpá rò ó nínú ara rẹ̀ pé òun á kán wọlé, òun á bu ẹ̀bẹ sínú fìlà, òun á dé e mọ orí ni ó ńgbàdúrà ní kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ ọkàn rẹ̀.

Nígbà tí ó yá, ìyá ìyàwó Ìjàpá bu oúnjẹ fún un; ẹ̀fọ́ tí wọ́n ṣè ni òsíkì, ti ẹran ìgbẹ́ kún inú rẹ̀ ni báńṣí báńṣí ni wọ́n gbé fún un, nwọ́n si gùn iyán t'ó fẹ́lẹ́ dáadáa tí ì. Ìjàpá jẹ ó yó, ṣùgbọ́n kò tẹ́ ẹ lọ́rùn tori ẹ̀bẹ tó pupa dòdò ti ògéére epo pupa sì ń ń ṣàn lórí rẹ̀ ni ó wọ̀ ọ́ lójú ṣùgbọ́n ìtìjú kò jẹ́ k'ó lè bèèrè.

Nígbà tí ó yà, Ọlọ́run bá a ṣe é, ẹ̀bẹ gúnlẹ̀, obìnrin t'ó ń ṣé é jáde, ó sọ fún àwọn t'ó wà lẹ́yìnkùlé pé oùn ń lọ gbọnsẹ̀. Bí ìjàpá ti rí i pé ó lọ tán, ó wo ọ̀tún, ó wo òsì, kò rí ẹnìkan; ó lọ sí ẹ̀hìnkùnlé, ó rí i pé gbogbo obìnrin t'ó wà níbẹ̀ l'ó ń ṣe iṣẹ́ pàtàkì kan tí kò lè tètè fi sílẹ̀, lọ́wọ́: òmíràn ń ro ọkà, òmíràn ń gún iyán, òmíràn ń gé ẹran, òmíràn ń lọ ata, ìjàpá yọ́ kẹ́lẹ́ wọlé, ó ṣí fìlà ní orí rẹ̀, ó bù ẹ̀bẹ sí i, ó dé e mọ́ orí rẹ̀.

Ẹ̀bẹ gbígbóná bẹ̀rẹ̀ sí í jó o lórí fòò, fòò! Ó sáré lọ s'ọ́dọ̀ àwọn àna rẹ̀, ó ni òun fẹ́ yára lọ pààrọ̀ aṣọ nílé. Aṣọ iṣẹ́ l'òun ṣì wọ̀ wà, òun fẹ́ yára lọ mú òmíràn kí àwọn àlejò tó máa dé fún ìnáwó ìgbeyàwó.

Ìyá ìyàwó rẹ̀ ni òun yóò sìn ín sọ́nà díẹ̀. Ìjàpá ni k'ó má ṣe ìyọnu, kó máa ba iṣẹ́ lọ, òun náà yóò padà dé nísínyí. Àna rẹ̀ ni dandan òun yóò sín ín sọ́nà. Ooru ẹ̀bẹ ń jó Ìjàpá lórí, omi ń gbọ̀n lójú rẹ̀ pẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀, ikun ń yọ nímú rẹ̀ fòrò. Àna rẹ̀ bèèrè kí l'ó ń ṣe é, ó ni òtútù díẹ̀ l'ó mú òun. Ara òun ò dá tẹ́lẹ̀, òun kàn kẹ́ 'ra wá ni, ibà l'ó ń mú òun, alaalẹ́ l'ó máa ń dé sí 'un bẹ́ẹ̀. Àna rẹ̀ bá kì i dáadáa, ó ní kò tètè máa lọ tọ́jú ara nílé; ó padà lẹ́yìn rẹ̀. Bí Ìjàpá ti fi kọ̀rọ̀ kan bo àna rẹ̀ lójú, aré l'ó mú, l'ó ń sá lọ fẹfẹ sí ọ̀nà ilé tí ẹ̀bẹ ń jó o fòò fòò. Láìpẹ́, ó délé, ó ṣí fìlà rẹ̀, ẹ̀bẹ ti bá a lórí mọ́yanmọ̀yan, orí rẹ̀ ti bó, gbogbo irun orí rẹ̀ ti tu dànù, orí Ìjàpá si ti bó yò-ò! Nígbà tí ó wo ọgbẹ́ orí rẹ̀ títí, ó san, ṣùgbọ́n irun kò hú níbẹ̀ mọ́. Láti ìgbà yẹn ni orí Ìjàpá ti pá, tí kò hu irun mọ́ o.

Ìtàn yí kọ́ wa pé ojúkòkòrò kò dára o. ohun tí wọ́n bá fún wa, kí a jẹ́ k'ó máa tẹ́ wa lọ́rùn o.

**Ọba Aláìgbọràn**

*Òsùpá jèrèirè, awo Oníbarà*
*L'ó dífá fún Oníbarà -*
*Nwọn ni k'ó f'àgbò kan*
*Àtẹ́'gbọ̀kànlá rúbọ*

*K'ágbèrè obìnrin má baà kó o s'ọ̀ràn*
*Oníbarà kọ̀, kò rú;*
*Ó ni ọ̀ran kí ni obìnrin kanṣoṣo*
*Lè kó oun odidi ọba ìlú sí!*

Gẹ́gẹ́ bí àṣà ilẹ̀ Yorùbá, wọn a máa dá ifá fún ọba ìlú láti lè mọ ohun t'ó ń bọ̀, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni wọn ṣe dá ifá fún ọba Onibarà ní ọdún kan, tí ifá si sọ pé kí Onibarà fi ẹran àgbò kan àti ẹgbọ̀kànlá rúbọ nítorí kí obìnrin àgbèrè má ba kó ọ̀ràn bá a.

Onibarà dá ṣíọ̀ ifá tí wọn dá fún un yí; ó ní kò sí ọrọ níbẹ̀, ó ní odidi oùn ọba ìlú kò lè tìtorí obìnrin kanṣoṣo rí ìjàngbọ̀n kankan. Ó ní nígbà tí ojú ọba ìlú bá tún ń tìtorí obìnrin kanṣoṣo rí ọ̀ràn, ayé di bámíràn niyẹn: ìre di òdì nígbà ti baba bá n sọ pé ó di ọwọ́ ọmọ òun l'ọ́run! Onibarà kọ̀ jálẹ̀, kò rú ẹbọ yí.

Kí ọdún yí tó yípo, obìnrin àgbèrè kan wá láti ìlú kejì, ó sì sọ pé òun fẹ́ fẹ́ ọba Onibarà. Obìnrin àjèjì yí l'ẹ́wà, à-rí-má-lè-lọ ní i ṣe. Àwọn ìdílé ọba kìlọ̀ fún Onibarà pe k'ó má fẹ́ obìnrin yìí ṣùgbọ́n ọba kọ etí ikún sí ìmọ̀ràn wọn. Àwọn ìyàwó ọba gba ọba níyànjú pe k'ó yàgò fún irú obìnrin yìí ṣùgbọ́n ẹ̀yìn etí ọba ni gbogbo rẹ̀ ń bọ́ sí. Àwọn ẹmẹ̀wà ọba sọ tiwọn; àwọn ọ̀rẹ́ ọba sọ; gbogbo ìlú l'ó sọ títí pe kí Onibarà má fẹ́ obìnrin yìí ṣùgbọ́n òtúbáńtẹ́ ni gbogbo ọ̀rọ̀ wọn jásí. Onibarà ní obìnrin t'ó dara bẹ́ kò lè wa fẹ́ òun odidi ọba kí oun kọ̀ láti fẹ́ ẹ, nkan àbùkù ni.

Bí obìnrin yí ti dé ilé tan, ọba kò rójú gbọ́ ti àwọn ìyàwó yoku mọ́, Ó gba ọba l'ọ́kàn t'ó fi jẹ́ pe gbogbo ohun ti obìnrin yí bá ti ńfẹ́ ti di dandan fún Onibarà láti ṣe. Oríṣìíríṣìí àrà ni obìnrin yìí gbé dé ṣùgbọ́n èyí tí ó pabambarì jùlọ nínú gbogbo àṣà ọwọ́ rẹ̀ ni pe ó ní oun kì í jẹ ohun miran lẹ́hìn ẹran.

Bí obìnrin yí ti wọ Onibarà l'ọ́kàn tó, kò n fi oúnjẹ mìíràn lọ̀ ọ́ lẹ́yìn ẹran tí ó sọ pe òun mọ̀ í jẹ. Ibi adìẹ inú àgbàlá ààfin ni ọba ti bẹ̀rẹ̀, t'ó ń pa gbogbo adìyẹ ilé rẹ̀ fún obìnrin yìí ní ọ̀kọ̀ọ̀kan títí tí adìyẹ fi tán n'ílé. Lẹ́yìn náà, wọ́n nawọ́ mú ewúrẹ́, ewúrẹ́ f'ìdíjálẹ̀, àgùtàn l'ó kàn lẹ́yìn ti ewúrẹ́ tán. Ṣùgbọ́n nígbà tí gbogbo àgùntàn ọba kì í bímọ lójoojúmọ́, àgùntàn bùse nígbà tí ó pé, ìyàwó Onibarà yìí di ìkookò jẹranjẹran.

Lẹ́yìn ti gbogbo ẹran ọ̀sìn inú agbolé ọba ti tán, ọba bẹ̀rẹ̀sí lọ dẹkùn mú adìẹ aládúgbò t'ó bá jẹ́ wa si itòsí ilé rẹ̀. Adìyẹ àti ẹran bẹ̀rẹ̀sí nù nígbà gbogbo. Ṣe a kò sì lè sọ pe nítorí ojú ìyá baálẹ̀ fọ́, kí a má gbọdọ̀ pe ẹlẹ́fọ̀ ni àdúgbò mọ: bí ẹnìkan bá wa adìẹ tàbí ẹran rẹ̀ tí, a fi ìbòòsí ta, a máa lọ̀ ọ́ kiri àdúgbò pe òun ń wá ẹran ọ̀sìn òun o, ẹni bá so ó mọ́'lẹ̀ kí ó tú u sílẹ̀ o. ijọ́ ẹnìkan bá ṣèèsì lọ ẹran rẹ̀ kọjá l'ójúde ọba, ọba Onibarà a bínú pe òun ni wọn ń dúnrun olè mọ́ nítorí pé olúwarẹ lọ ẹran t'ó nù kọja l'ojúde òun! Ìgbà tí ó sì jẹ pe kò si ẹni t'ó le sọ pe lébe pọn'mọ́, kò pọ̀n ọ́n 're, ẹni ẹran rẹ̀ ba nú, a yára panumọ́, a fi òfò rẹ̀ rẹ́ ara.

Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀, bẹ́ẹ́ bẹ́ẹ́, àkùkọ kò kọ ni àdúgbò mọ, ẹran kò ké mọ́; gbogbo ẹran ọ̀sìn àdúgbò tán, nítorí obìnrin ajẹran tí Onibarà fẹ́ yìí. Nígbà ti ẹran àdúgbò tán, Onibarà ni òun mọ èyí ti òun yóò ṣe; èyí tí à á ṣe kù bí ẹran

bá bùse l'ádugbò. Oníbarà wa òògùn pẹ̀nlẹ̀pẹ́ kan láti máa fi ji ẹran ọ̀sìn pa l'ọ́gànjọ́ òru. Bí Oníbara bá ti fi òògùn pẹ̀nlẹ̀pẹ́ yìí sọ ara rẹ̀ di ẹkùn tan ni ààrin òru, yóò jáde lọ sí ààrin ìlú láti máa lọ gún ẹran pa sórí ìso níbi ti olówó ẹran bá gbé so ẹran rẹ̀ mọ́'lẹ̀. Ìyàwó rẹ̀ kò ni í ti jẹ àgùntàn kan tan ti yóò fi tún jade lọ lóru láti lọ gún ewúrẹ́ mìíràn pa wá.

Àwọn ẹlẹ́ran ti 'ẹkùn' ń pa ẹran wọn wíjọ́ wíjọ́ títí, ó sú wọn. Nígbà tí ó di ọjọ́ kan ni àwọn ọkùnrin ìlú gbánujọ pe ó tó gẹ́-ẹ́ wàyí, ìdààmú ẹkùn yí pọ̀jù, àwọn gbọdọ̀ wa ọ̀nà láti pa á. Wọ́n yan awọn ọdẹ ti yóò máa ṣọ́ òde l'óru-l'óru títí tí ọwọ́ yóò fi tẹ ẹkùn náà.

Oníbarà kò mọ̀ pé àwọn ọdẹ ti wá l'óde ni òru ọjọ́ kan tí ó di ẹkùn jáde lọ láti lọ wá ẹran wa fun ìkookò t'ó gbé s'ílé ní ìyàwó. Ọ̀ṣùpá ń ràn jèrèjèrè ní òru ọjọ́ ti a wí yìí. Bí Oníbarà ti di pẹ̀nlẹ̀pẹ́ lọ gún ẹran kan ni orí ìso ni ẹran bẹ̀rẹ̀sí í ké, tí ó sí ǹ gbé ẹran ọ̀hún lọ. Bẹ́ẹ̀ ni ọdẹ kan rí i, ó sì ta á n'íbọn pàù, ó sì lọ ṣubú sí iwájú ààfin rẹ̀ gan-an. Nígbà tí ilẹ̀ mọ́, tí àwọn ará ìlú ń kọjá lọ ni wọ́n bá Oníbarà nínú awọ ẹkùn, ó ti kú paali! Wọ́n bá a pẹ̀lú gbogbo ọ̀bẹ mímú tí ó fi ń gún ẹran pa lọ́wọ́ rẹ̀ níbẹ̀, àgùtàn tí ó sì gún pa l'álẹ́ àná náà wà ni ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ níbẹ̀.

Gbogbo ìlú ya ẹnu, wọ́n fẹ́rẹ̀ má lè pa á dé mọ́, pé odidi ọba l'ó ḿba ilẹ̀ jẹ bayi! Ọ̀rọ̀ ọba yìí ni gbogbo ìlú, àtọmọdé àt'àgbà, sọ ṣúlẹ̀ ọjọ́ náà pé àwọn kò rí irú èyí rí. Bí gbogbo èyí ti ń ṣẹlẹ̀ ni àwọn àgbà foríkorí, ti wọ́n sì yara gbé òkú ọba kúrò níwájú ààfin, tí wọ́n si rọra lọ sin ín ní ìkọ̀kọ̀ níbi ti ojú aráyé kò tó. Ìyàwó rẹ̀ t'ó sún un dé'bẹ̀ pàápàá, wọ́n mú òun náà, wọ́n pa á, wọ́n sì sin in sínú ihò kan náà pẹ̀lú ọba t'ó di ẹkùn yìí.

Láti ọjọ́ náà ni ó ti di pe bí a bá pa ẹkùn, ìkọ̀kọ̀ ni a máa ń sin òkú rẹ̀ nítorí nwọn gbà pe òkú ọba ni.

## 4.4 Àrọ̀

Ọ̀rọ̀ tí a fi kọ ara wọn ni a mọ̀ sí àrọ̀. Oríṣìí àrọ̀ méjì ló wà. Ní ìgbà tí àrọ̀ kan jẹ́ ewì pọ́ńbélé, èkejì jẹ́ ìtàn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ geere ni a fi ń gbé àrọ̀ kalẹ̀ ṣùgbọ́n ìsàré ní a máa fi ń so wọ́n pọ̀. Àrọ̀ máa ń múni láròjinlẹ̀, èyí nìkan kọ́ ó tún máa ń morí jí pépé.
Àpẹẹrẹ àrọ̀:
Mo járọ̀, mo járọ̀ o
Àrọ̀ mo já ọ pátí
Mó jápá já
Mo já fùfù léèlé lọ́rùn àdàbà
Mo wá jájú Ọlọ́run Ọba pẹ̀rẹ́
Asẹta ń relé Adó
Ọ̀rúnmìlà ń ròde Ọ̀wọ̀
Ọ̀rúnmìlà ń roke Ìgẹ̀tí
Nínú ilé bàbá òun ni

Ewì
Ó lẹ́nu kò le sọ̀rọ̀ - Ìyámòpó
Ó bọ́ sómi láì ró táló- Abẹ́rẹ́
Òkú ewúrẹ́ ké ju ààyè rẹ̀ lọ Ìlú
Òkú ajá jẹ̀kọ ju ààyè rẹ lọ aja díndín
Ọ̀rọ̀ geere
Ǹjẹ́ o mọ akọ̀lé mágbe Ẹyẹ

## 4.5 Ìmọ́

Ìmọ́ jẹ́ bí orin ìdárayá láàrin àwọn ọmọdé ní ilẹ̀ Yorùbá. Ó máa ń fi ààyè sílẹ̀ fún àwọn ọmọdé láti se eré papọ̀, dárayá àti mu ìnú ara wọn dùn. Bátànì lílé àti gbígbè ni ìmọ́ ni.

Lílé: Lúbúlúbú ta ní ó lọ ọjà tó bá dalẹ́
Ègbè: Èmi ó lọ
Lílé: Gbowó o bá mi rayọ̀ olóokan bọ̀ bó o bá lọ
Ègbè: Èmi ò lọ́ mọ́
Lílé: Kí ló dé ná?
Ègbè: Kò sí nǹkankan
Lílé: Kí ló ha dé?
Ègbè: Kò sí nǹkankan
Lílé: Ǹjẹ́ o bùmọ́
Ègbè: Mo bùmọ́
Lílé: Ki ni ń jẹ́ ìmọ̀
Ègbè: Mọladé
Lílé: Kí ní ń jẹ́ adé
Ègbè: Adésípò
Lílé: Kí ní ń jẹ́ ipò
Ègbè: Ipòsẹ́rẹ́
Lílé: Kí ní ń jẹ́ ìṣẹ́rẹ́
Ègbè: Ìsẹ́rẹ́ ọmọ́yọ
Lílé: Kí ní ń jẹ́ ọmọ́yọ
Ègbè: Ọmọ́yọ àkókò
Lílé: Kí ní ń jẹ́ àkókò
Ègbè: Àkókò òrìṣà
Lílé: Kí ní ń jẹ òrìṣà
Ègbè: Òrìṣà alayé
Lílé: Kí ní ń jẹ alayé
Ègbè: Alayé alọ̀run
Lílé: Kí ní ń jẹ́ alọ̀run
Ègbè: Alọ̀run ekòló
Lílé: Kí ní ń jẹ ekòló
Ègbè: Ekòló àjùbà
Lílé: Kí ní ń jẹ́ àjùbà
Ègbè: Ajúbà rẹrẹ

Lílé: Kí ní ń jẹ́ rẹrẹ
Ègbè: Rẹ̀rẹ̀ ń moogun
Lílé: Kí ní ń jẹ́ mogun
Ègbè: Ògún oníre
Lílé: Kí ní ń jẹ́ onire
Ègbè: Onire ẹ́fun
Lílé: Kí ń ń jẹ ẹ́fun
Ègbè: Efun iyẹ
Lílé: Kí ní ń jẹ́ iyẹ́
Ègbè: Ìyé àsá
Lílé: kín ní ń jẹ́ àsá
Ègbè: Àsá òkè
Lílé: kí ní ń jẹ́ òkè
Ègbè: Òkè ilẹ̀
Ègbè: Kí ní ń jẹ́ ilẹ̀
Lílé: Ilẹ̀ òwú
Ègbè: Kí ní ń jẹ́ òwú
Lílé: Òwú aṣọ
Ègbè: Kí ní ń jẹ́ aṣọ
Lílé: Aṣọ mo wọ̀ yìí, igi lo wọ yẹn
Lílé: Aṣọ mo ró, igi lo ró
Ègbè: Aṣọ mo ró, igi lo ró

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín kejì lábẹ́ módù kejì, o ti kọ́ pé:

- Àlọ́ pípa jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì láti kọ́ àwọn ọmọdé ní àṣà àti ìwà ọmọlúàbí
- Ọ̀nà mẹ́rin ni a lè pín àlọ́ sí: àlọ́ àpamọ̀, àlọ́ àpagbè, àrọ̀ àti ìmọ́
- Àlọ́ àpamọ̀ jẹ́ àdììtú ọgbọ́n àgbà tí a ń fi ìbéèrè kúkúrú gbé kalẹ̀
- Apá méjì ni àlọ́ àpamọ̀ ni, ìbéèrè àti ìdáhùn
- Àlọ́ onítàn ni àlọ́ àpagbè jẹ́, o lè ní orin ègbè tàbí kí ó ma ni orin ègbè
- Àwọn àgbà tí ó ní ọ̀pọ̀ ìrírí ni ó máa ń pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé ní ilẹ̀ Yorùbá
- Ẹni tí ó bá pa àlọ́ ní àárọ̀ tàbí ọ̀sán ni àwọn Yorùbá mọ̀ sí olóòrayè
- Gbàgede tàbí àgbàlá ni àlọ́ pípa tí ń wáyé
- Àrọ́ lè jẹ́ ewì tàbí ọ̀rọ̀ geere
- Ìmọ́ jẹ́ erémọdé tí ó ní bátànì lílé àti gbígbé

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣe ìpínsísọ̀rí tó yẹ fún àlọ́
2. Kí ní láríjà àlọ́ àpamọ̀
3. Ta ni àwọn Yorùbá mọ̀ sí Olóòrayè
4. Pààlà láàrin àrọ̀ àti ìmọ́

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Amọo, (2010). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè.* Ọ̀ṣogbo: Mabol Trust publishers.

Babalọlá, A (1973). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá.* Ibadan: University Press Limited.

Ládélé, T. AA, et al (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn: Garima Press Ltd.

Yemitan, O. (1979). *Ojú Ọ̀ṣùpá*. Ìbàdàn University Press Limited.

# ÌPÍN KẸTA KÓKÓ TÓ MÁA Ń JẸYỌ NÍNÚ ÀLỌ́

**Àkòónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Kókó tó máa ń jẹyọ nínú àlọ́
 4.2 Ẹ̀kọ́ Ìwà
 4.3 Ìdí Abájọ
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kẹta módùù kejì yìí ohun tí ó máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ ni àwọn kókó tó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́ o lè:

i. Ṣàlàyé kíkún nípa àwọn kókó tó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá
ii. Jíròrò lórí ọ̀kanòjọ̀kan ẹ̀kọ́ ìwà tí ó wà nínú àlọ́
iii. Se àgbéyẹ̀wò ìdí abájọ tí àlọ́ máa ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kín ni àlọ́?
2. Àwọn ẹ̀kó wo ni a máa ń rí kọ́ nínú àlọ́?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Kókó tó máa ń jẹyọ nínú àlọ́

Kókó méjì pàtàkì tí àlọ́ máa ń dálé ni ẹ̀kọ́ ìwà àti ṣíṣàfihàn ìdí abájọ. Oríṣìírísìí àwọn ìwà rere tí àwùjọ ń retí láti ọ̀dọ̀ àwọn olùgbé inú rẹ̀ ni ó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ onítàn. Díẹ̀ lára àwọn ìwà rere yìí ni ìfẹ́, òtítọ́, ìsoore, ìforítì, àti ìtẹ́lọ́rùn. Lára àwọn ìwà búburú tí a máa ń bu ẹnu àtẹ́ lù nínú àlọ́ ni olè, ìbínú, ìkórìíra, ọ̀kánjúwà àti ọwú jíjẹ. Ọ̀kanòjọ̀kan ìdí abájọ ni àlọ́ máa ń sàfihàn ohun tí ó sókùnkùn tẹ́lẹ̀ nípa ohun tàbí ẹ̀dá kan, yóò sì hàn síta kedere.

## 4.2 Ẹ̀kọ́ Ìwà

Ọ̀nà kan pàtàkì láti kọ́ni ni ẹ̀kọ́ ̀ìwà lórísìírísìí ni àlọ́ onítàn jẹ́. Àfojúsùn àlọ́ ni láti dánilẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe ohun tí o tọ́ láwùjọ àti láti jìnnà sí àwọn ìwà tí àwùjọ kò fi àyè gbà lọ́nà àtimú kí àlàáfíà jọba, kí ìdàgbà sókè sì bá àwùjọ. Àpẹẹrẹ àwọn ẹ̀kọ́ ìwà tí a rí kọ́ nínú àlọ́ onítàn ló wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

**Ìjàpá àti Àdàbà jọ dá oko**

a. Ìwà ìwọ̀ra kò dára. Ìwọ̀ra ló ṣekú pa Ìjàpá nínú àlọ́ Ìjàpá àti Àdàbà ti wọ́n jọ́ dá oko kan
b. Ojúkòkòrò kò dára. Ojúkòkòrò ló pa Ìjàpá
d. Àìsòtítọ́ kò lérè rere kankan. Ìjàpá jẹ́ aláìsòótọ́ ẹ̀dá
e. Ilẹ̀ dídà kò dára. Ọ̀dàlẹ̀ ọ̀rẹ́ ni Ìjàpá. Ó sì bá ilẹ̀ lọ
ẹ. Bí ẹ̀dá bá ń yọlẹ̀ dà, ohun abẹ́nú a máa yọ́ irú wọn ṣe.

**Ìjàpá àti Ìyá Alákàrà**

a. Ìwà àṣejù, ẹ̀tẹ́ ló ń mú wá
b. Ojúkòkòrò kò dára. Ojúkòkòrò Ìjàpá ló pa á
d. Ìwọ̀ntúnwọ̀nsì ló dára nínú ohun gbogbo tí ẹ̀dá bá ń ṣe láyé
e. Olè jíjà kò dára, ó máa ń gé ẹ̀mí kúrú
ẹ Kò dára kí ènìyàn má ṣiṣẹ́, ọwọ́ tó bá dilẹ̀ ni èṣù ń bẹ̀ lọ́wẹ̀

**Ìjàpá àti Àkùkọ**

a. Owú jíjẹ kò dára
b. Owú jíjẹ lè mú kí ènìyàn sìwà hù
d. Owú jíjẹ máa ń mú ọ̀rẹ́ méjì pa ara wọn
e. Ìbínú kò dára. Inúbíbí ló ṣekú pa àkùkọ
ẹ. Ó yẹ kí a máa kíyèsára. Àìkíyèsára Àkùkọ ló ṣekú pa á

## 4.3 Ìdí Abájọ

Ohun tí ìdí abájọ máa ń ṣàfihàn nínú àlọ́ onítàn Yorùbá ni ìdí tí ohun kan tàbí ẹ̀dá kan ṣe rí bí ó ti rí. Àwọn Yorùbá bọ̀, wọ́n ni "Bí kò bá nídìí, obìnrin kìí jẹ́ kúmólú". Àríyànjiyàn lórí ohun kàn ní pàtó ló máa ń fojú hàn síta kedere lẹ́yìn ìtàn àlọ́ tó ń sọ ìdí abájọ. Àpẹẹrẹ díẹ̀ lára ìtàn àlọ́ tó ń sọ̀rọ̀ nípa ìdí abájọ ló wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

**Ìdí ti orí Ìjàpá fi pa**

Ìtàn àlọ́ yìí jẹ́ kó yẹ wa pé ní ìgbà ìwáṣẹ̀ Ìjàpá lọ sí ilé àwọn òbí ìyàwó rẹ̀ láti bá wọn ṣe ìgbéyàwó. Ojúkòkòrò Ìjàpá ló jẹ́ kí ó yọ̀lọ bu àsáró gbígbóná sí inú fìlà tí ó sì dé e mọ́ orí lẹ́yìn tí wọ́n ti gbé iyán, ọbẹ̀ òsíkí àti ẹran ìgbẹ́ fún un. Bí Ìjàpá kò ṣe tètè rí ọ̀nà lọ sí ilé ló mú kí ẹ̀bẹ gbígbóná tó dé mọ́ fìlà rẹ̀ bó gbogbo irún orí rẹ̀ tí ó sì di ẹni tó pa lórí. Ohun tí ìtàn yìí kọ́ wa ni pé ojúkòkòrò kò dára.

**Ìdí tí Igún fi pálórí**

Ní ìgbà láéláé ìyàn ńlá bẹ́ sílẹ̀ láàrin àwọn ẹranko àti ẹyẹ, kò sí ohun tí wọ́n lè jẹ, ní ìgbà tí agbára wọn kò gbé e mọ́, wọ́n fi oókan kún eéjì wọ́n sì gba oko aláwo lọ. Babaláwo sọ pé ẹnìkan nílò láti gbé ẹbọ lọ sí ọ̀dọ̀ Olódùmarè ni. Lẹ́yìn ọ̀pọ̀ ẹ̀bẹ̀, igún gbà, ó sì gbe ẹbọ lọ sọ́dọ̀ Olódùmarè. Olódùmarè gba ẹbọ lọ́wọ́ igún ó sí ṣe ìlérí pe òjò yóò rọ̀ láìpẹ́. Kí igún tó padà dé ilé ayé, òjò ńlá rọ̀, ó sì pa igún èyí tí o mú un di sìọ̀sìọ̀. Gbogbo ilé àwọn ẹyẹ ni Igún yà ṣùgbọ́n wọn kò sílẹ̀kùn fún un. Ẹbọ ti Igún gbe ló pa á lórí, bẹ́ẹ̀ ni òjò tí ó pa a ló jẹ́ kí ara rẹ̀ ṣe sìọ̀sìọ̀ di òní. Èyí ni àwọn àgbà ṣe máa ń pòwe pé oore níwọ̀n torí ènìyàn sòro.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín kẹta yìí a ti sọ̀rọ̀ nípa àwọn kókó tí ó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ onítàn ní ilẹ̀ Yorùbá. Àkọ́kọ́ ni ẹ̀kọ́ ìwà tí àwọn àlọ́ onítàn máa ń kọ́ni. Ẹ̀kejì ni ìdí abájọ ohun kan tàbí òmíràn èyí tí ìtàn àlọ́ oní ìdí abájọ máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí.

Ní ìpín kẹta lábẹ́ módù kejì yìí, o ti kẹ́kọ̀ọ́ pé

- Kókó méjì tí àlọ́ onítàn máa ń dálé ni Ẹ̀kọ́ Ìwà àti Ìdí Abájọ
- Ẹ̀kọ́ ìwà máa ń bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà búburú láwùjọ
- Ìdí abájọ máa ń ṣàfihàn ohun tó pamọ́ fún aráyé
- Àríyànjiyàn lórí ohun kan tàbí ìtàn kan ni ìtàn ìdí abájọ máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Àwọn kókó wo ló máa ń jẹyọ nínú àlọ́ onítàn
2. Jíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ́ ìwà tí o ti kọ́ nínú ìtàn àlọ́ gbogbo tí o ti kà
3. Pààlà láàrin àlọ́ ìdí abájọ àti àlọ́ tó ń kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ ìwà

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adébáyọ̀, B. (1973. *Àkójọpọ̀ àlọ́ Ìjàpá.* Ìbàdàn University Press Ltd.

Amọo, (2010). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè.* Ọ̀ṣogbo: Mabol Trust publishers.

Ládélé, T.A.A et al (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Garima Press Ltd.

Yémitán, O. (1979). *Ojú Òsùpá.* Ìbàdàn: University Press Ltd.

## ÌPÍN KẸRIN ỌGBỌ́N ÌSỌ̀TÀN ÀLỌ́

**Àkòónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Àlọ́
 4.2 Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe
 4.3 Ìbánisọ̀rọ̀ tààrà
 4.4 Àwàdà
 4.5 Ìgbénilọ́kànsókè
 4.6 Orin
5.0 Ìsọnísókí
7.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Ní ìpín kẹrin módù kejì yìí ni o ti máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa àwọn onírúurú ọgbọ́n tí òǹsọ̀tàn àlọ́ máa ń ṣàmúlò lọ́nà àti mú kí àwọn olùgbọ́ àlọ́ tẹ́tí sílẹ̀ ní ìgbà tí ìtàn rẹ̀ bá dùn, kí wọ́n sì gbádùn rẹ̀ dáadáa.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó lè:

i. Sọ ohun tí ọgbọ́n ìsọ̀tàn àlọ́ jẹ́
ii. Ṣe ọ̀rínkíniwín àlàyé lórí àwọn oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn àlọ́
iii. Pààlà láàrin àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn àlọ́ kọ̀ọ̀kan

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Pa àlọ́ onítàn Yorùbá kan tí o mọ̀
ii. Ṣe àfàyọ àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn inú àlọ́ tí o pa

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Àlọ́

Kí ìtàn kan tó lè ṣe ìtẹ́wọ́gbà tí àwọn ènìyàn yóò sì farabalẹ̀ láti gbọ ọ́, irúfẹ́ asọ̀tàn bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ jẹ́ èyí tó mọ́ ọgbọ́n ìsọ̀tàn oríṣìírísìí èyí tí yóò mú àwọn olùgbọ́ rí ẹ̀kọ́ tí ó fẹ́ kí wọ́n gbọ́ dìmú. Ète lọ́lọ́kan-ọ̀jọ̀kan ni òǹsọ̀tàn lè lò láti gbé ìtàn rẹ̀ kala fún aráyé gbọ́ lọ́nà tí ó lérò pé yóò ṣẹ ìtẹ́wọ́gbà. Bí àwọn ènìyàn kò bá farabalẹ̀ láti gbọ́ ìtàn kan, ohun tó dájú ni pé òǹsọ̀tàn kùnà láti lo ète onírúurú láti gbé èrò rẹ̀ tàbí iṣẹ́ tí ó fẹ́ jẹ́ jáde fún aráyé.

Láti lè jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ ìtàn gbádùn ìtàn tí ó ń sọ, ọ̀kan-òjọ̀kan ọgbọ́n ni òǹsọ̀tàn yóò ta, sebí Yorùbá bọ̀ wọ́n ni "Ọwọ́ ara ẹni laá fi tún ìwà ara ẹni ṣe" Àwọn oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn àlọ́ tí òǹsọ̀tàn àlọ́ máa ń lò ni: Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe, ìbánisọ̀rọ̀ tààrà, àwàdà, igbénilọ́kànsókè àti orin.

**Àwọn oríṣìíríṣìí Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Àlọ́**
Lọ́nà àti jẹ́ kí ohun tí òǹsọ̀tàn àlọ́ ń sọ ní ìtumọ̀ létí àwọn olùgbọ́ ìtàn rẹ̀, ó gbọdọ̀ sàmúlò ọgbọ́n ìsọ̀tàn lóríṣìíríṣìí. Ní báyìí, a ó máa ṣàlàyé àwọn ọgbọ́n tàbí ète ìsọ̀tàn wọ̀nyí ni síṣẹ̀-n-tẹ̀lé.

## 4.2 Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Ojú-mi-ló-ṣe

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-lo-ṣe jẹ́ èyí tí ó máa ń mú ìbáyẹ́mu lọ́wọ́ torí pé ẹni tí ó ni ìrírí ló ń sọ ìtàn náà. Èyí túmọ̀ sí pé fúnra òǹsọ̀tàn ni yóò sọ gbogbo ìrírí rẹ̀ ní èdè ara rẹ̀.

Àpẹẹrẹ irúfẹ́ ìtàn yìí ni ìtàn Ọmọbìnrin aláìgbọràn tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:
Ní ayé àtijọ́ Ọmọbìnrin kan wà ní ìlú kan. Ọmọbìnrin yìí lẹ́wà bí ẹgbin. Gbogbo àwọn ọmọkùnrin ni ó fẹ́ fi s'aya ṣùgbọ́n kò gbà fún ẹnìkankan nínú wọn. Àwọn òbí rẹ̀ yan ọkọ fún un ṣùgbọ́n kò gbọ́ sí àwọn òbí rẹ̀ lẹ́nu. Nígbà tí ó ṣe, ó bá ọmọkùnrin kan pàdé, ọmọkùnrin yìí rẹwà, ó sì wu ọmọbìnrin yìí dáadáa. Ọmọbìnrin yìí dẹnu ìfẹ́ kọ ọmọkùnrin, ṣùgbọ́n ọmọkùnrin kọ̀ pé òun kò nífẹ́ ọmọbìnrin yìí. Ọmọbìnrin fààké kọ́rí pé ọmọkùnrin yìí ni òun ní láti fẹ́ láìmọ̀ pé sènìyàn-ṣẹranko ni ọkùnrin náà. Ọmọbìnrin sọ pé ibikíbi tí ó bá ń lọ ni òun yóò bá a lọ. Nígbà tí wọ́n rìn díẹ̀, ọmọkùnrin yìí bá yà sí inú igbó ó sì gbé àwọ̀ èrè rẹ̀ wọ̀. Bí erè ti fè dé ojú ọ̀nà ní ó fa ẹsẹ ọmọbìnrin yìí tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí gbé e mì, bí ọmọbìnrin yìí ṣe rí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ yìí ni ó bá fariwo ta pẹ̀lú orin lẹ́nu báyìí pé:

Lílé: Nìkún o, Nìkún ninì
Ègbè: Ninini, nikún ninì
Lílé: Nìkún o, Nìkún ninì
Ègbè: Ninini, nìkún ninì
Lílé: Bàbá fimi f'ọkọ èmi ò gbọ́ o
Ègbè: Ninini, nìkún ninì
Lílé: Ìyá fi mi f'ọkọ èmi ò gbà o
Ègbè: Ninini, nìkún ninì
Lílé: Ọko nìkan tí mo fẹ́ ló bá derè o
Ègbè: Nìkún o, Nìkún ninì

Bi ọmọbìnrin yìí ṣe ń kọ orin ni ère bẹ̀rẹ̀ sí gbéemì díẹ̀ díẹ̀. Ṣe orí tí yóò sunwọn ní gbáláwo re ko ni. Ọ̀kan ninú àwọn tí wọ́n ti kọnu sí obìnrin yìí láti fi saya wà lórí ẹ̀gùn tí ó ń s'ọdẹ. Ó ta ìbọn mó ere, tí ère sì kú. Lẹ̀yín èyí ni ọmọbìnrin yọ jáde lẹ́nu ere (Àmọ̀ọ́ 2010:17)

Ẹ̀kọ́ tí àlọ́ yìí kọ́ wa ni pé kò yẹ kí a máa ṣe àìgbọràn sí àṣẹ àwọn òbí wa, bẹ́ẹ̀ ni fáàrí àṣejù máa ń kó wàhálà báni.

## 4.3 Ìbánisọ̀rọ̀ Tààrà

Ọgbọ́n ìbánisọ̀rọ̀ tààrà ni asọ̀tàn máa ń lo láti bá àwọn ènìyàn tí ó jókòó ni ìgbà tí ó ń pa àlọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀. Fún àpẹẹrẹ, nínú ìtàn àlọ́ Atiro Ìlú Ògèlé, lẹ́yìn tí òǹsọ̀tàn àlọ́ ti sọ ìtàn bí Atiro tí ó jẹ́ Àwo ṣe de ìlú Ògèlé tí ó sì ràn wọ́n lọ́wọ́ ní ìgbà tí ó gbọ́ pé ìlú wọ́n tu, tí ó ṣe ètùtù tí ìlú Ògèlé sì padà kún padà. Léyín èyí àwọn ará ìlú Ògèlé mọrírì, Ògèlé, ti wọn fi oyè dá ògèlé àti ìyàwó rẹ̀ lọ́la. Oore pé asiwèrè gbàgbé àwọn ará ìlú Ògèdé lé Atiro jade lẹ́yìn ti Èsù gbà wọ́n ní ìyànjú. Lẹ́yìn ti Atiro tú ìlú Ògèlé lẹ́ẹ̀kejì torí àìmoore wọn, asọ̀tàn bá àwọn olùgbọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀ báyìí

Nítorí náà, ìwà ìkà àti èrò búburú ti èsù ń gbìn sí enia lọ́kàn
jẹ́ nǹkan tí a gbọdọ̀ máa sọ́ra nípa rẹ̀, ṣùgbọ́n o, ẹni a rán ní ìkà,
tó gbìnkà, ó ti ní tirẹ̀ nínú tẹ̀lẹ̀ ni (Yemitan et al 1970:26)

Gbogbo ìbánisọ̀rọ̀ tààrà òǹsọ̀tàn nínú àwọn ìtàn àlọ́ fún ìwàásù àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni.

## 4.4 Àwàdà

Èyí jẹ́ ìsẹ̀lẹ̀ adẹ́rìn-ín pani tí òǹsọ̀tàn máa ń fi sí àárín ìtàn rẹ̀ kí ó máa ba a le ju, àti láti jẹ kí àwọn olùgbọ́ ìtàn gbádùn rẹ̀ dáadáa. Fún àpẹẹrẹ, nínú ìtàn àlọ́ "Ìjàpá l'óyún ìjàngbọ̀n" àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó dẹ́rín-ín pani ọlọ́kan-ọ̀-jọkan ni òǹsọ̀tàn fi bọ inú ìtàn rẹ̀. Ọ̀nà ti asọ̀tàn gbà sọ̀rọ̀ nípa àsèjẹ yánníbo àti bí Ìjàpá ṣe tó ọ wò, jẹ́ èyí tó panilẹ́rìn-ín.

Babaláwo gbé ọbẹ̀ lé e lọ́wọ́ Ó sì kìlọ̀ pé kò gbọdọ̀ tọ́ ọ́
Wò. Ó gba àsèjẹ, ó dúpẹ́ lọ́wọ́ Àkàlà. Bí o ti ń lọ, ọbẹ̀ yìí
Ń tasánsán sí i nínú, ó ń fi imú fa òórun rẹ̀, ó ń dá ọ̀fun mì
Itọ́ sì ń yọ sí i lẹ́nu (Babalọla 1973:180)

Gbogbo àlàyé nípa Ìjàpá àti bí ó ṣe ń ṣe ní ìgbà tí o gbà àsèjẹ ìyàwó rẹ̀ Yánníbo, panilẹ́rìn-ín, ó sì fi Ìjàpá hàn gẹ́gẹ́ bí oníwọra àti ọ̀kánjúà.

## 4.5 Ìgbénilọ́kànsókè

Èyí ni ète tí òǹsọ̀tàn máa ń lò láti jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ ìtàn rẹ̀ ni ìtara láti mọ ibi tí ìtàn yóò parí sí. Àpẹẹrẹ ìgbénilọ́kànsókè wáyé nínú ìtàn àlọ́ ìdí tí orí Ìjàpá fi pá ní ìgbà tí ó bú ẹ̀bẹ sí fìlà tí ó sì dé e mọ́ orí ṣùgbọ́n tí ìyá ìyàwó rẹ̀ kò jẹ́ kí ó lọ tí o sọ pé àfi dandan kí òun sìn ín dé ọ̀nà

Ìjàpá ta kóló wọlé ó sí fìlà. Ní orí rẹ̀, ó bu ẹ̀bẹ sí i, ó dé e mọ́ orí rẹ̀
Ẹ̀bẹ gbígbóná bẹ̀rẹ̀ sì í jó o lórí fòfò! Ó sáré lọ sọ́dọ̀ àwọn àna rẹ̀, ó ní òun fẹ́ yára lọ pààrọ̀ aṣọ nílé. Aṣọ iṣẹ́ l'òun sì wọ̀ wá, òun fẹ́ yára lọ mú

òmíràn kí àwọn àlejò tó máa dé. Ìyá ìyàwó rẹ̀ ní òun ó sìn ín sọ́nà díẹ̀. Ìjàpá ní kó má yonu, kó máa bá iṣẹ́ lọ, òun ná yóò padà dé nísìnyí.

Àna rẹ̀ ní dandan òun á sìn ín sọ́nà. Ooru ẹ̀bẹ ńjó Ìjàpá lórí, omi ńgbọ̀n lojú rẹ̀ pẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀, ikun ń yọ nímú rẹ̀ fòrò. Ànà rẹ bèèrè kió ló ńṣe é, ó ní òtútù díẹ̀ ló mú òun (Babalọla 1973:77)

Gbogbo ọkàn olùgbọ́ ìtàn ló gbé sókè ní ìgbà tí àna Ìjàpá fàáké kọ́rí pé òun gbọdọ̀ sìn ín sọ́nà, kò sí ẹni tó mọ ohun tí ó lè sẹlè sí Ìjàpá pẹ̀lú ẹ̀bẹ gbígbónà tí ó bù sínú fìlà tí ó dé mọ́ orí. Òǹsọ̀tàn mọ̀ ọ́n mọ̀ dà á bí ète ni pé kí àná Ìjàpá sọ́ pé òun yóò sìn ín sọ́nà ète yìí wà láti mú ìfẹ́ àwọn olùgbọ́ ìtàn àlọ́ náà dúró dé òpin ni.

## 4.6 Orin

Kìí ṣe gbogbo àlọ́ onítàn ló ni orin nínú, ṣùgbọ́n àwọn àlọ́ kan wà tí o ní orin nínú èyí máa ń fi ààyè sílẹ̀ fún àwọn olùgbọ́ ìtàn àlọ́ náà láti kópa nínú àlọ́ ni, bẹ́ẹ̀ orin yìí tún máa ń dá àwọn olùgbọ́ lárayá.

Nínú ìtàn àlọ̀ Ìjàpá àti Babaláwo. Ìjàpá kọtí ọ̀gbọnin sí ìkìlọ̀ Babaláwo pé kò gbọdọ̀ jẹ́ nínú àsèjẹ tí babaláwo ṣe fún ìyàwó rẹ̀ kí o lè bímọ, èyí sì mú kí inú Ìjàpá wú. Èyí ló mú Ìjàpá gba ilé babaláwo lọ tí o sì ń kọ orin ẹ̀bẹ̀ ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Bàba-láwo mo wá bẹ̀bẹ̀
Ègbè: Alugbinrin
Lílé: Ògùngùn to ṣe fún mi lẹ́rẹ̀kàn
Ègbè: Alugbinrin
Lílé: Ó ni n mọ́ mọ̀ mọ́wọ́ banu
Ègbè: Alugbinrin
Lílé: Gbòǹgbò ọ̀nà ló yọ̀ mí tẹ̀ẹ̀rẹ̀
Ègbè: Alugbinrin
Lílé: Mo mọ́wọ́ balẹ̀ mo mú banu
Ègbè: Alu gbinrin
Lílé: Mo bojúwokùn, ó rí gbẹndu
Ègbè: Alugbinrin
Lílé: Babaláwo mo wá bẹ̀bẹ̀
Ègbè: Alugbinrin (Amọo 2010:19)

Àpẹẹrẹ orin mìíràn jẹ́ orin ìdánilójú tàbí ìjẹ́wọ́ èyí tí ọkọ àwọn orogún méjì tí ó lọ sí oko ọdẹ fún ìgbà pípẹ́ sọ pé kí àwọn ìyàwó rẹ̀ méjèèjì kọ láti lè jẹ́ kí ó mọ aláìsòótọ́ nínú àwọn ìyàwó rẹ̀.

Apàló: Gbewé mi, gbewé mi jẹ
Agbálọ̀ọ́: Àgbò, gbewé mi jẹ
Apálọ̀ọ́: Ọdún kẹta ọkọ ti lọ

Àgbálọ̀ọ́: Àgbò gbewé mi jẹ
Apàlọ́: Emi ò rìnnà bọkùnrin pàdé
Agbálọ̀ọ́: Àgbò gbewé mi jẹ
Apàlọ́: Ọkùnrin ò tẹ́ní fún èmi sùn rí
Àgbálọ̀ọ́: Àgbò gbewé mi jẹ
Agbàlọ̀ọ́: Gbewé mi, gbewé mi jẹ
Agbàlọ̀ọ́: Àgbò gbewé mi jẹ (Ọ̀pádọ̀tun 1994:47)

Yàtọ̀ sí pe orin àlọ́ máa ń fi ààyè síle fún olùgbọ́ láti kópa àti dánilárayá. Ó tún máa ń mú ẹ̀mí ìtàn àlọ́ gùn.

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín kẹrin módù kejì yìí, a ti kọ́ pé:

- Ète ọlọ́kan-ò-jọ̀kan tí òǹsọ̀tàn lò láti gbé ìtàn àlọ́ rẹ̀ kalẹ̀ ní a mọ̀ sí ọgbọ́n ìsọ̀tàn.
- Àwọn oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí òǹsọ̀tàn lè lò ni ojú-mi-ló-ṣe, ìbánisọ̀rọ̀ tààrà, Àwàdà, ìgbénilọ́kànsókè àti orin.
- Ọgbọ́n ìsọ̀tàn Ojú-mi-lo-ṣe máa ń mu ìbáyému lọ́wọ́ torí pé ẹni tí ó ní ìrírí ló ń sọ ìtàn náà
- Ìbánisọ̀rọ̀ tààrà ni apàlọ́ máa ń lò láti bá àwọn ènìyàn tí ó jókòó ní ìgbà tí ó ń pa àlọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀
- Àwàdà jẹ́ ìsẹ̀lẹ̀ apani-lẹ́rìn-ín tí òǹsọ̀tàn máa ń fi si ààrin ìtàn rẹ̀ kí ó máa ba à le jù, àti láti jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ gbádùn rẹ̀ dáadáa.
- Òǹsọ̀tàn máa ń lo ète ìgbénilọ́kànsókè láti jẹ́ kí àwon olùgbọ́ ìtàn rẹ̀ ní ìtara láti mọ ibi tí ìtàn rẹ̀ yóò parí sí.
- Orin ni òǹsọ̀tàn àlọ́ máa ń lò láti fún àwọn olùgbọ́ ìtàn rẹ̀ ni àǹfààní láti kópa nínú ìtàn tí ó ń sọ.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Jíròrò lórí ọgbọ́n ìsọ̀tàn nínú àlọ́ onítàn Yorùbá
2. Ṣàlàyé ohun tí ó ń mú òǹsọ̀tàn ṣàmúlò orin nínú ìtàn rẹ̀
3. Pààlà láàrin Àwàdà àti ìgbélọ̀kànsókè nínú àlọ́ onítàn Yorùbá

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Amọo, (2010). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè.* Ọ̀ṣogbo: Mabol Trust publishers.

Babalọla, A. (1973). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá*. Ìbàdán: University Press Limited

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994). *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ìbàdàn: Oluseyi Press Ltd.

Yemitan, O. et al (1973) *Ojú Ọ̀ṣùpá*. Ìbàdán: University Press Limited

## ÌPÍN KARÙN-ÚN ÌWÚLÒ ÀLỌ́

**Àkòónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ìwúlò Àlọ́
5.0 Ìsọnísókí
3.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín karùn-ún módù kejì yìí ni a ó tí máa jíròrò nípa oríṣìíríṣìí ìwúlò tí àlọ́ ni. ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé "Bí kò bá nídìí, obìnrin kìí jẹ́ kúmólú. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé àlọ́ náà ní ìwúlò tirẹ̀ ni àwùjọ Yorùbá. Gbogbo àwọn àǹfààní wọ̀nyí ni a ó máa gbéyẹ̀wò ni ọ̀kan-ò-jọ̀kan nínú ìtàn ìpín karùn-ún ní abẹ́ módù kejì yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- Ṣàlàyé ní kíkún nípa ìwúlò àlọ́
- Ṣe àfàyọ àwọn ìwúlò àlọ́ tí ó ti gbọ́ rí

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Kín ni lárííjà àlọ́
ii. Ṣé lóòótọ́ ni pé Olóòrayè ní pa àlọ́

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìwúlò Àlọ́

Onírúurú ìwúlò ni àlọ́ ni yálà ó jẹ́ àlọ́ àpamọ̀ tàbí àlọ́ onítàn. Àwọn ìwúlò wọ̀nyí ni a ó máa sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ báyìí.

Àlọ́ onítàn máa ń dánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tàrà ni èyí tí o túmọ̀ sí pé ní òpin ìtàn àlọ́ ẹni tí ó bá ṣe rere yóò kẹ́san ìwà rere rẹ̀, ní ìgbà ti ẹni tí o bá ṣe hu ìwà búburú yóò kẹ́san búburú rẹ̀ bákan náà. Fún ìdí èyí, àlọ́ onítàn máa ń kọ́ tọmọdé tàgbà ní ẹ̀kọ́ ìwà.

Ní ilẹ̀ Yorùbá, erémọdé ni ó máa ń padà di ọ̀rẹ́mọdé. Àjọsepọ̀ tí àwọn ọmọ máa ń ní lásìkò tí wọ́n bá ń gbọ́ àlọ́ máa ń mú kí ìfẹ́ àti ìrẹ́pọ̀ wa láàrin

wọn, ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ wọ̀nyí ni wọn sì máa ń di ọ̀rẹ́ tí wọn yóò sì ṣe ọ̀rẹ́ yìí di ọjọ́ alẹ́.

Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé ní ọgbọ́n àtinúdá torí ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn ọmọdé yìí máa ń tún àwọn àlọ́ tí wọ́n ti gbọ́ ni ẹnu àwọn àgbà sọ fún ara wọn ni ìgbà tí àwọn àgbà kò bá sí ní itòsí láti sọ àlọ́ fún wọn tàbí ní ìgbà tí ọwọ́ àwọn àgbà bá di. Àwọn ọmọdé yìí pẹ̀lú ọgbọ́n àtinúdá ti wọn lè ṣe àfikún tàbí àyọkúrò sí àwọn àlọ́ tí wọ́n ti gbọ́ tẹ́lẹ̀.

Àlọ́ máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tí ó sókùnkùn sí àwọn ọmọdé tẹ́lẹ̀. Oríṣìíríṣìí àlọ́ onítàn ló máa ń tọ́ka sí ìdí abájọ èyí tí o sì máa ń mú kí àwọn ọmọdé kọ́ ẹ̀kọ́ kan tàbí òmíràn. Fún àpẹẹrẹ àlọ́ onítàn tí ó sọ̀rọ̀ nípa ìdí tí orí Ìjàpá fi pá kọ́ àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ pé ìwà ojúkòkòrò àti olè kò dára rárá. Bí àwọn ọmọdé bá tilẹ̀ fẹ́ hu ìwà búburú kan, bí wọ́n bá ti rántí àtubọ̀tán ìwà ojúkòkòrò Ìjàpá èyí tí ó sọ ọ́ di olórí pípá, wọn yóò tún èrò wọn pa.

Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé mọ̀ nípa oríṣìíríṣìí ohun tí ó wà ní àyíká wọn, èyí tí ó jẹ́ pé wọ́n lè ṣe alaìmọ wọn bí kò ṣe pé wọn gbọ́ ọ nínú àlọ́. Ọ̀pọ̀ àwọn ọmọdé lóde òní tí kò ní àǹfààní sí àwọn àlọ́ wọ̀nyí ni kò ní ìmọ̀ tó nípa àwọn ohun tí ó wà ní àyíká wọn.

Ìgboyà tún wà lára àǹfààní ti àlọ́ máa ń fún àwọn ọmọdé, ọ̀pọ̀ ọmọ ni kì í fẹ́ láti sọ̀rọ̀ láàrin ẹgbẹ́ ṣùgbọ́n ní ìbẹ̀rẹ̀ àwọn àlọ́ onítàn apàlọ́ lè bèèrè àwọn àlọ́ àpamọ̀ bíi mélòó kan fún ìdárayá àti ìmúrasílẹ̀ fún àlọ́ onítàn ó sì lè pe ẹni tí ó wù ú. Èyí máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé wà ní ìmúrasílẹ̀ pẹ̀lú ìgboyà torí wọn kò mọ ẹni tí apàlọ́ lè pè.

Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé ní àròjinlẹ̀ pàápàá àlọ́ àpamọ̀. Ọ̀pọ̀ àwọn àlọ́ àpamọ̀ ló jẹ́ pé ọmọdé tí kó bá le ronú jinlẹ̀ dáadáa kò ní lè dáhùn irú àlọ́ àpamọ̀ bẹ́ẹ̀. Ọ̀pọ̀ ìgbà ló sì jẹ́ pé àwọn ọmọdé wọ̀nyí máa ń fi ara wọn ṣe yẹ̀yẹ́ bí wọ́n bá kùnà láti dáhùn àlọ́, lọ́nà àti dènà èyí àwọn ọmọdé máa ń ronú jinlẹ̀, wọ́n sì máa ń wà ní ìmúrasílẹ̀.

Ìdárayá ní àlọ́ wà fún lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́. Inú àwọn ọmọdé máa ń dùn ara wọn sì máa ń yá gágá lásìkò tí wọ́n bá ń gbọ́ àlọ́, gbogbo ọmọdé ló máa ń wọ̀nà fún àsìkò àti gbọ́ àlọ́ yìí, èyí sì máa ń mú ara wọn yá gágá.

Àlọ́, pàápàá àlọ́ àpamọ̀ máa ń jẹ́ kí ọpọlọ àwọn ọmọdeń jí pépé. Torí àlọ́ tí wọ́n ń gbọ́ láti ìgbà dé ìgbà máa ń fi ìmọ̀ kún ìmọ̀ wọn ni. Ó sì máa ń mú ìrònú wọn jinlẹ̀.

A tún máa ń fi àlọ́ parí ìjà tàbí aàwọ̀ ni ilẹ̀ Yorùbá. Ní ìgbà tí a bá pa àlọ́ yìí tàn ẹni ti ọ̀rọ̀ kan yóò ti rí ẹ̀kọ́ kan tàbí méjì kọ́ pé ìjà kò dára àti pé a rẹ́ ma jà kan kò sí

Àwọn ọmọdé máa ń kọ́ orin ní ìgbà tí wọ́n bá ń gbe orin àlọ́. Àwọn mìíràn nínú àwọn ọmọdé yìí lè tí ipasẹ̀ orin tí wọn kọ́ nínú àlọ́ onítàn yìí di ẹni tí ó ń kọ orin, tí yóò sì di olókìkì. Ìwúlò tí ko ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ni àlọ́ ní ní ilẹ̀ Yorùbá.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín karùn-ún, módùlù kejì, a kọ ọ́ pé:

- Àlọ́ onítàn a máa dánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà
- Àlọ́ máa ń mú ifẹ́ àti ìrẹ́pọ̀ wà láàrin àwọn ọmọdé
- Àlọ́ máa ń jẹ́ kí ọmọdé ní ọgbọ́n àtinúdá
- Àlọ́ máa ń sọ ìdí abáyọ, fún ìdí èyí ó máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun to sókùnkùn
- Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé mọ̀ nípa ohun tó wà ní àyíká wọn
- Àlọ́ máa ń fún àwọn ọmọdé ní ìgboyà
- Àlọ́ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé ní àròjinlẹ̀
- Àlọ́ máa ń jẹ́ kí ọpọlọ ọmọdé jí pépé
- Àlọ́ wúlò fún ìparí ìjà
- Àwọn ọmọdé máa ń kọ́ orin nípasẹ̀ àlọ́

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣe àgbéyẹ̀wò àǹfààní ọ̀kan-ò-jọ̀kan tí àlọ́ ní
2. Ọ̀nà wo ni àlọ́ máa ń gbà tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tó sókùnkùn?
3. Kọ àlọ́ onítàn kan kí o sì sọ àwọn ìwúlò tí àlọ́ náà ni

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Àmọ̀ó, A. (2010). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Àpagbè*. Oṣogbo: Mabol Trust publishers.

Babalọlá, A. (1973). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá*. Ìbàdàn: University Press Limited.

Ọ̀pádoun, O. (1994). *Àsàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ìbàdàn: Olúsèyí Press Ltd.

Yemitan, O. et al (1973). *Ojú Ọ̀ṣùpá*. Ìbàdàn: University Press Limited.

# MÓDÙ KẸTA ÌTÀN ÀRÒSỌ YORÙBÁ

Nínú módù kẹta yìí ni a o ti máa ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìí ìtàn kan tí a mọ̀ sí ìtàn àròsọ. A ó tu iṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò nípa ohun tí ìtàn àròsọ jẹ́, bẹ́ẹ̀ ni a ó tún sọ̀rọ̀ nípa ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbàsókè ìtàn àròsọ Yorùbá. Èyí nìkan kọ́, a ó tún se ìpínsísọ̀rí ìtàn àròsọ Yorubá. Lẹ́yìn èyí ni a ó máa fi ọ̀rọ̀ jomitoro ọ̀rọ̀ lórí àhunpọ̀ ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ọgbọ́n ìsọ̀kan nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. Ohun tí ó dájú sáká ni pé lẹ́yìn àwọn idánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìtàn àròsọ Yorùbá, o ó lè ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ gbogbo ohun tí o rọ̀ mọ́ ìtàn àròsọ Yorùbá bí ó ti tọ́ àti bí o ti yẹ.

| | |
|---|---|
| Ìpín Kìnní | Ìdìdelẹ̀ àti Ìdàgbàsókè Ìtàn Àròsọ Yorùbá |
| Ìpín Kejì | Ìpínsísọ̀rí Ìtàn Àròsọ Yorùbá |
| Ìpín Kẹta | Ìfìwàwẹ̀dá Nínú Ìtàn Àròsọ Yorùbá |
| Ìpín Kẹrin | Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Nínú Ìtàn Àròsọ Yorùbá |
| Ìpín karùn-ún | Àgbéyẹ̀wò Àsàyàn Ìwé Ìtàn Àròsọ Yorùbá |

## ÌPÍN KÌNNÍ ÌDÌDẸLẸ̀ ÀTI ÌDÀGBÀSÓKÈ ÌTÀN ÀRÒSỌ YORÙBÁ

**Àkòónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  4.1 Ohun tí ìtàn àròsọ jẹ́
  4.2 Ìdìdẹlẹ̀ àti Ìdàgbàsókè Ìtàn àròsọ Yorùbá
  4.3 Àhunpọ̀ Ìtàn Nínú Ìtàn àròsọ Yorùba
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÀRÀ

A ó bẹ̀rẹ̀ ìpín kìnní yìí nípa sísọ ohun tí ìtàn àròsọ jẹ́, lẹ́yìn èyí ni a ó tẹ̀síwájú láti jẹ́ kí o mọ̀ nípa ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbàsókè ìtàn àròsọ Yorùbá torí pé okùn kò le gùn gùn, kí a má mọ orísun rẹ̀.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kìnní yìí, o lè:

i. Fún ìtàn àròsọ Yorùbá ni oríkì
ii. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbàsókè ìtàn àròsọ Yorùbá

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Ṣàlàyé ìyàtọ̀ tí ó wà nínú àlọ́ àti ìtàn Yorùbá
ii. Ṣe àlàyé ohun tí àhunpọ̀ ìtàn jẹ́

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìtàn Àròsọ Yorùbá

O ní láti mọ̀ pé ìtàn tí òǹkọ̀wé fi inú rò, tí o wá kọ sílẹ̀ fún ìgbádùn, àkàyé, àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àwọn ènìyàn àwùjọ ni a mọ̀ sí ìtàn àròsọ. Ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àròsọ lè jẹ́ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ kan tó ṣojú òǹsọ̀tàn tàbí èyí tí a sọ fún un ṣùgbọ́n ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni òǹkọ̀wé máa ń pá irú ìtàn bẹ́ẹ̀ láró kí ó tó kọ ọ́ sílẹ̀. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé òǹkọ̀wé lè ṣe àfikún tàbí àyọkúrò sí ìtàn náà. Bákan náà ìtàn àròsọ lè jẹ́ èyí tí òǹsọ̀tàn kàn fi inú rò lásán tàbí tí ó ṣe àkíyèsí pé o ti sẹ̀lẹ̀ sẹ́yìn tàbí èyí tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí èyí tí òǹsọ̀tàn lérò pé ó lè sẹlẹ̀ ní ọjọ́ iwájú.

Oríṣìíríṣìí ìwé ìtàn àròsọ ló wà káàkiri. Àwọn kókó pàtàkì yìí la máa ń kíyèsí nínú ìwé ìtàn-àròsọ.

(a) Àkọlé ìwé náà àti ẹni tó kọ ọ́.
(b) Orísun ìtàn inú ìwé náà. Ìyẹn ni bí ìtàn náà ṣe dáyé àti àdúgbò ìṣẹ̀lẹ̀
(d) Kókó ohun tí ìtàn náà dá lé lórí
(e) Àwọn ẹ̀dá-inú-ìtàn náà àti ipa ti ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn kó láti ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin ìtàn náà.
(ẹ) Ọgbọ́n tí ìtàn náà kọ́ni.
(f) Àwọn ẹwà-èdè tó wà nínú ìwé náà tó mú kó dùn
(g) Àwọn ohun tó dánilárayá níbẹ̀
(gb) Àwọn àṣà àti ìṣe ẹ̀dá tó jẹyọ nínú ìtàn náà
(h) Ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí òǹkọ̀wé (asọ̀tàn) náà lò.

Àwọn ìtàn-àròsọ jẹ́ àwọn ìtàn tí a tinúdá tàbí tí a fọkànrò. Ìtàn náà lè jẹ́ àpẹẹrẹ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ ẹ̀dá ènìyàn. Òǹkọ̀wé a máa lo àwọn orúkọ láti hùwà tó bá fẹ́ gbé lé irú àwọn bẹ́ẹ̀ lọ́wọ́. Àwọn orúkọ yìí náà kì í sábà jẹ́ orúkọ ẹni tó hùwà náà gan-an. Bó bá jẹ́ pé òǹkọ̀wé fẹ́ tú àṣírí ìwà ìbàjẹ́ kan, ó lè má lo orúkọ ènìyàn gidi.

Ìtàn lè jẹ́ lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìlú ńlá tàbí ti ìgbèríko, àwọn oríṣìíríṣìí ẹ̀dá-ìtàn le wà nínú ìtàn náà kí ọ̀kan tàbí méjì nínú wọn sì jẹ́ olú nínú ìtàn gidi. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ọgbọ́n àti ẹ̀kọ́ ló má ń jẹyọ nínú ìtàn-àròsọ Yorùbá, irúfẹ́ ọgbọ́n bẹ́ẹ̀ a sì máa mú kí ènìyàn máa ṣọ́ra ṣe ohun gbogbo, ṣé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ọgbọ́n layé gbà.

Òwe, àkànlò-èdè, ìfọ̀rọ̀dárà àti àsọrégèé a máa pọ̀ nínú ìtàn-àròsọ láti mú ènìyàn ronú sí, ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ìtàn-àròsọ ló máa ń fi àwọn àṣà àti ìwà ẹ̀dá hàn

gbangba. Nígbà tí a bá ń ka ìtàn àròsọ a máa fi àwọn àṣà àti ìwà ẹdá hàn nínú ọkàn wa bóyá irú ohun bẹ́ẹ̀ lè ti ṣẹlẹ̀ lójú ayé tàbí àròbájọ lásán ni.

## 4.2 Ìdìdelẹ̀ Ìtàn Àròsọ Yorùbá

Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ní àwọn ẹ̀yà tí a mọ̀ sí Yorùbá ti máa ń sọ àwọn ìtàn fèyíkọ́gbọ́n lóríṣìíríṣìí láti kọ́ àwọn ọmọ wọn ni ẹ̀kọ́ ìwà torí wọ́n gbàgbọ́ pé ilé la t ií kẹ́sọ̀ọ́ ròde àti pé "ọmọ tí a kò kọ́ ni yóò gbé ilé tí a kọ́ tà lẹ́yìn ọ̀la". Gbogbo àwọn ìtàn wọ̀nyí tí àwọn baba-ńlá Yorùbá fi ń kọ́ àwọn ọmọ ni ẹ̀kọ́ ìwà yìí jẹ́ alohùn ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ torí wọn kò mọ̀n-ọ́n-kọ mọ̀-ọ́n kà ni àsìkò tí a ń sọ yìí. Ní ìgbà tí àwọn òyìnbó alawọ̀ funfun mú ẹ̀kọ́ ìwé wá ọ̀pọ̀ àwọn tí o ní ẹ̀kọ́ ìwé ni wọn kò ka èdè abínibí wọn sí torí wọ́n kà á sí ojú dúdú. Àwọn ọmọlẹ́yìn Krístì tó jẹ́ ajíyìnrere ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ akitiyan láti rí i pé èdè Yorùbá di àkọsílẹ̀ àti igi àlọ́yè. Torí èyí ló lè mú kí iṣẹ́ ìwàásù wọn ṣe ìtẹ́wọ́gbà. Èyí ló sì mú wọn gbìyànjú láti túmọ̀ Bíbélì sí èdè Yorùbá.

Ó yẹ kí o mọ akitiyan ọlọ́kanòjọ̀kan tí àwọn ìránsẹ́ Ọlọ́run ajíhìnrere wọ̀nyí ṣe èyí tí ó jẹ́ kí èdè Yorùbá di kíkọ sílẹ̀ èyí tí o sì ṣe okùnfà bí ìtàn àròsọ ṣe di kíkọ sílẹ̀ torí àjèjì ni ìtàn àròsọ jẹ́ ni àwùjọ Yorùbá kí àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun tó dé.

- Edward Bowdich ni ó kọ́kọ́ ṣe àkọsílẹ̀ èdè Yorùbá ní ọdún 1819.
- Hannah Kilham ṣe àkójọpọ̀ ẹyọ ọ̀rọ̀ Yorùbá ní ọdún 1828
- Ọdún 1829 ni Hugh Clapperton náà ṣe àkójọpò ọ̀rọ̀ ilẹ̀ Yorùbá
- John Raban gbé ìwé mẹ́ta jáde ní ọdún 1830, 1831 àti 1832 èyí tí ó ṣe àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ ilẹ̀ Yorùbá bákan náà
- Ọjọ́ kẹsàn-án oṣù kìnní ọdún 1844 ní àlùfáà Sámúẹ̀lì Àjàyí Crowther wàásù fún ìgbà àkọ́kọ́ ní èdè Yorùbá ní Freetown ní Sàró. Ìwé ìhìnrere Luku 1:35 tí ó kà báyìí "ohung ohwoh ti aobih inoh re li amkpe ti omoh Olorung" ní o fi ṣe ẹsẹ ìwàásù rẹ̀
- Samuel Ajayi Crowther yìí kan náà ló túmọ̀ Bíbélì sí èdè Yorùbá ní ọdún 1851
- Ìpàdé tí ó wáyé ní Fájì ní ìlú Èkó ní ọjọ́ kejìdínlọ́gbọ̀n sí ìkọkàndínlọ́gbọ̀n oṣù kínní ní ọdún 1875 ni wọ́n ti fi ẹnu kò lórí ọ̀nà tí a ó máa gbà kọ èdè Yorùbá sílẹ̀. Àbájáde ìpàdé yìí ló bí ọ̀nà tí a ń gbà kọ̀ èdè Yorùbá sílẹ̀, bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìpàdé kọ̀ọ̀kan tún padà wáyé, ṣùgbọ́n ìpàdé ọdún 1875 tí a sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí ló ṣe ọ̀pákútẹ̀lẹ̀ fún bí èdè Yorùbá ṣe di igi àlọ́yè.

### Ìdàgbàsókè Ìtàn Àròsọ Yorùbá

Ó yẹ kí o mọ̀ pé lẹ́yìn tí àwọn ajíyìnrere ẹlẹ́sìn Krístì ti rí i dájú pé èdè Yorùbá di kíkọ sílẹ̀ ní akitiyan ọlọ́kanòjọ̀kan ti bẹ̀rẹ̀ láti rí i dájú pé ìtàn àròsọ Yorùbá di kíkọ sílẹ̀. Iṣẹ́ takun-takun ni àwọn ìwé ìròyìn Yorùbá ṣe èyí tí o sì yẹ kí a pé àkíyèsí rẹ sí.

- Henry Townsend ni ẹni àkọ́kọ́ tí ó dá ìwé ìròyìn fún Ẹ̀gbá àti Yorùbá sílẹ̀ ní ìlú Abẹ́òkúta ni ọdún 1859, ìtẹ̀síwájú ìyìnrere sì ni èròǹgbà dída ìwé ìròyìn yìí sílẹ̀
- David Hinder túmọ̀ ìwé John Buyan Pilgrims's progress sí èdè Yorùbá ní ọdún 1911.
- Ìwé mẹ́ta tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa agbára àwámárìdìí àti ọgbọ́n Ọlọ́run tí o sì tún jẹ́ ìtàn àlọ́, àsàyàn Bíbélì àti ìkìlọ̀ ìwà ni Ajísafẹ́ gbé jáde ní ọdún (1921) Ènìà sòro, (1921) Tań t'Ọ́lọ́run àti (1923) Ìwé ìgbádùn Ayé
- Adéoyè Dénigà dá ìwé Ìròyìn Èkó Àkéte sílẹ̀ ní ọdún 1922.
- Akìtàn náà da ìwé ìròỳin Elétí ọfẹ sílẹ̀ ní ọdún 1923.
- Ọbasá gbé ìwé Ìròyìn Yorùbá jáde ní ọdún 1924
- I.B. Thomas gbé ìwé ìròyìn Akéde Èkó jáde ní ọdún 1928.

Ìgbìyànjú àkọ́kọ́ láti kọ ìtàn àròsọ Yorùbá sílẹ̀ ló wáyé ní ọwọ́ Akintan nínú ìwé ìròyìn Elétí ọfẹ ní ọjọ́ kẹrin oṣù kẹjọ ọdún 1926 èyí tí ó sọ̀rọ̀ nípa *Bámwò ọmọ òrukan* èyí tí ó dojúkọ onírúurú ìsòro àti ìdààmú ṣùgbọ́n nítorí ìpamọ́ra àti ìwà akin rẹ̀, o padà di aya ọba. Lẹ́yìn tí Akintan ti gbé ìtàn àròsọ yìí jáde ní ìgbà mẹ́rìndínlọ́gbọn nínú ìwé ìròyìn rẹ̀ ló wá sí ìdánudúró ní oṣù kẹsàn-án ọdún 1927. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìtàn àròsọ *Bamwo ọmọ orukan* ló jẹ́ ìgbìyànjú àkọ́kọ́ láti kọ ìtàn àròsọ àkọ́kọ́ sílẹ̀, síbẹ̀ kìí ṣe ìtàn àròsọ àkọ́kọ́ torí pé lẹ́yìn tí ó ti wá sí ìdánidúró nínú ìwé ìròyìn, kò sí àkọsílẹ̀ kankan pé a gbé ìtàn Bámwò jáde gẹ́gẹ́ bí odidi ìwé ìtàn àròsọ. Fún ìdí èyí, kì í ṣe ìwé ìtàn àròsọ àkọ́kọ́, atọ́nà lo jẹ́ fún ìtàn àròsọ àkọ́kọ́ lédè Yorùbá.

Olùdásílẹ̀ ìwé ìròyìn Akéde Èkọ́ I.B Thomas ló bẹ̀rẹ̀ sí ní gbé ìtàn *Èmi Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún ọkọ Láyé* jáde nínú ìwé ìròyìn rẹ̀ láti July 4 1929 sí March 8, 1930. Lẹ́yìn tí ìtàn àròsọ yìí wá sí ìdánudúró nínú ìwé ìròyìn ní àwọn ènìyàn bẹ̀ ẹ́ pé kí ó sọ ọ́ di odidi ìwé.

Ní ìdáhùn sí ìbéèrè àwọn ènìyàn I.B. Thomas gbé ìtàn àròsọ Èmi Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé jáde ni ọdún 1930. Ohun sì ni ìwé ìtàn àròsọ àkọ́kọ́ ní èdè Yorùbá.

## 4.3 Àhunpọ̀ ìtàn Nínú Ìtàn Àròsọ Yorùbá

Àhunpọ̀ ìtàn ṣe pàtàkì nínú ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá torí ọ̀nà tí òǹkọ̀wé kan bá gbà láti hun ìtàn rẹ̀ pọ̀ ni yóò sọ bí irúfẹ́ ìwé ìtàn àròsọ bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà tàbí bẹ́ẹ̀ kọ. Ó yẹ kí o mọ̀ pé ètò ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé ìtàn àròsọ gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ṣe tò ó tàbí ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin ní a mọ̀ sí àhunpọ̀ ìtàn. Àhunpọ̀ ìtàn nínú ìtàn àròsọ kò gbọdọ̀ lọ́jú pọ̀ rárá, ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé ìsewẹ́kú gbọdọ̀ wá, ìṣẹ̀lẹ̀ gbọdọ̀ máa so pọ̀ mọ́ ara wọ́n lọ́nà tó yanjú, tí àgbọ́yé yóò sì fi wà. Àhunpọ̀ ìtàn ínú ìtàn àròsọ lè bá àrògún ojú ayé mu, èyí sì lè má rí bẹ́ẹ̀. Bí òǹkọ̀wé kan bá ṣe hùn ìtàn rẹ̀ pọ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó máa ń sọ irú ìhà tí òǹkọ̀wé kọ sí ohun tí ìtàn àròsọ rẹ̀ dálé.

Ọ̀nà mẹ́ta ni a lè pín àhunpọ̀ ìtàn inú ìwé ìtàn àròsọ sí. Èyí ni: ìbẹ̀rẹ̀, àárín àti ìparí. Ní ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn ni òǹkọ̀wé tí máa ń pàjùbà nípa àwọn onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ tí kò ní se aláìwáyé nínú ìtàn náà. Nígbà tí àhunpọ̀ ìtàn bá ń de àárín ni orísìírísìí ni ìkọlura àti èdè-àìyedè yóò máa wáyé láàrin àwọn èdá ìtàn. Òtéńté àhunpọ̀ ìtàn àròsọ ni yóò ti máa sáré tete lọ sí òpin. Ìparí àhunpọ̀ ìtàn àròsọ ni òǹkọ̀wé yóò ti wá ojútùú sí gbogbo èdè-àìyedè tàbí aáwọ̀ tí o ti sẹlẹ̀ nínú àhunpọ̀ ìtàn àròsọ yòówù tí kò bá wá ojútùú sí gbogbo ìkọlura tó wáyé nínú àhunpọ̀ ìtàn lópin ìtàn kò kógojá gẹ́gẹ́ bí òǹsọ̀tàn

**Fọ̀nrán Àhunpọ̀ Ìtàn**

Kí àhunpọ̀ ìtàn àwọn òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ lè ṣe ìtẹ́wọ́gbà onírúurú fọ̀nrán ni wọ́n máa ń sàmúlò nínú àhunpọ̀ ìtàn wọn. Bí òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ kan bá kùnà láti sàmúlò àwọn fọ̀nrán yìí, ìtàn rẹ̀ yóò kan ṣe sákálá lásán ni, kò sì ní jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ. Lọ́nà àti dènà èyí, àwọn fọ̀nrán tí òǹkọ̀wé máa ń lò láti jẹ́ kí àhunpọ̀ ìtàn wọn dùn ni ìjọnilójú, àwàdà àti ìkóniláyàsókè.

**Ìjọnilójú**: Ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé tàbí òǹsọ̀tàn ìtàn àròsọ máa ń dá láti jẹ́ kí ìrètí àwọn òǹkọ̀wé rẹ̀ yọrí sí ibi tí wọn kò lérò ní ìgbẹ̀yìn ni a mọ̀ sí ìjọnilójú.

**Àwadà:** Ní ìgbà tí ìtàn àròsọ kan bá jẹ́ ládojúdé òǹkọ̀wé máa ń dọ́gbọ́n fífi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ apanilẹ́rìn-ín sí àárín àwọn àhunpọ̀ ìtàn rẹ̀ kí ó má ba à sú àwọn òǹkàwé láti kà.

**Ìkóláyàsókè**: Ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé dà láti gbé ìfẹ́ àwọn òǹkàwé rẹ̀ ro lọ́nà àti nífẹẹ̀ láti mọ àbájáde ọ̀rọ̀ kan tàbí ìsèlẹ̀ kan ni a mọ̀ sí ìkóláyà sókè.
Ní ìgbà tí òǹkọ̀wé bá ṣàmúlò àwọn fọ̀nrán tí a dárúkọ ni òkè yìí dáradára, ohun tí ó dájú ni pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ni yóò ni ìfẹ́ àtika irúfẹ́ ìtàn àròsọ bẹ́ẹ̀

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín kìnní, módù kẹta, ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò ìtàn àròsọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ìtàn tí òǹsọ̀tàn fi inú rò, tí o sì kọ sílẹ̀ fún ìgbádùn, àkàyé àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ènìyàn àwùjọ. A tún jẹ́ kí o mọ̀ pé láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ayé àwọn ẹ̀yà Yorùbá ni wọ́n ti máa ń sọ́ ìtànb fèyíkọ́gbọ́n lórísìírísìí láti kọ́ àwọn ọmọ wọn ni ẹ̀kọ́ ìwà. Àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun tí ó jẹ́ ajíhìnrere ọmọlẹ́yìn Krístì ló mú ẹ̀kọ́ ìwé wá èyí tí o sì fàáyè gbà mọ̀-ọ́n-kọ mọ̀-ọ́n-kà. Ìmọ̀ ẹ̀kọ́ yìí ló ṣe okùnfà tí ìtàn àròsọ fi di ohun tí a ń kọ sílẹ̀.

Ní ìparí ìpín kínní yìí a ti kọ́ pé:

- Ìtàn àròsọ jẹ́ ìtàn tí òǹkọ̀wé fi inú rò, tí ó sì kọ sílẹ̀ fún ìgbádùn, àkàyé àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àwọn ènìyàn àwùjọ
- Ìtàn àròsọ lè jẹ́ èyí tí ó sojú òǹsọ̀tàn, èyí tí a sọ fún un tàbí tí ó finú rò.
- Orísìírísìí ìtàn fèyíkọ́gbọ́n ní àwọn ẹ̀yà Yorùbá fí máa n kọ àwọn ọmọ wọn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀.

- Àwọn ajíyìnrere ọmọlẹ́yìn Krístì tó mú ẹ̀kọ́ ìwé wá ló ṣe okùnfà bí ìtàn àròsọ Yorùbá ṣe di kíkọ sílẹ̀
- Ìtàn Èmi Bámwò ọmọ Orùkan tí Akíntàn gbé jáde nínú ìwé ìròyìn Elétí Ọfe ní 1926 ló jẹ́ ìgbìyànjú àkọ́kọ́ láti kọ ìtàn àròsọ Yorùbá sílẹ̀
- Ìtàn Èmi Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé tí I.B. Thomas gbé jáde ní 1930 ni ìwé ìtàn àròsọ àkọ́kọ́ ní èdè Yorùbá.
- Ìtàn àròsọ gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ṣe tò ó láti ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin ní a mọ̀ sí àhunpọ̀ ìtàn.
- Àhunpọ̀ ìtàn nínú ìtàn àròsọ kò gbọdọ̀ lọ́jú pọ̀ rárá, ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé ìsewẹ́kú gbọdọ̀ wá, ìṣẹ̀lẹ̀ gbọdọ̀ máa so pọ̀ mọ́ ara wọ́n lọ́nà tó yanjú, tí àgbọ́yé yóò sì fi wà.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

- Jíròrò lórí ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbàsókè ìtàn àròsọ Yorùbá
- Ṣàlàyé ohun tí àhunpọ̀ ìtàn jẹ́
- Àwọn ọ̀nà wo ni àhunpọ̀ ìtàn lè pín sí?
- Kí ni èrò rẹ̀ nípa òténté
- Jíròrò lórí àwọn fọ́nrán tí òǹkọ̀tàn máa ń lò lọ́nà àti mú kí ìtàn rẹ̀ ṣe ìtẹ́wọ́gbà.
- Ka ìtàn kékeré ìsàlẹ̀ yìí kí o sì ṣe àfàyọ àwọn kókó ẹ̀kọ́ tó jẹyọ nínú rẹ̀.
- Wá àwọn ìwé ìtàn-àròsọ kéékèèkéé láti kà.

**Ọ̀kánjúwà ní í dolè**

Olúrínú àti Abólóúnjẹkú jọ ń ṣe ọ̀rẹ́ nígbà kan. Ọ̀rẹ́ wọn kì í tanná kí wọn tó jọ jẹun. Ọ̀rẹ́ ni wọ́n ṣe di àkókò tí ìyàn mú ní ìlú, ti gbogbo nǹkan di 'Ọlọ́mú dọ́mú ìyá rẹ̀ gbé. Olúrínú ṣe àwárí oko olóko kan níbi tó ti ń rí iṣu méjì méjì wà lójoojúmọ́. Yóò gbé iṣu náà sínú àpò ajílẹ̀. Bó bá di òru-òun àti ìyàwó rẹ̀ a gún iyán fẹlifẹli jẹ. Abólóúnjẹkú kò rí ọ̀nà gbé e gbà mọ́. Bó bá lọ sí ilé ọ̀rẹ́ rẹ̀, tó jókòó di ìrọ̀lẹ́, wọn yóò kàn jọ máa tàkúrọ̀sọ ni. Kò kúkú sí tátà lójú yányàn. Ṣùgbọ́n ó ń ṣàkíyèsí pé Olúrínú kò rù hangogo bíi tòun. Ó takú lálẹ́ ọjọ́ kan láti mọ ibi tí eyín egúngún tó ń jobì wà. Ó tó àkókò kó lọ, ìtàn ayé nà-mí-n-nalẹ̀ ló mú ba ẹnu. Ìyàwó Olúrínú seṣu jinná, óku bí yóò ṣe gún un. Ó wà fi ọgbọ́n pe ọkọ rẹ̀, 'Ìyá kòtíìlọ tilẹ̀ rán mi síi yín, baálé wa'. Olúrínú bọ́ sí ẹ̀yìnkùlé, wọ́n fi odó lọ iyán bí ẹni lọ ata. Nígbà tí Abólóúnjẹkú kò gbúròó ọ̀rẹ́ rẹ̀ fún ìṣẹ́jú díẹ̀, ó yọjú sí àgbàlá. Ọ̀rọ̀ tí a ní baba ó máà gbọ́, àṣe baba ni yóò parí ẹ̀. Wọ́n ṣá jọ rẹ́yìn oúnjẹ alẹ́ ọjọ́ náà ni. Nígbà tó di ojoojúmọ́ tí ọ̀rẹ́ ń wá, tó ń dẹ̀bìtì àyà sílé olóúnjẹ, Olúrínú sọ àṣírí ibi tó ti ń rọ́wọ́ mú rẹnu fún un. Olúrínú mú ọ̀rẹ́ yìí lọ sí ibi ti àṣírí ti ń bò. Kò pẹ́ tí wọ́n ti ibẹ̀ dé ni jagunlabí tún gbé agbọ́n lé ìyàwó rẹ̀ lórí, ó doko olóko. Kò tíì wa agbọ̀n iṣu kan tán ni ọwọ́ olóko tẹ̀ ẹ́. Wá wo ẹ̀sìn tọkọtaya lójúde ọba.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ìṣọ̀lá, A. (1998). *The Modern Yorùbá Novel (An analysis of the writer's art)* Ibadan: Heinemann Education Books (Nigeria) Plc.

Ògúnsínà, B. (2006). *Sociology of the Yorùbá Novel: An Introduction.* Ilorin Integrity Publication.

Ògúnsínà, J.A (2976). *The Development of the Yorùbá Novel M. Phil Dissertation,* University of Ibadan, Ibadan

# ÌPÍN KEJÌ ÌPÍNSÍSỌ̀RÍ ÌTÀN ÀRÒSỌ YORÙBÁ

## Àkòónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ìpínsísọ̀rí Ìtàn Àròsọ Yorùbá
 4.2 Ìtàn Àròsọ Méríìrí
 4.3 Ìtàn Àròsọ Abáyému
 4.4 Ìtàn Àròsọ Ajẹmọ́ Ìtàn gidi
 4.5 Ìtàn àròsọ Ajẹmawùjọ
 4.6 Ìwé Ìtàn Àròsọ Ajẹmọ́ Ọ̀ràn Dídá
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Ìpín kejì yìí ni a ó bẹ̀rẹ̀ nípa síṣe ìpínsísọ̀rí ìtàn àròsọ Yorùbá. Àwọn ìsọ̀rí wọ̀nyí ni a ó pín wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́, tí a ó si ṣàlàyé rẹ̀ ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Kò sí àní àní pé o lè pín ìtàn àròsọ Yorùbá sí àwọn ìsọ̀rí tí ó yẹ lẹ́yìn tí o bá ti ka ìpín kejì yìí tán.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o lè
i. Pín ìtàn àròsọ yorùbá sí ọ̀nà tí ó yẹ
ii. Ṣàlàyé ni òrínkíniwín lórí oríṣìíríṣìí ọ̀nà tí a pín ìtàn àròsọ Yorùbá sí.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Ṣe ìpínsísọ̀rí fún ìtàn àròsọ Yorùbá
ii. Jíròrò lórí ìtàn àròsọ mérìírí

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìpínsísọ̀rí Ìtàn Àròsọ Yorùbá

Ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá lọ́lọ́kan-òjọ̀kan ló wa lórí igbá tí àwọn òǹkọ̀wé tí kọ. Ó yẹ kí o mọ̀ pé ọ̀nà méjì ggbòòrò ní a lè pín ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá sí. Àkọ́kọ́ ni ìwé ìtàn àròsọ mérìírí èyí tí a tún mọ̀ sí ìtàn àròsọ onílànà Fágúnwà. Èkejì ni ìtàn àròsọ abáyemú tàbí ìtàn àròsọ òde òní. Ní báyìí a ó máa ṣàlàyé àwọn ìsọ̀rí ìtàn àròsọ yìí ni sísẹ̀-n-tẹ̀lé.

## 4.2 Ìtàn Àròsọ Mérîìrí

Ìtàn àròsọ nínú èyí ti àjọsepọ̀ ti máa ń wáyé láàrin, ẹranko, ẹyẹ, iwin, igi àti ẹ̀dá ènìyàn ni a mọ̀ sí ìtàn àròsọ mérîìrí. Ìtàn àròsọ mérìírí yìí kan náà ni a tún máa ń pè ní ìtàn àròsọ onílànà Fágúnwà torí Fágúnwà ni òǹkọ̀wé àkọ́kọ́ tí ó kọ ìwé ìtàn àròsọ mérìírí ni o jẹ́ kí a máa fi ouńkọ Fágúnwà pé irúfẹ́ ìsọ̀tàn bẹ́ẹ̀. Ìwé ìtàn àròsọ márùn-ún ni Fágúnwà kọ tí ó jẹ́ méríírí. Àwọn ìwé ìtàn àròsọ náà ni: *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmọlẹ̀, Igbó Olódùmarè, Ìrèké Oníbùdó, Ìrìnkèrindò Nínú Igbó Elégbèje* àti *Àdììtú Olódùmarè*. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn kan rò pé ọ̀kanùn ni kánún ní àwọn ìwé ìtàn àròsọ Fágúnwà máràárún, èyí kò rí bẹ́ẹ̀ tórí ìwé kọ̀ọ̀kan ló ni olú ẹ̀dá ìtàn tirẹ̀., bẹ́ẹ̀ ni olú ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan ni o lọ sí ìrìnàjò àko tirẹ̀. Èyí nìkan kọ́ àwọn ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì, ọ̀rọ̀ ìfẹ́, oúnjẹ, aṣọ wíwọ̀ àti onírúurú àṣà Yorùbá tó wáyé ń ṣàfihàn àwùjọ Yorùbá ni. Kìí ṣe Fágúnwà nìkan ni o kọ gbogbo àwọn ìwé ìtàn àròsọ mérìírí, àwọn òǹkọ̀wé mìíràn tí o gùn lé irúfẹ́ ìsọwọ́kọ̀wé Fágúnwà ni Ògúndélé tí o kọ *Èjìgbèdè Lọ́nà Ìsálú-Ọ̀run* àti *Ibú Olókun, Ọmọ́yájowó* tí ó kọ *Ìtàn Ọdẹ́níyà àti Ìtàn Adégbẹ̀san*, Ọdúnjọ tí ó kọ *Kúyẹ̀* àti *Ọmọ Òkú Ọ̀run*, Jẹ́bọdà tí o kọ *Olówolaiyémọ̀*, Fátànmí tí ó kọ *Kórímálẹ̀ nínú Igbó Adìmúlà* àti àwọn mìíràn.

Ó yẹ́ kí o mọ̀ pé àwọn ìwé ìtàn àròsọ méríírí tí a ń sọ̀rọ̀ nípa wọn yìí ni àwọn àbùdá pàtàkì tí a fi ń dá wọn mọ̀. Lákọ̀ọ́kọ́ inú omi, ihò ilẹ̀, aginjù, ojú ọ̀run àti orí òkè ni ó sábà máa ń jẹ́ ibùdó ìtàn àròsọ mérìírí kò sí ìdíwọ̀ kankan fún òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ méríírí, èyí ni o ṣe rọrùn fún àwọn ẹ̀dá ìtàn àròsọ yìí láti lọ sí ibi tí ó wù wọ́n láìsí ìdíwọ̀ kankan, ìrànlọ́wọ́ òjijì tí àwọn ẹ̀dá ìtàn máa ń rì gbà láti ọ̀dọ̀ alàaye tàbí òkú ní ìgbà ìsòro tún jẹ́ àbùdá mìíràn fún ìtàn àròsọ mérìírí.

## 4.3 Ìtàn Àròsọ Abáyému

Àwọn ìtàn àròsọ tí ó máa ń dálé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó máa ń wáyé láàrin àwùjọ ènìyàn ni a mọ̀ sí ìtàn àròsọ abáyemu tàbí ìtàn àròsọ òde-òní. Ọ̀nà mẹ́ta gbòòrò ní a lè pín ìtàn àròsọ abáyemu sí, èkínní ni ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ìtàn gidi, èkejì ni ìtàn àròsọ ajẹmáwùjọ, ní ìgbà tí ìkẹta jẹ́ ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá.

## 4.4 Ìtàn Àròsọ Ajẹmọ́ Ìtàn gidi

Ó yẹ́ kí o mọ̀ pé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ìtàn gidi máa ń sọ̀rọ̀ lórí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti wáyé sẹ́yìn láwùjọ, èyí tí òǹkọ̀wé lè ṣe àfikún tàbí àyọkúrò pẹ̀lú ọgbọ́n àtinúdá tirẹ̀. Àwọn òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ìtàn gidi kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ torí àwọn òǹkọ̀wé ni ìsọ̀rí yìí jẹ́ àwọn tí ó ní ìrírí púpọ̀ nípa àwùjọ wọn, tí wọn si súnmọ́ àwọn àgbà. Ṣé Yorùbá bọ̀ wọn ni "bí ọmọ kò bá ìtàn, yóò bá àrọ̀bá, àti pé àrọ̀bá ni baba ìtàn". Àìlè mú ìtàn sọ bí òǹkọ̀wé ti fẹ ni kò jẹ́ kí àwọn òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ìtàn gidi pọ rárá. Ẹ̀ta hóró ní àwọn òǹkọ̀wé tí ó wà ni ìsọ̀rí yìí. Isaac Délaní ni ó kọ ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ìtàn

gidi méjì: *Lọ́jọ́ ọjọ́un* àti *Ayé daiyé Òyìnbó*. Nígbà tí Adébáyọ̀ Fálétí kọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin*. Ní ìgbà tí ìtàn àròsọ *Lọ́jọ́ ọjọ́un* ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ọlọ́kanòjọ̀kan tó wáyé ni ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ayé àwọn ẹ̀yà Yorùbá, *Ayé daiyé Òyìnbó* ní tirẹ̀ ń tọ́kasí àwọn àyípadà tí àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun mú wọ àwùjọ Yorùbá, èyí tí ó mú àyípadà bá ìgbésí ayé wọn. Ìjìjagbara àwọn ará òkè ògùn kúrò lábẹ́ ìsìnrú Òtu ni Adébáyọ̀ Fálétí sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin*.

## 4.5 Ìtàn àròsọ Ajẹmawùjọ

Ó dára kí o mọ̀ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí ó dá lórí ẹ̀sìn, òṣèlú àti àṣà ni a mọ̀ sí ìtàn àròsọ ajẹmáwùjọ. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ni àwọn ìwé ìtàn àròsọ ajẹmáwùjọ tí ó wà lórí igbá. Lára àwọn ìwé ìtàn àròsọ ajẹmáwùjọ tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn ni a ti ri *Ọlọ́un Lúgọ* tí Débọ̀ Awẹ́ kọ,. *Kékeré Ẹkùn* àti *Àyànmọ́* tí Ọlábímtán kọ àti *Jẹ́ N Lògbà Tèmi* èyí tí Ládélé kọ. *Sàngbá Fọ́* ti Akínlàdé kọ, *Ọ̀tẹ̀ Nìbò* láti ọwó Olú Owólabí, *Bàbá Rere àti Orílawẹ̀ Àdìgún* tí Ọlábimtán kọ ni wọn jẹ́ àpẹẹrẹ ìtàn àròsọ ajẹmọ́ òṣèlú. Àwọn ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ àwùjọ tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa àṣà Yorùbá ni *Gbọ́baníyì* láti ọwọ́ Yémítán, *Ó sojú mi* tí Yínká Adébàjẹ́ kọ, *Àárọ̀ Olómọge* tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ àti *Ìtàn Èmi Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé* ti I.B. Thomas kọ. Ọ̀goọ̀ọ̀rọ̀ ni àwọn òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá tí wọ́n ń kọ ìtàn àròsọ ajẹmáwùjọ torí ààyè gbà wọ́n láti kọ ìtàn wọn bí wọn ṣe fẹ́ pẹ̀lú ìrọ̀rùn. Bóyá ìtàn àròsọ ajẹmọ́ àwùjọ jẹ́ èyí tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn, òṣèlú, tàbí àṣà, igbó kan náà ni ọdẹ gbogbo wọn jọ ń dẹ, ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé ọ̀rọ̀ nípa ìgbáyégbádùn àti ìdàgbàsókè àwùjọ ni ó jẹ gbogbo àwọn òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ wọ̀nyí lógún.

## 4.6 Ìwé Ìtàn Àròsọ Ajẹmọ́ Ọ̀ràn Dídá

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà tí àwọn ọ̀daràn máa ń gbà ṣe iṣẹ́ ibi wọn láwùjọ àti àwọn ọ̀nà àbáyọ kúrò lọ́wọ́ àwọn ọ̀daràn wọ̀nyí ni àwọn ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá máa ń tẹnumọ́. Ọ̀nà méjì ni àwọn ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá pín sí. Èkínní ni ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ nígbà tí ìkejì jẹ́ ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá amárabùmásọ. Kọ́lá Akínlàdé ní òǹkọ̀wé tí ó yan kíkọ ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ láàyò nígbà tí òǹkọ̀wé Ọládẹ̀jọ Òkédìjí gbajúmọ̀ ní kíkọ ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá amárabùmáṣọ. Ní ìgbà tí àwọn akọ́sẹ́mọsẹ́ olùwádìí máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn ọ̀ràn tí wọ́n bá dá nínú ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ Ọlọ́pàá tí o ti fẹ̀yìntì lẹ́nu iṣẹ́ ọlọ́pàá ni ó ń ṣe iṣẹ́ takuntakun pẹ̀lú àwọn ìpátá láti kojú àwọn ọ̀daràn tí àwọn ọlọ́pàá kùnà láti kápá. Àpẹẹrẹ àwọn ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ni: Owó Ẹ̀jẹ́, Asenibánidárò, àsírí Amòòkùnjalè Tú, Báyọ̀ Ajọ́mọgbé àti Ta ló pa Ọmọọba., nígbà tí Àjà ló lẹrù, Àgbàlagbà Akàn àti Kárìn ká pọ̀ jẹ́ àpẹẹrẹ ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá àmárabùmásọ.

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín kejì yìí a ti kọ́ pé

- Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a lè pín ìwé ìtàn àròsọ yorùbá sí: Mérìírí àti Abáyému
- Ìtàn àròsọ mérìírí náà ni Onílànà Fágúnwà
- Ìtàn àròsọ abáyému ni a tún mọ̀ sí ìtàn àròsọ òde òní
- Fágúnwà ni òǹkọ̀wé àkọ́kọ́ tí ó kọ ìwé ìtàn àròsọ mérìírí
- Àwọn òǹkọ̀wé mìíràn tó gùnlé ìsọwọ́kọ̀wé Fágúnwà ni: Ògúndélé, Ọmọ́yájowó, Jẹ́bọdà àti Ọdúnjọ
- Àbùdá pàtàkì tí ìtàn àròsọ mérìírí ní ni ibùdó ìtàn mérìírí àti ìrànlọ́wọ́ òjijì
- Ìtàn àròsọ ajẹmọ́ àwùjọ lè sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn, òṣèlú tàbí àṣà
- Ìwé ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá pín sí ọ̀nà méjì: Ọtẹlẹ̀múyẹ́ àti amárabùmáṣọ

## 6.0 IṢẸ́ SÍṢE

1. Ṣe ìpínsísọ̀rí tó gbòòrò fún ìtàn àròsọ Yorùbá
2. Àwọn àbùdá wo ni ìtàn àròsọ mérìírí ní?
3. Kí ni àwọn ìwé ìtàn ajẹmáwùjọ máa ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀?
4. Pààlà láàrin ìtàn àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá amárabùmásọ àti ọ̀telẹ̀múyẹ́

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ìṣọ̀lá, A. (1998). *The Modern Yorùbá Novel (An analyses of the writers art)* Ibadan: Heineman Educational Books (Nigeria) Plc.

Ògunsina, B. (2006). Sociology of the Yorùbá Novel: An introduction. Ilorin: Integrity publication.

Ogunsina, J.A (1976). *The Development of the Yorùbá Novel.* M.Phil Disertation, University of Ibadan, Ibadan.

## ÌPÍN KẸTA ÌFÌWÀWẸDÁ NÍNÚ ÌTÀN ÀRÒSỌ YORÙBÁ

**Àkòónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
- 4.1 Ohun ti ìfìwàwẹ̀dá jẹ́
- 4.2 Oríṣìíríṣìí ẹ̀dá Ìtàn
- 4.3 Olú Ẹ̀dá Ìtàn
- 4.4 Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Ẹ̀dá Ìtàn
- 4.5 Àgbékalẹ̀ ẹ̀dá Ìtàn
- 4.6 Ìsesí
- 4.7 Ìrísí
- 4.8 Ìhùwàsi
- 4.9 Orúkọ

5.0 Ìsọnisókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kẹta lábẹ́ módù kẹta, ohun tí ijíròrò yóò máa wáyé tí a ó sì máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ ní ìfìwàwẹ̀dá nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. A ó sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́, àwọn oríṣìírísìí ẹ̀dá ìtàn tí a lè bá pàdé nínú ìtàn àròsọ Yorùbá àti àwọn onírúurú ọ̀nà tí òǹkọ̀wé lè gbà gbé àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ìtàn àròsọ rẹ̀ kalẹ̀.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kẹta yìí, ó lè:

i. Ṣàlàyé ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́ nínú ìtàn àròsọ Yorùbá
ii. Pín àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ìtàn àròsọ Yorùbá sí ìsọ̀rí tí o yẹ
iii. Ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀nà tí òǹsọ̀tàn ìwé ìtàn àròsọ lè gbà ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Sọ ohun tí o mọ̀ nípa ìfìwàwẹ̀dá
ii. Jíròrò nípa ọ̀nà tí òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ kan tí o kà gbà fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀

## 4.0 ÌDÁNILÉKỌ̀Ọ́

### 4.1 Ohun ti ìfìwàwẹ̀dá jẹ́

Ó yẹ kí o mọ̀ pé àwọn ète àti ọgbọ́n lóríṣìíríṣìí tí òǹkọ̀tàn máa ń dá láti fún àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ìtàn rẹ̀ ní àwòmọ́ ẹ̀dá ènìyàn láwùjọ ni a mọ̀ sí ìfìwàwẹ̀dá. Nínú ìtàn àròsọ Yorùbá àwọn ẹ̀dá ìtàn ni òǹkọ̀wé máa ń lò láti pàsamọ̀ ohun tí ó ní lọ́kàn sí àwọn ènìyàn àwùjọ. Amọ̀ ni àwọn ẹ̀dá ìtàn jẹ́ nínú ìtàn àròsọ Yorùbá ní ìgbà tí òǹkọ̀tàn jẹ́ amọ̀kòkò. Fún ìdí èyí ohun tí o bá wu amòkòkò òǹkọ̀tàn nínú ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá ni ó máa ń fi àwọn ẹ̀dá itàn rẹ̀ tí wọ́n jẹ́ amọ̀ mọ. Gbogbo àbùdá ènìyàn ni òǹkọ̀tàn lè gbé wọ ẹ̀dá ìtàn tó bá yàn láàyò, bẹ́ẹ̀ ni ó lágbára láti ṣe àfihàn ìrònú ẹ̀dá ìtàn àti ìgbésí ayé rẹ̀.

### 4.2 Oríṣìíríṣìí ẹ̀dá Ìtàn

Ọ̀kanòjọ̀kan ni àwọn ẹ̀dá ènìyàn tó wà ni àwùjọ. Irúfẹ́ isẹ́ tí òǹkọ̀tàn bá fẹ́ rán sí àwùjọ ni yóò sọ irúfẹ́ ẹ̀dá ìtàn tí yóò ṣàmúlò láti báa a jẹ́ iṣẹ́ náà. Àwọn ẹ̀dá ìtàn oríṣìí méjì ni a lè bá pàdé nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. Ẹ̀dá ìtàn àkọ́kọ́ tí a lè bá pàdé ni Olú ẹ̀dá ìtàn nígbà tí ẹ̀dá ìtàn kejì jẹ́ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Olú ẹ̀dá Ìtàn. Ìyàtọ̀ tó gbòòrò ló wà láàrin irúfẹ́ àwọn ẹ̀dá ìtàn méjèèjì tí a dárúkọ. Ni báyìí, a ó sọ̀rọ̀ nípa oríṣìí ẹ̀dá ìtàn méjèèjì.

### 4.3 Olú Ẹ̀dá Ìtàn

Ẹ̀dá Ìtàn tí ìsẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àròsọ dálé lórí láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin ni a mọ̀ sí Olú-Ẹ̀dá Ìtàn. Olú Ẹ̀dá ìtàn ṣe pàtàkì nínú ìtàn àròsọ Yorùbá, nítorí pé bí owó orí ṣe jẹ́ dandan, bẹ́ẹ̀ ni, ó pọn dandan láti ní olú ẹ̀dá ìtàn nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. Bí olú ẹ̀dá ìtàn ṣe jẹ́ dandan tò nínú ìtàn àròsọ, àìgbọdọ̀ má ṣe ni fun òǹkọ̀wé làti sẹ̀dá àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn tí yóò kópa pẹ̀lú olú ẹ̀dá ìtàn nínú ìtàn àròsọ Yorùbá.

### 4.4 Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Ẹ̀dá Ìtàn

Àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá ìtàn ni àwọn ẹ̀dá ìtàn tó darapọ̀ mọ́ olú ẹ̀dá ìtàn láti jẹ́ ki ìrìnàjò ìtàn àròsọ kógojá. Òǹkọ̀tàn lè sẹ̀dá àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ yìí láti ko wàhálà àti ìdàámú bá Olú ẹ̀dá ìtàn, o sì lágbára láti gbé àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá ìtàn yìí kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro tí olú ẹ̀dá ìtàn ń kojú. Òǹkọ̀tàn ni ó máa ń yan iṣẹ́ ti ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan yóò ṣe tàbí iṣẹ́ tí yóò jẹ́ nínú ìtàn àròsọ, kì bá à jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn tàbí amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn.

### 4.5 Àgbékalẹ̀ ẹ̀dá Ìtàn

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni òǹsọ̀tàn lè gbà láti gbé àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ kalẹ̀. Ọ̀nà yòówù tí ó bá yàn jẹ́ èyí tí ó gbàgbọ́ pé ó dara jùlọ láti jẹ́ iṣẹ́ tí ó fẹ́ rán sí àwùjọ.

Ìsesí, ìrísí, ìhùwàsí àti orúkọ ni òǹkọ̀tàn lè lò láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀.

## 4.6 Ìsesí

Ó jẹ́ ìwà kan tí o ti di bárakú fún ẹ̀dá ìtàn kan, ṣùgbọ́n tí ó lè má ni pa kankan lórí ẹ̀dá ìtàn mìíràn. Bí àpẹẹrẹ ìjá olú tí ó jẹ́ alábàágbélé Àlàbí ní ìlú Èkó jẹ́ aláriwo ẹ̀dá. Bákan náà ni Tàfá ìgìrìpa tí o jẹ́ ọmọ iṣẹ́ fún Lápàdé nínú ìtàn àròsọ àjà ló lẹ̀rù fẹ́ràn láti máa kí ara rẹ ni gbogbo ìgbà láti fi irú ẹ̀dá tí ó jẹ́ hàn. Àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí jẹ́ ọ̀kan lára bí Tàfá ṣe máa ń ki ara rẹ̀:

Èmi Tàfá ìgìrìpà ọmọ Láwálé
Èmi Àjàó Àró fúnrá mi, abojúbọmọlẹ́rù
Èmi abẹ́kún-pọmọ lẹ́kún
Abẹ̀rín-in pọmọ lẹ́kún
Olójú-bá-mi-dẹ́rù bọmọọ̀-mi
Ẹní bá kò mi ko túláàsì
Ẹni mo kò pàdé àgbákò
(Àjà ló lẹ̀rù o.i 56)

Ìsesí Tàfá ìgìrìpà àti bí o ṣe ń ki ara rẹ yìí ṣàfihàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀daràn pọ́ńbélé, tí ó kún fún iṣẹ́ ibi àti ìjàǹbá.

## 4.7 Ìrísí

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé “bí a ṣe rìn, là á koni àti pé “ìrínisí ni ìṣeni lọ́jọ̀”. Òǹkọ̀tàn lè lò àbùdá ìsẹ̀dá ẹ̀dá ìtàn, aṣọ tàbí ìmúra rẹ̀ láti fi ìrísí rẹ̀ hàn. Bákan náà ni òǹkọ̀tàn lè lo ẹ̀yà ara ẹ̀dá ìtàn nípa àpèjúwe láti fi ìrísí ẹ̀dá ìtàn hàn. Nínú ìwé ìtàn àròsọ *Sègilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé*, Sẹ̀gilọlá lò fi ìrísí ara rẹ̀ hàn.

Èmi jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọmọbìnrin ayé tí Ẹlẹ́dàá fi ẹwà ara ṣe lọ́sọ̀ọ́, tí kò ń ṣe díẹ̀. Ènìyàn pupa fòò”lèmi ń ṣe. Ẹwà ara mi kunna, ó sì wẹ́ pẹ̀lú. Ara mi rí múlọ́múlọ́ bíi ìrọrí ọlọ́wùú-ẹ̀gùngun. Mo sígbọnlẹ̀ láti òkè ara mi dé ilẹ̀. Èmi kò sanra jù lẹ́nìyàn, bẹ́ẹ̀ni èmi kò sì gbẹra kọjá ààlà (Thomas 2009:4)

Kò sí àní àní pé àpèjúwe tí Sẹ̀gilọlá ṣe nípa ara rẹ̀ nínú àyọlò òkè yìí fi hàn gẹ́gẹ́ bí arẹwà obìnrin tí Ẹlẹ́dàá dá ní àrà ọ̀tọ̀. Ohun tí òǹkọ̀tàn fẹ́ kí o di mímọ̀ nípa fífi ìrísí Sẹ̀gilọlá gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn hàn ni pé bí gbogbo ènìyàn ṣe mọ̀ Sẹ̀gilọlá gẹ́gẹ́ bí arẹwà obìnrin bẹ́ẹ̀ náà ni ẹwà Sẹ̀gilọlá ń pa òun fúnrarẹ̀ bí ọtí.

## 4.8 Ìhùwàsi

Ìṣe àti ìwá ènìyàn tí ó máa ń ní ipa rere tàbí búburú lórí ẹ̀dá ìtàn mìíràn ni a mọ̀ sí ìhùwàsí. Àwọn ìhùwàsí ẹ̀dá ìtàn tí o lè ní ipa búburú lórí ẹ̀dá ìtàn mìíràn ni olè, ìkórìíra, ọ̀dàlẹ̀, ìkà tàbí ìbínú. Ní ìgbà tí ìhùwadsí ẹ̀dá ìtàn tí ó máa ń ní ipa rere lórí ẹ̀dá ìtàn mìíràn jẹ́ ìfẹ́, òtítọ́, ìkónimọ́ra àti ìrẹ̀lẹ̀. Gbogbo ìwà pákáleke tí Àdìká ìyàwó Àjàdí ń hù nínú ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ ló mú kí Àjàdí máa pé ìyàwó rẹ̀ ní akọgba-túgbaká, lẹ́yìn tí wọn fi ẹ̀yin Àjàdí tí lẹ́nu iṣẹ́ rẹ, ó kọ̀ láti padà sí ọ̀dọ̀ ìyàwó rẹ̀ Àdìká, ó yàn láti máa ṣe òwò iṣu, èyí ló sì gé ẹ̀mí rẹ̀ kúrú. Ìwà burúkú Àdìká sí ọkọ rẹ̀ ni ipa búburú lóri ọkọ rẹ̀ àti gbogbo ẹbí Àjàdí.

## 4.9 Orúkọ

Àwọn ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ èyí tí kò fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú orúkọ, èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé orúkọ ọmọ ní i ro ọmọ àti pé orúkọ ọmọ ni ìjánu rẹ̀. Ọ̀kanòjọ̀kan orúkọ ni òǹkọ̀tàn lè fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀. Bí ó bá fẹ́, o lè fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ni orúkọ alárokò èyí tí ó jẹ́ pé yóò ní ìtumọ̀ tó jinlẹ̀ nínú ìfìwàwẹ̀dá àwọn ẹ̀dá ìtàn. Ẹ̀dá ìtàn tí ó ń jẹ́ Kàrímù Alákòóbá nínú ìwé ìtàn àròsọ "Àjà ló lẹrù" jẹ́ eléwú àti oníjàm̀bá ènìyàn, èyí túmọ̀ sí pé orúkọ ẹ̀dá ìtàn yìí ní ìtumọ̀ tí ó jinlẹ̀ lórí ìfìwàwẹ̀dá rẹ̀. Ní ìgbà mìíràn òǹkọ̀tàn lè fún ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ni orúkọ àmútọ̀runwá bíi Táyé, Ìdòwú, Ẹ̀taòkò, Ìgè, Ìlọ̀rí tàbí Ọ̀kẹ́, èyí nìkan kọ́, ó tún lè fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ní orúkọ oyè bí i Basọ̀run, Séríkí, Balógun, Ìyálóde tàbí ìyálájé bí ó bá fẹ́. Òǹkọ̀tàn sì tún lè fún ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ní orúkọ àbísọ bí i Abiọ́lá, Ayòmídé, Adéọlá tàbí Ọlamide, dandan ni kí òǹkọ̀tàn fún àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ìtàn àròsọ rẹ̀ kọ̀ọ̀kan ni orúkọ kí ó lè pààlà ẹ̀dá ìtàn kan sí òmíràn.

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín kẹta yìí ni a ti kọ́ pé:

- Ìfìwàwẹ̀dá ni àwọn ète tí òǹkọ̀tàn máa ń dá láti fún àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ìtàn rẹ̀ ni àwòmọ́ ẹ̀dá ènìyàn ní àwùjọ
- Ẹ̀dá ìtàn méjì tí a lè bá pàdé nínú ìtàn àròsọ ni Olú ẹ̀dá ìtàn àti Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá ìtàn.
- Olú ẹ̀dá ìtàn ni ìsẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àròsọ máa ń dálé láti ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin
- Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀dá ìtàn ni ó máa darapọ̀ mọ olú ẹ̀dá ìtàn láti jẹ kí ìtàn àròsọ kógojá
- Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni òǹkọ̀tàn lè gbà láti fi ìwà wọ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀
- Ìrísí, ìsesí, ìhùwàsí àti orúkọ ni òǹkọ̀tàn lè ṣàmúlò láti ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dá ìtàn rẹ̀
- Ìsesí jẹ́ ìwà tí ó ti di bárakú fún ẹ̀dá ìtàn kan
- Ìrísí jẹ́ àpèjúwe láti fi irísí tàbí àbùdá ìsẹ̀dá ẹ̀dá ìtàn hàn
- Ìhùwàsí jẹ́ ìse àti ìwà ènìyàn tó ní ipa rere tàbí búburú lórí ẹ̀dá ìtàn mìíràn
- Orúkọ ni òǹkọ̀wé máa ń fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ láti pààlà láàrin wọn.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé lórí ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́
2. Pààlà láàrin oríṣìí ẹ̀dá ìtàn tí a lè bá pàdé nínú ìtàn àròsọ Yorùbá
3. Àwọn ọ̀nà wo ni òǹkòtán lè gba ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Adébọ̀wálé, O. (1999). *Ọgbọ́n Òǹkọ̀wé Alátínúdá*. Lagos: The Capstone

Ìṣọ̀lá, A. (1998). *The Modern Yorùbá Novel: An Analysis of the Writer's Art*. Ìbàdán: Heinemnn Educational Books.

Ogundeji, P.A. (1991). Introduction to Yorùbá Written Literature, External Studies Programme, Department of Adult Education, University of Ibadan, Ibadan.

Ogúnsínà, B. (1992). *The Development of the Yorùbá Novel 1930 – 1975*. Ìlọ̀rin: Gospel Faith Mission Press.

Ogúnsínà, B. (2001) 'Ìdílè àti Ìdàgbàsókè Lítírẹ̀ṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá' nínú Ẹ̀kọ́ *Ìjìnlẹ̀ Yorùbá, Ẹ̀dà Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Bádé Àjàyí (olóòtú). Ìlọrin: University Press Ltd.

Ogunsina, B. (2002). *Ṣaájú Fágúnwà.* Ilorin: Department of Linguistics and Nigerian Langauges, University of Ilorin.

Ogunsina, B. (2006). *Sociology of the Yorùbá Novel: An Introdctuion.* Ilorin: Integrity publication.

Ogunsina, J.A. (1976). *The Development of the Yorùbá Novel. MPhil Dissertation.* University of Ibadan, Ibadan.

Òkédìjí, O. (1971). *Àjà ló lẹrù.* Ibadan: Longman (Nig) Ltd.

Olújìmí, B. (2017) *Ọ̀bàyẹ́jẹ́.* Ibadan: vantage publishers

## ÌPÍN KẸRIN ỌGBỌ́N ÌSỌ̀TÀN NÍNÚ ÌTÀN ÀRÒSỌ YORÙBÁ

**Àkòónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
   4.1 Ohun tí ọgbọ́n ìsọ̀tàn jẹ́
   4.2 Àwọn asọ̀tàn ìtàn àròsọ Yorùbá
   4.3 Oríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn nínú ìtàn àròsọ Yorùbá
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín kẹrin ní abẹ́ módù kẹta yìí ni ó ti máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí ó máa ń jẹyọ nínú ìtàn àròsọ Yorùbá. A ó ṣàlàyé kíkún nípa àwọn asọ̀tàn tí o lè bá pàdé nínú ìtàn àròsọ àti ọ̀kanòjọ̀kàn ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí òǹkọ̀tàn máa ń ṣàmúlò nínú ìtàn rẹ̀ kí o lè ṣe ìtẹ́wọ́gbà.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kẹrin yìí, o ó lè:

i. Ṣàlàyé kíkún nípa ọgbọ́n ìsọ̀tàn nínú ìtàn àròsọ Yorùbá
ii. Ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn asọ̀tàn tí òǹkọ̀wé lè yàn láàyò fún kíkọ ìtàn àròsọ rẹ̀
iii. Jírọ̀rò lórí oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí àwọn òǹsọ̀tàn máa ń ṣàmúlò nínú ìtàn wọn.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Kọ ìtàn kékeré kan kí ó sì rí í dájú pé o ṣàmúlò oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn
ii. Jírọ̀rò lórí asọ̀tàn tí o lò nínú ìtàn kékeré tí o kọ

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ohun tí ọgbọ́n ìsọ̀tàn jẹ́

Èyí ni oríṣìíríṣìí ọgbọ́n tàbí ète tí òǹkọ̀tàn máa ń dá láti rí i pé ìtàn tí oùn ń sọ kò tètè sú àwọn òǹkàwé tàbí olùgbọ́. Gbogbo ète tí òǹkọ̀tàn bá mọ̀ ni yóò lò láti mú ìfẹ́ àwọn ènìyàn láti gbọ́ tàbí ka ìtàn rẹ̀ dúró títí dé òpin. Bí òǹkọ̀tàn kò bá mọ́ ète láti lo àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí dáadáa ohun tí ó dájú

gbangba ni pé àwọn ènìyàn lè má nífẹ̀ẹ́ àtika ìtàn rẹ̀ tàbí láti tẹ etí sílẹ̀ láti gbọ́ ìtàn náà. Lọ́nà àtidènà èyí, oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn ni òǹkọ̀tàn tí ó bá pegedé yóò lò láti rí i pé ìtàn rẹ̀ kò di àkọ̀tì.

## 4.2 Àwọn Asọ̀tàn ìtàn Àròsọ Yorùbá

Ní kété ti òǹkọ̀tàn bá ti pinnu làti kọ ìtàn àròsọ rẹ̀ ni yóò ti máa ronú nípa irúfẹ́ asọ̀tàn tí yóò lò fún ìtàn rẹ̀. Oríṣìí asọ̀tàn méjì ló wà, èkínní ni asọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe, nígbà tí asọ̀tàn kejì jẹ́ asọ̀tàn arínúróde. Ọ̀kan lára àwọn asọ̀tàn yìí ni òǹkọ̀tàn lè yàn láàyò láti kọ ìtàn àròsọ rẹ̀. Òǹkọ̀tàn kò lè ṣe àmúlò asọ̀tàn méjèèjì lẹ́ẹ̀kan, ṣùgbọ́n ó lè ṣe àmúlùmálà asọ̀tàn méjèèjì nínú ìtàn kan soso. Àmúlùmálà asọ̀tàn méjèèjì yìí ni Fálétí se nínú ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin*, Ó fi ààyè gbà oríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ lásìkò kan náà ní ibi ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Bákan náà, ni ó dá ọgbọ́n láti mú kí àwọn asọ̀tàn ojú-mi-ló-se mẹ́tẹ̀ẹ̀ta pàdé nínú ẹ̀wọ̀n Olúmokò láti ròyìn tàbí sọ ìtàn ìrírí ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn láti ìgbà tí wọ́n ti pinya, Délànò náà tún ṣàmúlò asọ̀tàn ojú-mi-ló ṣe nínú ìtàn àròsọ rẹ̀, *Aiyé Daiye Òyìnbó*.

## 4.3 Oríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn nínú ìtàn Àròsọ Yorùbá

Ó yẹ kí o mọ̀ pé bí òǹkọ̀tàn bá ti yan asọ̀tàn ojú-mi-lóṣe láti sọ ìtàn rẹ̀, ó di dandan kí ó lo ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-lóṣe. Àmọ́, bí ó bá yan asọ̀tàn arínúróde, ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde náà ni yóò lò fún àgbékalẹ̀ ìtàn rẹ̀

### i. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn Ojú-mi-ló-ṣe

Èyí ni ọgbọ́n ìsọ̀tàn tó fààyè gba olú ẹ̀dá ìtàn láti sọ ìrírí rẹ̀ ọlọ́kàn-ò-jọ̀kan pẹ̀lú èdè ara rẹ̀, ìbáyému máa ń wà nínú ìtàn àròsọ tí a gbé kalẹ̀ pẹ̀lú ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe torí ẹni tó ní ìrírí ìṣẹ̀lẹ̀ náà ló ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀. Ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ ẹni kìnní tàbí ọ̀rọ̀ arọ́pò afarajórúkọ ẹni kínní ni òǹkọ̀tàn máa ń lò. Àpẹẹrẹ àwọn ìwé ìtàn àròsọ tí òǹkọ̀wé ti ṣàmúlò ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú mi-ló-ṣe ni *Lọ́jọ́ Ọjọ́un* àti *Ayé daíyé Òyìnbó* tí Isaac Délàno kọ, àpẹẹrẹ mìíràn tún ni ìtàn Àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin* ti Adébáyọ̀ Fálétí kọ. Bí ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe se ní àǹfààní, bẹ́ẹ̀ náà ni ó ni àléébù tirẹ̀. Àǹfààní àkọ́kọ́ tí ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí ní ni pé ó máa ń jẹ́ kí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn jẹ mọ́ òtítọ́. Èyí nìkan kọ́, ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-se kì í jẹ́ kí asọ̀tàn àti òǹkọ̀wé jìnnà síra wọn, ṣe ni ó máa ń mú àwọn méjèèjì súnmọ́ ara wọn. Àléébù pàtàkì tí ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí ní ni pé asọ̀tàn kò ní ìmọ̀ kíkún nínú gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àròsọ, torí kì í ṣe gbogbo ibi ìṣẹ̀lẹ̀ ló ni agbára láti wà. Irúfẹ́ àsìkò bẹ́ẹ̀ àyàfi tí àwọn tó ṣojú bá ròyìn irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ fún un, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ yóò pamọ́ fún un. Bákan náà, asọ̀tàn ojú-mi-ló-se kò lè mọ èrò inú ọkàn àwọn ẹ̀dá ìtàn yòókù àyàfi bí àwọn ẹ̀dá ìtàn bẹ́ẹ̀ bá sọ fún un. Asọ̀tan yìí kan náà kò lè sọ̀rọ̀ nípa ara rẹ̀ tó bí yóò ṣe ṣe ìròyìn nípa àwọn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn.

### ii. Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Arínúróde

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni èyí tí asọ̀tàn ti jẹ onigba ojú èyí tí ó fún un ni àǹfààni láti ṣe ọ̀fintótó nípa gbogbo nǹkan tí ó rọ̀ mọ́ ìtàn àròsọ tí ó ń sọ.

Ó hàn gbangba pé àwọn òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ Yorùbá púpọ̀ ló ṣàmúlò ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde nínú ìtàn àròsọ wọn. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ó fi ààyè sílẹ̀ fún wọn láti máa wo ọ̀tún, wo òsì. Ọ̀rọ̀ arópò ẹni kẹta ni asọ̀tàn arínúrode máa ń lò fún gbígbé ìtàn rẹ̀ kalẹ̀. Àǹfààní pàtàkì tí ó wà nínú ìṣàmúlò ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni pé asọ̀tàn mọ èrò ọkàn gbogbo ẹ̀dá ìtàn. Èyí sì túbọ̀ fún un ní àǹfààní láti mú ìtàn sọ bí ó ṣe wù ú láìni ìdíwọ́ rárá.

Yàtọ̀ sí ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde àti ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe, àwọn òǹkọ̀tan tún lè lo àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn mìíràn nínú ìtàn wọn lẹ́yìn tí wọ́n bá ti yan irúfẹ́ asọ̀tàn tí wọ́n fẹ́ tán.

Àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn yòókù tí òǹkọ̀tàn tún lè ṣàmúlò yàtọ̀ sí àwọn méjì tí a ti jíròrò lé lórí ṣaájú ni a ó máa sọ̀rọ̀ nípa wọn báyìí.

### iii. Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Àlá

Òǹkọ̀tàn lè lo àlá láti gbé lára ìtàn rẹ̀ kalẹ̀, ẹ̀dá ìtàn kan lè la àlá èyí tí ó jẹ́ ìtanilólobó nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń bọ̀ wá ṣẹlẹ̀ ní ọjọ́ iwájú. Bí irú àlá bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ èyí tí ó burú, dandan ni kí ìkóláyàsókè wà fún ẹ̀dá ìtàn bẹ́ẹ̀, èyí ti yóò sì mú un gbé ìgbésẹ̀ pé kí irú àlá búburú bẹ́ẹ̀ má wá sí ìmúṣẹ. Ẹ̀dá ìtàn mìíràn lè lá àlá kí ó sì fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú un, èyí tí ó lè wá kàbámọ̀ rẹ̀ ní ọjọ́ iwájú. Ohun tí òǹkọ̀tàn fẹ́ kí àwọn òǹkàwé rẹ̀ mọ̀ ní pe kì í ṣe gbogbo ìgbà ni àlá gọ̀, ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ wí pé àlá ń ṣe ìkìlọ̀ àti ìtọ́ni ni, èyí tí o sì fẹ́ àkíyèsí ẹni tí ó lá irúfẹ́ àlá bẹ́ẹ̀. Nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọlọ́un Lúgọ* tí Débọ̀ Awẹ́ kọ, Apánpá tí ó jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn la àlá èyí tí ó bà á lẹ́rù tí ó sì tẹ orí ọkàn rẹ̀ bá. Láti dènà àlá búburú yìí ni Apáńpá àti Monisọ́lá ìyàwó rẹ̀ ṣe gba ààwẹ̀ àti àdúrà ọlọ́jọ́ mẹ́rìnlá. Àlá tí a fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú lè padà yíni ní àgbo dànù.

### iv. Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn Onílẹ́tà

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà máa ń fún àwọn ẹ̀dá ìtàn tí kò sí ní ìtòsí ara wọn láti bá ara wọn sọ̀rọ̀ tàbí láti jẹ́ kí wọ́n mọ̀ nípa ohun kan tí ó ṣe pàtàkì. Fún àpẹẹrẹ, nínú ìtàn àròsọ *Àṣírí Amòòkùnjalè Tú*, tí Kọ́lá Akínlàdé kọ, Ọ̀kẹ́ mẹ́ta náírà pòórá nínú séèfù lẹ́yìn tí Orímóògùnjẹ́ kú, èyí ló mú kí Dúró tí í ṣe ọmọkùnrin Orímóògùnjẹ́ kọ lẹ́tà sí Akin Olúṣínà láti wá tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tó sókùnkùn, kí ó sì fi ojú amòòkùnjalè síta. Òǹkọ̀wé Akinlabí ṣe àmúlò ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà púpọ̀ nínú ìtàn àròsọ rẹ̀ *Àìsàn Ìfẹ́* àti *Ọmọ Ọlọ́jà Ìrọ̀lẹ́*. Ẹ̀ẹ̀mẹrin ni Délé kọ lẹ́tà sí Fúnkẹ́ pé kí o fojú fo àsìse òun dá ṣùgbọ́n ẹ̀ẹ̀kan soso tí Fúnkẹ́ dá èsì padà fún Délé jẹ́ láti sọ fún un pé àjọsepọ̀ kò lè wáyé láàrin àwọn mọ́. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà máa ń jẹ́ kí ẹni tí ó ń kọ lẹ́tà tú ọkàn rẹ̀ jáde láìsí ìdíwọ́ kankan bó ti wù kó mọ.

### v. Ìlò Àpèjúwe

Gbogbo ohun tí o wà ni àyíká àti ẹ̀dá ènìyàn ni òǹkọ̀tàn lè ṣe àpèjúwe rẹ̀. Àpèjúwe yìí lè wáyé nípa ìhùwàsí, ìṣesí tàbí ìrísí ẹ̀dá ìtàn. Láti lè ṣe àmúlò ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí, òǹsọ̀tàn gbọdọ̀ jẹ́ ọlọ́fintótó, tí ó máa ń ṣe àwòfín. Ní ìbẹ̀rẹ̀ ìwé ìtàn àròsọ "*Ọ̀bàyéjẹ́* tí Olújìnmí kọ ni ó ti ṣe àpèjúwe àwọn ará

ìlú Ìlọfẹ̀ gẹ́gẹ́ bí jayéjayé àti ẹni ti Ọlọ́run fún ní ilẹ̀ tí ó ń sàn fún wàrà àti oyin.

Àwọn ará abúlé Ìlọfẹ̀ fẹ́ràn fàájì dáadáa, ìlú Ọ̀kọ́
sì jẹ́ ibi kan tí wọ́n ti máa ń lọ ra ohun gbogbo tí
wọ́n bá fẹ́ nítorí ibẹ̀ ni ó tóbi jù ní agbègbè wọn.
Ní ìrọ̀lẹ́, ìdí ayò ni wọ́n ti máa ń ṣe fàájì nídìí igi
Ọdán ńlá kan báytìí tó wà láàrin abà. (Olújìnmi 2017:1)

Ọ̀kẹ́dìjí náà ṣe àpèjúwe ìran tí àwọn jangunjagun ti yìnbọn pa àwọn adigunjalè báyìí:

Wọ́n pa lọ́lọ́ ni bí ẹni pé ọ̀fọ̀ gbígbóná sẹ̀ wọn.
Ẹnikankan nínú wọn kò dún pínkín, ẹnì kan ko gbin.
Kẹ́kẹ́ pa mọ́ gbogbo wọn lẹ́nu ni. Bẹ́ẹ̀ sì ní ewée rúmọ́
ń yájú ni, pípọ̀ ọ̀hún pàpọ̀jù. Wọ́n ju ẹgbàágbèje lọ.
Ẹnìkọ̀ọ̀kan ń jákọ̀ kẹ̀hẹ́, kẹ̀hẹ́ nidàágbánídàágbá. Bó ṣe,
ẹlòmíràn a sáná si sìgá ọwọ́ rẹ̀ pẹ̀rẹ̀, á tì í bọnu, a máa
mu sìgá rẹ̀ lọ. Bó sì ṣe, ẹlòmíràn a mi kanlẹ̀ hìn-ìn bó tún
ṣe, ẹlòmíràn a gbin kìn (Ọ̀kédìji 2005:2)

Àpèjúwe máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tí o ba ṣókùnkùn tí yóò sì mọ́lẹ̀ kedere ni.

### vi. Ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́-ìran

Ní ìgbà tí òǹkọ̀tàn bá lo ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí ṣe ni o máa ń dàbí ẹni pé ó gbé ìran kalẹ̀. Àǹfààní máa ń wáyé nínú èyí tí òǹkọ̀tàn yóò fi ààyè gbà ìtakùrọ̀sọ nínú èyí tí òǹkàwé yóò máa fi ojú-inú wo ìsesí àti ìhùwàsí àwọn ẹ̀dá ìtàn akópa. Òǹkọ̀tàn lè gba ọ̀nà mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ láti ṣàmúlò ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́-ìran. Lákọ̀ọ́kọ́, ó lè ṣàmúlò ìgbékalẹ̀ ibi tí àwọn ẹ̀dá ìtàn ti ń tàkùrọ̀sọ tàbí ṣe ìròyìn. Ó lè lo ìròyìn láti lè jẹ́ kí òǹkàwé máa fi ojú inú wo ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ròyìn. Bákan náà ni òǹkọ̀tàn lè ṣe àfihàn àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àròsọ rẹ̀ bí wọn ṣe n tàkùrọ̀sọ. Àǹfààní pàtàkì tí ọgbọ́n ìṣọ̀tàn ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́-ìran ní ni pé ó máa ń dín àlàyé ti òǹkọ̀tàn ìbá ní láti ṣe kù.

### vii. Ìtàn nínú ìtàn

Nínú ọgbọ́n ìtàn nínú ìtàn ni òǹkọ̀tàn tí máa ń mú ìtàn mìíràn wọ inú ìtàn pàtó tí ó fẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ̀. Ẹni ti ó bá fẹ́ lo ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí gbọdọ̀ kíyèsára kí o sì rí i dájú pé àwọn ìtàn tí ó ń fi ṣe àlàfibọ̀ yìí ní í ṣe pẹ̀lú ìtàn tí o ti ń sọ bọ̀ tẹ́lẹ̀. Òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ tí ó jẹ́ gbajúgbajà nínú lílo ọgbọ́n ìtàn nínú ìtàn ní Fágúnwà jẹ́. Àìmoye ìtàn nínú ìtàn ni Fágúnwà mú wọ inú àwọn ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ máràárún. Ète ọgbọ́n ìtàn nínú ìtàn ni láti mú ẹ̀mí ìtàn gùn.

### viii. Ọgbọ́n Pípadàsẹ́yìn

Ní ìgbà tí òǹkọ̀wé bá fẹ́ ran àwọn òǹkàwé rẹ̀ léti nípa ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn tàbí tí ó bá fẹ́ tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tí ó ṣókùnkùn sí wọ́n ni ó máa ń lo

ọgbọ́n pípadàsẹ́yìn. Ọládẹ̀jọ Òkédìji nínú ìtàn àròsọ *Àjà ló lẹrù* lo ọgbọ́n pípadàsẹ́yìn ní ìgbà tí Tọ̀lání tí àwọn gbọ́mọgbọ́mọ gbé lọ padà fi ẹnu ara rẹ̀ ròyìn gbogbo ohun tí o sẹlẹ̀ sí i, lẹ́yìn tí wọ́n rí i.

**ix. Ìsọníṣókí**

Èyí ni ọgbọ́n tí òǹkọ̀tàn máa ń dá láti fi hàn léréfèé ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn, pàápàá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣe kókó sí ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàsókè ìtàn. Ìsọníṣókí bí orúkọ rẹ̀ jẹ́ ṣókí lọbẹ̀ oge. Ọ̀nà kan kò wọjà ni ọ̀rọ̀ ìsọníṣókí jẹ́, bí òǹkọ̀tàn bá fẹ́, o lè gbé ìsọníṣókí rẹ̀ jáde lórí tẹlifísàn, rédíò tàbí ìwé ìròyìn. Ọ̀kanòjọ̀kan ìsọníṣókí ni Òkédìjí ṣàmúlò nínú àwọn ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, *Àjà ló lẹrù, Àgbàlagbà ikàn àti Ká rìn ká pọ̀.*

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín kẹrin yìí a ti kọ́ pé:

- Gbogbo ọgbọ́n ìmọ̀ àti ète tí òǹkọ̀tàn máa ń ta láti rí i pé ìtàn òun kò tètè su àwọn òǹkàwé tàbí olùgbọ́ rẹ̀ ni a mọ̀ sí ọgbọ́n ìsọ̀tàn
- Asọ̀tàn méjì tí a lè bá pàdé nínú ìtàn àròsọ Yorùbá ni asọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe àti arínúróde.
- Asọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe kò mọ èrò àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ṣùgbọ́n onígba ojú ni asọ̀tàn arínúróde
- Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni ọ̀pọ̀ òǹkọ̀tàn gùnlé torí wọ́n ni àǹfààní láti mú ìtàn sọ bí ó ṣe wù wọ́n.
- Àwọn oríṣìíríṣìí ọgbọ́n ìsọ̀tàn mìíràn tí òǹkọ̀tàn tún lè ṣàmúlò ni ọgbọ́n ìsọ̀tàn àlá, ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà, ìlò àpèjúwe, ìgbékalẹ̀ ajẹrmọ̀ ìran, ìtàn nínú ìtàn, ọgbọ́n pípadàsẹ́yìn àti ìsọnísókí

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Jíròrò lórí ohun tí ọgbọ́n ìsọ̀tàn jẹ́
2. Sọ̀rọ̀ rẹpẹtẹ lórí àwọn asọ̀tàn tí òǹkọ̀tàn lè yan láàyò
3. Pàálà láàrin asọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe àti asọ̀tàn arínúróde.
4. Ṣe àgbéyẹ̀wò onírúurú ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí òǹkọ̀tàn máa ń lò nínú ìtàn àròsọ rẹ̀

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Awẹ, D. (1991). *Ọlọ́un lúgọ*. Ilesa: JỌlá publishing co. Ltd.

Delano, I.O. (1966). *Lọ́jọ́ Ọjọ́un.* London: Thomas Nelso & Sons Ltd.

Delano, I.O. (2005). *Atótó Arére*. Ibadan: University Press PLC.

Fágúnwà D.O. (1973). *Igbó Olódùmarè.* Lagos: Thomas Nelson (Nig) Ltd.

Fágúnwà, D.O. (1967). *Ògbójú ọdẹ Nínú Igbó Irúnmalẹ̀*. Thomas Nelson Sons.

Fágúnwà, D.O. (1968) *Ìrèké Oníbùdó.* London: Thomas Nelson & Sons Ltd.

Fágúnwà, D.O. (1970). *Àdìtú Olódùmarè.* Lagos: Thomas Nelson (Nig) Ltd.

Fálétí, A. (1969̣) *Ọmọ Olókùn Ẹsin*. London: University of London Press Ltd.

Olújìnmí, B. (2017) *Ọ̀bàyẹ́jẹ́.* Ibadan: Vantage Publishers.

## ÌPÍN KARÙN-ÚN ÀGBÉYẸ̀WÒ ÀSÀYÀN ÌWÉ ÌTÀN ÀRÒSỌ YORÙBÁ

**Àkòónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
   4.1 Ìtàn Àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin
   4.2 Ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́
   4.3 Ìtàn àròsọ Àjà ló lẹrù
   4.4 Ìtàn àròsọ Èmi Ṣẹ̀gilọ́lá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Nínú ìpín karùn-ún ní abẹ́ módù kẹta yìí ni ó ti máa kẹ́kọ̀ọ́ nípa àwọn ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá mẹ́rin. Àwọn ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí a ó máa ṣàlàyé kíkún nípa wọn ni *Ọmọ Olókùn Ẹsin, Ọ̀bàyéjẹ́, Àjà ló lẹrù, àti Èmi Ṣẹ̀gilọ́lá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́.* Gbogbo àwọn ohun tí a ti jíròrò lé lóri ṣaáju lábẹ́ ìtàn àròsọ Yorùbá bí àhunpọ̀ ìtàn àti ọgbọ́n ìsọ̀tàn ni a o gbé yẹ̀wò bí a ṣe ń ṣe àtúpalẹ̀ tó lóòrìn fún àwọn ìwé àròsọ Yorùbá mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí a yàn láàyò fún ìtúpalẹ̀.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín karùn-ún yìí, ó lè:

- Ṣe ìtúpalẹ̀ fún onírúurú ìtàn àròsọ Yorùbá
- Ṣe iṣẹ́ lámèétọ̀ tó múnádóko fún ìtàn àròsọ Yorùbá

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

i. Dárúkọ àwọn ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá mẹ́ta àti ohun tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn dá lé lórí
ii. Ṣe àtúpalẹ̀ fún ìtàn àròsọ kan tí o ti kà rí

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìtàn Àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin: Adébáyọ̀ Fálétí

**Kókó**

Kokó kan pàtàkì tí ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin dálé ni òmìnira. Àwọn ará Òkè Ògùn ti wà lábẹ́ ìsìnrú Òkò fún ìgbà pípẹ́, ọdọọdún ni àwọn ará

Òkè Ògùn máa n rú àsìngbà lọ sí Òkò. Wọ́n yóò pa bẹẹrẹ ti ọba yóò fi kọ́ ilé, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò ru ẹran ti Ọba yóò fi ṣe ọdún lọ sí Òkò, Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin pàápàá kò gbẹ́yìn nínú ríru àsìngbà lọ sí Òkò lọ́dọọdún. Àwọn ara Òkè Ògùn kò sí rí ohun tí ó buru nínú àsìngbà tí wọ́n n sìn yìí, wọ́n ń ṣe é tayọ̀tayọ̀ láìsí ìkùnsínú. Ní ọjọ́ kan, Ọmọ Olókùn ẹsin ronú, ó sì kórìíra ipò ti àwọn ènìyàn rẹ̀ tí í ṣe ara Òkè Ògùn wà yìí, ó si pinnu láti sọ àwọn ènìyàn rẹ̀ di òmìnira.

Mo kórìíra àìlómìnira, mo kórìíra ìdènígbèkùn, n kò sì fẹ́ kí á máa sin àwọn ará Òkò mọ́ (o.i. 4)

N kò fé kí orílẹ̀-èdè wa sin Òkò mọ́. Bí orílẹ̀-èdè wa kòbá sì gbà nígbà náà, n kò fẹ́ ki ilè tiwa lọ́wọ́ nínú àsìngbà mọ́. Èmi kò ní sìn ín mọ́ ni tèmi (o.i 4)

Àyọ́lò òkè yìí fi hàn gbangba pe Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin fúnrarẹ̀ ló pinnu pé òun àti àwọn ènìyàn Òkè Ògùn kò ni sín Òkò mọ́. Àjàyí nínú àyolò òkè yìí ti pinnu láti ja ìjà òmìnira náà yálà ó ri atilẹyìn àwọn ènìyàn rẹ tàbí kò rí.

Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ wàhálà àti ìgbìyànjú, Àjàyí rí àtìlẹyìn Ìbíwùmí ọmọ Ọba Òtu àti Àyọwí ara Ìgbòho, àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí sì jà fitafita. Níkẹ̀yìn, àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta borí wọ́n sì gbà òmìnira fún àwọn ará Òkè Ògùn.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Apá mẹ́ta ni Fálétí pín ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin* sí. Apá kìnní ni Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin tí bá Rótì ẹrú Ọba ja ni oko bẹẹrẹ. Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin ṣàlàyé ohun tí ó fi bá Róti jà torí Ó fẹ kí ó yé àwọn ònkàwé rẹ̀ pe òun kórìíra ìdènígbèkùn àti àìlómìnirà. Wọn mú Ọmọ Olókùn Ẹsin tọ Baálẹ̀ lọ, wọ́n sì fi sí àtìmọ́lé, inú àtìmọ́lé ti Àjàyí wà tó ti fi òye òmìnira yé Ìbíwùmí, Ìbíwùmí ọmọ Baálẹ̀ Òtu yìí ló tú Àjàyí sílẹ̀ ni àtìmọ́lé èyí ló fún un ni àǹfààní láti lọ sọ ọ̀rọ̀ òmìnira fún àwọn ọ̀ré rẹ̀ Àyọ̀wí ara Ìgbòho, Ṣàngódèyí ni Ìràwọ̀ àti Ọ̀súnjùmọ̀bí ní Baba-Ọdẹ. Ọwọ́ pàpà tẹ Ọmọ Olókùn ẹsin, wọn sì fi ránṣẹ́ si ilé Olósì ni Òkò.

Apá kejì ni Ìbíwùmí ọmọ Baálẹ̀ Òtu ti sọ ọ̀kanòjọ̀kan wàhálà àti ìdààmú tí ó dé bá a lẹ́yìn tí ó tú Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin sílẹ̀ ní ìgbèkùn bàbá rẹ̀. Àwọn ààrẹ wá láti Òkò wọ́n sì fi Ìbíwùmí ránṣẹ́ sí ilé Ìyálóde. Ìbíwùmí bèèrè fún ogún ìní rẹ̀ lọ́wọ́ bàbá rẹ̀, ó sì fi ra àwọn kan lára àwọn ẹrú bàbá rẹ̀ pẹ̀lú àrọwà fún àwọn ẹrú náà láti ṣiṣẹ́ kí wọ́n sì ra àwọn ẹrú mìíràn kúrò lóko ẹrú. Níkẹyìn, wọ́n fi Ìbíwùmí náà ránṣẹ́ sí Òkò.

Apá kẹta ni Àyọ̀wí ti ṣàlàyé bí ó ṣe lọ sí Ìgbẹ́tì láti bá Kọ́lájọ sọ̀rọ̀ òmìnira, Àyọ̀wí bá Lágboókùn ọmọ Olúmokò jà nítorí ó fẹ́ gbésẹ̀ lé Arinládé oníjó. Ìjà yìí pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ ṣùgbọ́n níkẹyìn wọ́n fi Àyọ̀wí àti Kọ́lápọ̀ ránṣẹ́ sí Òkò.

Ìparí apá kìnní ni ààfin Olúmokò tí jó ti Kọ̀lápọ̀ sì ti dágbére fáyé. Ìjà ńlá ṣẹlẹ̀ ni ìdí Àràbà nígbà ti Ọmọ Olókùn Ẹsin lọ láti gba bàbá rẹ̀ sílẹ̀. Ìbíwùmí dákú nígbà tí wọ́n fẹ́ pa wọ́n. Ọbákáyéjá bẹ Ìbíwùmí wo, ó ṣàlàyé bí òun ṣe ra ọ̀pọ̀ ẹrú kúrò ni ìgbèkùn, inú Àjàyí àti Ìbíwùmí sì dùn. Ọjọ́ ikú pé fún Ọmọ Olókùn Ẹsin àti àwọn yòókù rẹ̀ ṣùgbọ́n Ọbákáyéjá àti àwọn ará Òkè-Ògùn yòókù gba Ọmọ Olókùn Ẹsin àti àwọn ará rẹ̀ sílẹ̀ lọ́wọ́ Olúmokò. Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ wàhálà, ìfaradà àti ìyà àwọn ará Òkè-Ògùn gba òmìnira kúrò lábẹ́ ìsìnrú Òkò.

**Ìbùdó Ìtàn**

Ilẹ̀ Yorùbá ni agbègbè Òkè-Ògùn ni ibùdó gbogbogbòò ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin*. Ìlú Òtu àti Òkò ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn náà ti ṣẹlẹ̀. Àwọn ìlú mìíràn ti òǹkọ̀wé tún dárúkọ nínú *Ọmọ Olókùn Ẹsin* ni Ìgbòho, Baba-Ọdẹ, Ìgbẹ́tì, Ìràwọ̀, Tedé, Agúnrege àti Àgọ́-Àrẹ.

Àwọn ibi ti onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ ti wáyé ni pàtó nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin* ni Òkò Bẹẹrẹ, Ilé Baálẹ̀ Òtu, Ilé Olókùn Ẹsin, Ilé Àyọ̀wí, Ààrin Ọjà Ìgbòho, Òde Baálẹ̀, Ìgbẹ́tì, Òde Baálẹ̀ Baba-ọdẹ, Ilé Olósì, Ilé Ìyálóde àti Nárì babalórìṣà.

**Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn**

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe ni Fálétí lò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin. Ọ̀nà àrà ni Fálétí gbà lo ọgbọ́n ìsọ̀tàn yìí, asọ̀tàn mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Fálétí fi ọ̀rọ̀ sí lẹ́nu.

Ìjà Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin ní ó bẹ̀rẹ̀ ìtàn, èyí ló mú Àjàyí ṣàlàyé ohun tí ó fà á tí ó fi bá Róti ẹrú Baálẹ̀ jà, baálẹ̀ fi Àjàyí sí àtìmọ́lé. Inú àtìmọ́lé yìí ni Àjàyí ti fi òye òmìnira yé Ìbíwùmí ọmọ Baálẹ̀ Òtu. Ìrànlọ́wọ́ tí Ìbíwùmí ṣe fún Àjàyí nípa títú u sílẹ̀ kó ìjàngbọ̀n bá Ìbíwùmí èyí sì jẹ́ kí ó ni ìtàn tirẹ̀ láti sọ. Lẹ́yìn tí Ìbíwùmí ti tú Àjàyí sílẹ̀, Àjàyí lọ sí Ìgbòho lọ́dọ̀ ọ̀rẹ́ rẹ̀ Àyọ̀wí láti jẹ́ kí ó darapọ̀ mọ ìjà òmìnira, wọ́n pinnú láti lọ sí ẹlẹ́kùnjẹkùn láti kéde òmìnira èyí náà ló sì mú Àyọ̀wí ni ìtàn ìrírí tirẹ̀ náà láti sọ.

Oríṣìíríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ ló ṣẹlẹ̀ ní àkókò kan náà ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ibi. Fún àwọn asọ̀tàn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí, Àjàyí, Ìbíwùmí àti Àyọ̀wí láti lè fi ẹnu ara wọn sọ ìtàn ìrírí wọn, ìṣẹ̀lẹ̀ fi ipá mú wọn láti pàdé ni ẹ̀wọ̀n Olúmokò.

Fálétí ṣe àmúlò asọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe mẹ́ta nínú *Ọmọ Olókùn Ẹsin* ṣùgbọ́n a ó rí i pé ìlépa ìtàn àròsọ náà kò yípadà torí àwọn asọ̀tàn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ni èrò kan, ìgbàgbọ́ kan àti ìpinnu kan. Àwọn aninilára ni àwọn asọ̀tàn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta dojú ìjà kọ, Àjàyí, Ọmọ Olókùn Ẹsin bá Rótì jà, Ìbíwùmí bá Ìyálóde jà nígbà tí Àyọ̀wí bá Lágboókùn Ọmọ ọba jà.

Àwọn ọgbọ́n isọ̀tàn mìíràn ti Fálétí tún ṣe àmúlò wọn ni àpèjúwe àti ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́-ìran. Àpèjúwe (o.i 1, 8, 11, 119). Ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́-ìran wáyé (o.i 21, 163 àti 99).

**Ìfiwàwẹ̀dá**

Mẹ́fà lára àwọn ẹ̀dá ìtàn inú ìwé ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹsin* ni a ó máa sọ̀rọ̀ nípa wọn. Àwọn ẹ̀dá ìtàn yìí ni Àjàyí, Ìbíwùmí, Àyọ̀wí, Olúmokò, Baálẹ̀ Òtu àti Olóyè Olókùn Ẹsin.

Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó kópa nínú ìtàn Ọmọ Olókùn Ẹsin jẹ́ ènìyàn àwùjọ Yorùbá sì ni wọn ń gbé. Orúkọ àmútọ̀runwa, oyè àti àbísọ ni Fálétí fún àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀.

**Àjàyí**

Àjàyí ní olú ẹ̀dá ìtàn *Ọmọ Olókùn Ẹsin, o*rúkọ oyè tí wọ́n fi bàbá Àjàyí jẹ ní Òtu ni Olókùn Ẹsin. Ìdí nìyí tí àwọn ènìyàn fi máa n pe Àjàyí ni Ọmọ Olókùn Ẹsin. Àwọn ará Òkè-Ògùn ti wà lábẹ́ ìsìnrú Òkò fún ìgbà pípẹ́ tí wọn kò sì ri ohun kan tí ó burú nipa èyí, Àjàyí ọmọ Olókùn Ẹsin gẹ́gẹ́ bi ẹnìkan pinnu láti gba àwọn ènìyàn rẹ kúrò lábẹ́ ìsìnrú Òkò. Ọ̀rọ̀ òmìnira kò tètè yé àwọn ará ìlú Òtu àti Òkè-Ògùn lápapọ̀ wọ́n sì rò pé orí Ọmọ Olókùn Ẹsin ti dàrú ni.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn Òkè-Ògùn kò faramọ́ ọ̀rọ̀ òmìnira ti Àjàyí ń sọ ní ìbẹ̀rẹ̀ ṣùgbọ́n Àjàyí jẹ ẹ̀dá ìtàn tí ó ní ìpinnu. Nítorí náà, o làkàkà láti jèrè Ìbíwùmí ọmọ baálẹ̀ Òtu àti Àyọ̀wí ará Ìgbòho sí ọ̀dọ̀ ara rẹ̀. Pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Ìbíwùmí àti Àyọ̀wí, èròǹgbà Àjàyí ọmọ Olókùn Ẹsin wá sí ìmúṣẹ, àwọn ará Òkè Ògùn di òmìnira pátápátá kúrò lábẹ́ ìsìnrú Òkò.

Àjàyí ọmọ Olókùn Ẹsin jẹ́ ẹ̀dá ìtàn tó ní ìfarádà àti akitiyan, èyí ló sì jẹ́ kí òmìnira tí o n fẹ́ fún àwọn ènìyàn rẹ̀ láti Òkè Ògùn tẹ̀ wọ́n lọ́wọ́.

**Ìbíwùmí**

Ìbíwùmí jẹ ọmọbìnrin baálẹ̀ Òtu, lákọ̀ọ́kọ́ ọ̀rọ̀ òmìnira kò yé Ìbíwùmí, ó sì ń fi Àjàyí ṣe yẹ̀yẹ́. Ṣùgbọ́n lẹ́yìn ti Àjàyí farabalẹ̀ ṣe àlàyé ohun tí òmìnira jẹ́ fún Ìbíwùmí, ó tilẹ̀ jẹ́ pé bàbá rẹ ni ó fi Àjàyí sí àtìmọ́lé, kò rò ó lẹ́ẹ̀mejì tí ó fi tú Àjàyí sílẹ̀ láti sá àsálà fún èmi rẹ̀.

Títúsílẹ̀ ti Ìbíwùmí tú Àjàyí sílẹ̀ tí ó sì tún fi ẹnu ara rẹ sọ pé òun ni ó tu Àjàyí sílẹ̀ dá wáhálà ńlá sílẹ̀ láàárín Ìbíwùmí àti bàbá rẹ. Bàbá Ìbíwùmí tilẹ̀ lé ìyá Ìbíwùmí jáde níle nítorí ìwà Ìbíwùmí yìí. Wọ́n ti Ìbíwùmí mọ́lé dípò Àjàyí, baálẹ̀ kọ Ìbíwùmí lọ́mọ, ó sì pàsẹ kí wọ́n mú un lọ sí ilé Ìyálóde.

Akíkanjú ẹ̀dá ìtàn ni Ìbíwùmí jẹ́. Ó bèèrè ogún ìní rẹ̀ lọ́wọ́ bàbá rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni owó tí ó ri nínú àwọn ogún yìí ni ó fi rà òmìnira fún àwọn kan lára ẹrù

bàbá rẹ̀. Ìbíwùmí pàdé ọmọ Olókùn Ẹsin ni ẹ̀wọ̀n Olúmokò. Dídákú ti Ìbíwùmí dákú ni Nárì Babalóríṣà ló kó àwọn Àjàyí àti Ìbíwùmí yọ.

Àwọn ẹrú ti Ìbíwùmí ra òmìnira fún lọ́dọ̀ bàbá rẹ̀, ló padà gbà Ìbíwùmí àti àwọn yòókù rẹ̀ sílẹ̀ lọ́wọ́ ikú, tí wọ́n sì gba òmìnira fún àwọn ènìyàn Òkè Ògùn, Ìbíwùmí àti Àjàyí padà di tọkọtaya nígbẹ̀yìn.

**Àyọ̀wí**
Ará Ìgbòho ni Àyọ̀wí, ọ̀rẹ́ ìgbà èwe Àjàyí Ọmọ Olókùn ẹsin sì ní pẹ̀lú, Àjàyí lọ bá Àyọ̀wí, ó sì bèèrè fún ìrànlọ́wọ́ àti àtìlẹyìn Àyọ̀wí nínú ìjà òmìnira tí ó ti bẹ̀rẹ̀, Àyọ̀wí gbà láti darapọ̀ mọ Àjàyí, ó sì gbéra láti lọ sí Ìgbẹ́tì lọ́dọ̀ Kọ́lájọ̀ láti lọ fi ọ̀rọ̀ òmìnira yìí tó o létí.

Ìwà àìbìkítà Lágboókùn àti ayé fàmílétè ń tutọ́ tí ó ń jẹ́ nípa gbígbẹ́sẹ̀ lé Arinládé Alájòótà bí Àyọ̀wí nínú, èyí ló sì da ìjà ńlá sílẹ̀ ni òde baálẹ̀ Ìgbẹ́tì, Àyọ̀wí jẹ́ ẹ̀dá ìtàn tí ó kórìíra ìrẹ́jẹ. Ìpinnu rẹ̀ láti gba Arinládé sílẹ̀ lọ́wọ́ ọmọ ọba Lágboókùn ló gbé e de ẹ̀wọ̀n Olúmokò.

**Olúmokò**
Ọba ìlú Òkò ní a mọ̀ sí Olúmokò. Ọ̀dọ̀ Olúmokò ni àwọn ará Òkè Ògùn máa n ru bẹẹrẹ àti ẹran ìgbẹ́ lọ lọ́dọọdún. Olúmokò ni ó pàṣẹ pé kí wọ́n yọ Olóyè Olókùn Ẹsin lóyè fún ìwà àfojúdi ti ọmọ rẹ̀ Àjàyí hù. Olúmokò jẹ́ olórí tí ó jẹ́ aninílára àti ọ̀kánjúà. Ẹ̀wọ̀n Olúmokò ni àwọn asọ̀tàn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ti pàdé. Níkẹyìn agbára bọ́ lọ́wọ́ Olúmokò, àwọn ará Òkè Ògùn sì ṣe ìlérí láti máa fún Olúmokò ni àádọ́ta ọ̀kẹ́ lọ́dọọdún.

**Baálẹ̀ Òtu**
Bàbá Ìbíwùmí ni baálẹ̀ Òtu jẹ́. Abẹ́ àṣẹ Olúmokò ni baálẹ̀ Òtu wà. Gbogbo àṣẹ Olúmokò ni baálẹ̀ Òtu máa ń múṣẹ, ó sì tún máa ń rí i pé àwọn Òkè Ògùn pàápàá kò fọwọ́ pa idà Olúmokò lójú. Baálẹ̀ gbà láti kú ju kí o má mú àṣẹ Olúmokò ṣẹ. Baálẹ̀ Òtu kọ Ìbíwùmí lọ́mọ, ó sì tún fi Ìbíwùmí yìí kan náà ránṣẹ́ sí Olúmokò fún ìjìyà tí ó tọ́.

Baálẹ̀ Òtu bẹ̀rù Olúmokò, kò sì sí ohun tí kò lè ṣe láti mu àṣẹ Olúmokò ṣẹ. Nígbà tí ìjà òmìnira ń lọ lọ́wọ́, Olúmokò bèèrè lọ́wọ́ baálẹ̀ Òtu ihá ẹni tí ó wà, ó sì dáhùn pé ìhà Olúmokò ni. Ṣùgbọ́n nígbà tí àwọn Òkè Ògùn gba òmìnira inú baálẹ̀ Òtu dùn pé òun náà ti di òmìnira. Baálẹ̀ Òtu jẹ́ ojo, ìbẹ̀rù àti àṣẹ ìgbà láéláé tí wọn ti pá ni kò fẹ́ yà kúrò nínú rẹ̀

**Olóyè Olókùn Ẹsin**
Bàbá Àjàyí tí ó bẹ̀rẹ̀ ìjà òmìnira ni Olóyè Olókùn Ẹsin jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí Olóyè àti alàgbà bàbá Àjàyí kò faramọ́ ìjà òmìnira tí ọmọ rẹ̀ bẹ̀rẹ̀. Gbígbà tí wọ́n gba Àjàyí lọ lọ́wọ́ bàbá rẹ tí wọ́n sì tí í mọ́lé si Òkò ló mú un pinnu láti má lọ sí ìpàdé àwọn Olóyè mọ́.

Nígbà tí wọ́n ń gbé Ìbíwùmí lọ sí òkò láti rọ́pò Àjàyí. Bàbá Àjàyí lọ ba sí bùba láti gba Ìbíwùmí sílẹ̀ ṣùgbọ́n ọwọ́ tẹ Olóyè Olókùn ẹsin, wọ́n sì tì í mọ́lé.

A rí Olóyè Olókùn Ẹṣin gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn tó ní ẹ̀rí-ọkàn. Kò ká òfin Olúmokò sí ohunkóhun. Ó làkàkà láti gbà Ìbíwùmí sílẹ̀ nítorí ó gbàgbọ́ pé ko yẹ ki olóore kú sí ipò ìkà. Onínurere ènìyàn ni Olóyè Olókùn Ẹṣin.

**Ìlò èdè**

Ìlò èdè Fálétí nínú ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹṣin fi hàn gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé tí ó dángájíá, tí ó sì ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa àṣà àti ìṣe Yorùbá.
Àwọn ọnà èdè tí Fálétí ṣàmúlò ni àfiwé, ọ̀rọ̀ àtijọ́, àkànlò èdè àti òwe.

**Ạ̀fiwé**

Ọ̀nà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Fálétí gbà lo àfiwé nínú ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹṣin, bí ó ti ṣe àmúlọ̀ àfiwé alápẹẹrẹ náà ló tún lo àfiwé alápèjúwe.

**Àfiwé alápẹẹrẹ**

Ní ìgbà ti Fálétí ba ṣe àmúlò àfiwé alápẹẹrẹ, yóò fi àwọn ohun méjì wéra láìṣe àlàyé. Díẹ̀ lára àfiwé alápẹẹrẹ bí Fálétí ṣe lò wọ́n nínú ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹṣin* nìyí:

> Níbití mo ti n sún kiri bí Olundu (o.i 19)
> Nígbàmíì, a jó wọlé̩ bí ọ̀rèbè, a fi ẹ̀hìn jó bí Ẹiyẹbà (o.i 109)
> Nwọ́n pọ̀ bí ewé rúmọ̀ (o.i 116)

**Àfiwé alálàyé**

Ní àkókò tí Fálétí bá lo àfiwé tí kò ṣe bẹ́ẹ̀ gbajúmọ̀ yóò ṣe àlàyé láti lè jẹ́ kí ohun tí ó ń sọ yé àwọn òǹkàwé rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:
Báyìí ni a túká ní ilé Baálẹ̀, tí a n jà ràn-ìn lọ̩ bi
ìgbà ti ènìytàn fi ẹṣẹ̀ tú ọwọ́ ìkamùdù (o.i 12)

Péú ni èmi pàápàá kuku n wò ni tèmi, bí èkúté tí a fi sí
àárín ọ̀pọ̀ ènìyàn ní ọ̀sán gangan (o.i 8)

**Ọ̀rọ̀ àtijọ́**

Ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹṣin* dálé ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ ayé àtijọ́. Ìdí èyí ni Fálétí ṣe lo àwọn ọ̀rọ̀ àtijọ́ tí ó yẹ nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọmọ Olókùn Ẹṣin*. Fálétí mọ̀-ọ́n-mọ̀ lo àwọn ọ̀rọ̀ àtijọ́ yìí ni láti tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn ìgbé ayé kán tí àwọn ènìyàn ti gbé ní ìgbà àtijọ. Àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ àtijọ́ tí ó jẹ jáde nínú Olókùn Ẹṣin ló wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

| | | |
|---|---|---|
| Òkúnà (o.i 31), | ìsáná lẹ̀ù | (o.i 42) |
| Pọnga (o.i 64), | ojú àbátá | (o.i 67) |
| Gbájù (o.i 121), | màjàlà, (o.i 121) bàárú o. 122) | |

**Àkànlò èdè**
Fálétí ṣe àmúlò èdè púpọ̀ nínú *Ọmọ Olókùn Ẹṣin*, èyí sì fi hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ ọ̀dọ̀ agba tí ó gbọ́ ìjìnlẹ̀ Yorùbá. Àkànlò èdè tí Fálétí ṣàmúlò yìí jẹ́ ki ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹṣin mú òǹkàwé lọ́kàn bẹ́ẹ̀ ni kò jẹ́ ki ìtàn rí sákálá.

Fún àpẹẹrẹ:
Mu ọ̀gẹ̀dẹ̀ nínú ọ̀ṣọ́ (o.i 4)
Ẹnu ni a fi n họ́ra (o.i 4)
Dawọtẹlẹ (o.i 5)

**Òwe**
Fálétí lo òwe lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹṣin. Fálétí fi òwe gbé àwọn èrò ìjìnlẹ̀ kalẹ̀ láti jẹ́ kí àwọn òǹkàwé ronú jinlẹ̀ lórí ohun tí ó ń sọ èyí sì jẹ́ ki àwọn èdè ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹṣin wuyì, tó sì dùn láti ka. Díẹ̀ lára àwọn òwe inú ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹṣin ni ìwọ̀nyí:

A kì í wí pé ọmọ ti yóò bá hun eyín ganganran kíó má hù ú,
nígbà tí ó bá hù ú tí kò ri ètè fi bò ó ni yóò tó mọ̀ wí pé kò dára (o.i 8)
Ẹni tó ní ki ará ilé òun máa lọ́wó, ará òde ní yá Olúwa rẹ̀ ní ìwọ̀fà (o.i 11)
Inú ni idà komsó n gbé (o.i 12)
Ọmọ osè níí ko kùmọ̀ ba ìyá rẹ̀ (.o 13)

## 4.2 Ìtàn Àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́: Bùnmi Olújìnmí

**Kókó**
Àwọn kókó tí ó jẹyọ nínú ìwé ìtàn àròsọ Ọ̀bàyejẹ́ ni ogun ilé ayé, ìbáwí òbí àti pàtàkì ẹ̀kọ́ ìwé.

**Ogun Ilé Ayé**
Àjàdí tí ó ti fi ìgbà kan jẹ́ olówó ti gbogbo ènìyàn n wárí fún ṣùgbọ́n nipasẹ̀ àìkíyèsára ó padà di olòsì. Àdìká tí ó jẹ́ ìyàwó rẹ̀ kò fi Àjàdí lọ́kàn balẹ̀ rárá nítorí àìlówó lọ́wọ́ rẹ̀. Àdánwò ńlá ni àìlówó lọ́wọ́ Àjàdí jẹ́ fún un. Ìyàwó rẹ̀ ló n bọ́ ọ, tí ó sì tún n fún un lówó ọtí. Ìdí èyí ni Àdìká kò fi jẹ́ ki ọkọ rẹ̀ ni ẹnu ọ̀rọ̀ mọ gẹ́gẹ́ bí ọkọ, ogun ayé tí ó n ba Àjàdí fínra yìí kò jẹ́ kí inú rẹ̀ dùn nítorí pé o ti di ẹlẹ́yà láàrin ọ̀rẹ́ àti ojúlùmọ̀.

Pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Adégún ìbátan Àjàdí, ó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ aṣánko ní ìlú Ọ̀kọ́ ni ilé-iṣẹ́ atúnlùútò. Kínyọ̀ ọ̀gá ilé-iṣẹ́ náà fẹ́ràn Àjàdí, ó sì mú un gẹ́gẹ́ bíi bàbá, o sì la ọ̀nà tí wọ́n fi sọ Àjàdí di ìránṣẹ ni ọ́fíìsì rẹ̀. Gbogbo àwọn òsìṣẹ́ ibi ti Àjàdí ti ń ṣiṣẹ́ kórìírà rẹ torí kì í tú àṣírí ilé iṣẹ́ fún wọn, àwọn olóyè ìlú Ọ̀kọ́ jà fitafita pé kí Akínwálé ọmọ Àjàdí má le lọ sí òkè òkun nípa ìrànwọ́ ìlú ṣùgbọ́n gbogbo ìlàkàkà àwọn olóyè yií, pàbó ló jásí. Ìbínú ti ọmọ Àjàdí, Akínwálé, tó lọ sí òkè òkun lo jẹ́ ki ọ̀kan lára àwọn olóyè dárúkọ rẹ̀ fún ìdádúró lẹ́nu iṣẹ́

Ogún ayé tó dojúkọ Àjàdí ko fi lọ́rùn sílẹ̀ àfi ìgbà tí ó tì í wọ kòtò. Akínwálé ọmọ Àjàdí tó lọ sí òkè òkun kò padà de bá a nítorí pé Àjàdí pàdánù ẹ̀mí rẹ̀ nínú ìjàmbá ọkọ̀. Àjàdí ṣiṣẹ́ sílẹ̀ ṣùgbọ́n kò dúró jẹ́ ẹ́, ogún ni ilé ayé, ilé ayé, ogun ni.

**Ìbáwí Òbí**

Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé "Ọmọ tí a kò tọ́ ni yóò gbé ilé tí a kọ́ tà, bó dọ̀la" àti pé "kékeré lá ti í pẹ̀kan ìrókò, nítorí tó bá dàgbà tán, apá kò ní í ká a. Fún ìdí èyí, àwọn Yorùbá kì í fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mu ìbáwí àwọn ọmọ wọn.

Àjàdí jẹ́ àgbẹ̀ aládàá ńlá ní ìlú Ìlọ́fẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ò rí tajé ṣe. Ìgbà ayẹyẹ òkú bàbá rẹ̀ ló bẹ̀rẹ̀ ọtí àti tábà mímu ṣùgbọ́n tí ìyá rẹ̀ kọ̀ láti dá a lẹ́kun tàbí tọ́ ọ sọ́nà pé ọtí àti tábà mímú kò dára. Kíkọ̀ ti ìyá Àjàdí kọ̀ láti dá ọmọ rẹ̀ lẹ́kun tábà àti ọtí mímu ló ba ayé Àjàdí jẹ́, àjókù tábà tí Àjàdí jù sí inú pápá ló lọ sí inú oko èyí tí ó sì jó gbogbo oko pátápátá, èyí ló si padà sọ Àjàdí di olòsì.

Bákan náà Àdìká ìyá Ayọ̀ kọ̀ láti bá ọmọ rẹ̀ wí, gbogbo ìgbà ti Àjàdí bàbá Ayọ̀ bá fẹ́ tọ́ ọmọ rẹ̀ sọ́nà ni Àdìká máa n takò ó. Èyí ló mú Ayọ̀ di ẹja gbígbẹ tí kò ṣe é ká. Nítorí àìní ìbáwí Ayọ̀, ó darapọ̀ mọ àwọn Ọ̀bàyéjẹ́ láti máa jalè. Lẹ́nu iṣẹ́ olè jíjà yìí ni Ayọ̀ àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ti gbìyànjú àtida ẹ̀mí Akínwálé, àbúrò rẹ̀ légbodò, Àdìká kò jèrè ọmọ rẹ̀, Ayọ̀ nítorí pé ó kùnà gẹ́gẹ́ bí òbí láti bá ọmọ rẹ̀ wí àti láti tọ́ ọ sí ọ̀nà rere.

**Pàtàkì Ẹ̀kọ́ Ìwé**

Ẹ̀kọ́ ìwé ṣe pàtàkì, ó sì jẹ́ ọ̀nà láti ró ara ẹni ni agbára. Ayọ̀ kùnà láti ka ìwé rẹ̀ dójú àmì èyí ló sì mú un di alábàárù ni ibùdókọ̀. Lẹ́nu iṣẹ́ alábàárù yìí náà ni Ayọ̀ si ti darapọ̀ mọ̀ àwọn olè tí ó n pa àwọn ènìyàn lẹ́kún jayé. Ọwọ́ pálábá Ayọ̀ àti àwọn ìgárá ọlọ́ṣà ẹgbẹ́ rẹ̀ ségi, adájọ́ sì ju wọ́n sí ẹ̀wọ̀n gbére. Akínwálé àbúrò Ayọ̀ fi ọwọ́ tó nípọn mu ẹ̀kọ́ rẹ̀, èyí ló fún un ní àǹfààní láti lọ sí òkè òkun tí ó sì di olórí akọ̀wé ètò owó àti ètò ìsúná ìlú Ọ̀kọ́, ẹ̀kọ́ ìwé ṣe pàtàkì, ó ṣe kókó.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Orí mọ́kànlá ni Olújìnmí pín ìwé ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ sí. Orí kìnní ni ó jẹ́ ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn, orí kejì sí ẹ̀kẹsàn-án jẹ́ àárin àhunpọ̀ ìtàn, nígbà tí orí kẹwàá sí ìkọkànlá sì jẹ́ ìparí àhunpọ̀ ìtàn.

Orí kìnní tí ó jẹ́ ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn ni Olújìnmí ti ṣe àpèjúwe ìlú Ìlọfẹ̀, tí ó sì fi hàn àwọn òǹkàwé irú ẹni ti Àjàdí àti Àdìká ìyàwó rẹ jẹ́.

Nínú orí kejì ni Àjàdí ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ asánko pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Adégún ìbátan rẹ̀, gbígbé tí Àjàdí ń gbé pẹ̀lú ẹbí Adégún ní ìlú Ọ̀kọ́ mú àyípadà ńlá bá ìgbésí ayé rẹ̀. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní í lọ sí ṣọ́ọ̀ṣì. Akínwálé n gbé lọ́dọ̀ bàbá rẹ̀ ní Ọ̀kọ́. Nínú orí kẹta ní o ti di mímọ̀ pé Ayọ ti n bá mọ́tò kiri ni abúlé wọn. Bẹ́ẹ̀ ni Àjàdí di ìránṣẹ́ ní ibi iṣẹ́ rẹ̀.

Nínú orí kẹrin ni Akínwálé ti ri ìrànlọ́wọ́ ìlú gbà tí ó sì lọ sí òkè òkun pẹ̀lú Ládérìn ọmọ ọba. Orí karùn-ún ni iṣẹ́ burúkú àwọn Ọ̀bàyéjẹ́ ti ń gbilẹ̀ síi ni Ìlọfẹ̀, orí yìí kan náà ni Ayọ̀ ọmọ Àdìká ti darapọ̀ mọ́ àwọn ìgárá ọlọ́sà. Gbogbo ọ̀rọ̀ tí ìyá rẹ̀ n bá a sọ kò tu irun kan lára rẹ̀.

Orí kẹfà ni Kínyọ̀ àti Àjàdí ti gba ìwé ìfẹ̀yìntì, tí Àjàdí sì kọ̀ láti padà sí ìlú Ìlọfẹ̀. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní í ṣe òwò iṣu ṣùgbọ́n ó seni láàánú pé Àjàdí pàdánù ẹ̀mí rẹ̀ nínú ìjàmbá mọ́tò.

Nínú orí keje Sùnmọ́nù àti àwọn ọ̀bàyéjẹ́ ẹgbẹ́ rẹ̀ n gbilẹ̀ síi nínú iṣẹ́ ibi wọn, gbogbo ìlàkàkà àwọn ọlọ́pàá kò sì so èsò rere. Jimọ̀ tá àwọn ọlópàá lólobó, èyí ló sì ràn wọ́n lọ́wọ́ láti mú òkẹ́rẹ́ níbi tí ọ̀kẹ́rẹ́ ti ń kó ọsàn. Títakú tí ọ̀kẹ̀rẹ̀ taku láti dárúkọ àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù ló jẹ́ kò fòjú ba ilé ẹjọ́, adájọ́ sì sọ ọ́ sì ẹ̀wọ̀n ọdún mẹ́wàá gbáko. Orí kẹjọ ni Akínwálé ti padà dé láti òkè òkun ti Ayọ̀ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ sì ba gbé ẹru wálé láìmọ̀. Ìbànújẹ́ subú lu Ayọ̀ fún Àdìká.

Orí kẹsàn-án ni àwọn ìjòyè ti kọ̀ jálẹ̀ pé Akínwálé kò le máa báwọn jókòó papọ̀ ní ìpàdé ìlú ṣùgbọ́n nígbẹ̀yìn, wọ́n fààyè gbà á. Akínwálé ṣe ìgbéyàwó aláṣàlátù, inú Àdìká sì dùn púpọ̀. Nínú orí yìí kan náà ni àwọn Ọ̀báyéjẹ́ ti yin ìbọn mọ Akínwálé, tí wọ́n sì wa ọkọ̀ rẹ̀ lọ sínú ìgbàlẹ̀ wọn. Orí kẹ́wàá ni ìtàn àròsọ náà ti n sáré lọ sópin. Ìsọ̀ Ejide ni àṣírí ikú to pa Akínwálé ti tú¸síta láti ẹnu àwọn ọmọ ilé-ìwé méjì kan. Èyí ló sì ran ọlópàá ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ láti ìlú kejì lọ́wọ́ láti dọdẹ Sùnmọ́nù àti àwọn Ọ̀bàyéjẹ́ ẹgbẹ́ rẹ. Ní ìgbẹ̀yìn, ọwọ́ sìnkún àwọn ọlọ́pàá tẹ Sùnmọ́nù àti àwọn ìsọmọgbè rẹ̀ wọ́n sì fi wọ́n ṣe ẹgbẹ̀tàlà yẹ̀yẹ́.

Orí kọkànlá tí ó parí ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ ni àwọn ènìyàn ti mọ̀ pé Akínwálé kò kú àti pé àwọn ọlọ́pàá fi pamọ́ ni láti lé ráàyè ṣe ìwádìí wọn. Ojú àwọn Ọ̀bàyéjẹ́ hàn fún aráyé rí, Ayọ̀bámi àti àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ ni adájọ́ fi sí ẹ̀wọn gbére, nígbà tí olórí wọn, Sùnmọ́nù gba ìdájọ́ ikú nípa fífi ẹ̀yìn ti àgbá fi àyà gba ọta ìbọn.

**Ibùdó Ìtàn**

Ibùdó ìtàn gbogbogbòò fún ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́* ní ìlú Ìlọfẹ̀. Àwọn mìíràn tí ó tún jẹyọ ni Ọ̀kọ́ àti Àbújá.

Àwọn ibùdó ìtàn pàtó tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé ìtàn náà ti wáyé ni ìlú Ìlọfẹ̀ ìlú Ọ̀kọ́, Ilé Àjàdí, Ilé-iṣẹ́ atúnlùútò, Ilé Adégún, Ibùdókọ̀, Ìgbàlẹ̀, Ààfin Ọba Ọ̀kọ́, Ilé Akínwálé àti Ilé-ẹjọ́.

**Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn**

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni Olújìnmí lò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́. Àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn mìíràn tí ó tún súyọ ni àpèjúwe (o.i 1,2,35, 73,75), ọ̀rọ̀ àdásọ (o.i 3, 52, 74) ọgbọ́n ìpadàsẹ́yìn (o.i 21), ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́ ìran (o.i 38), lẹ́tà (o.i 49, 50-51).

**Ìfiwàwẹ̀dá**
Àwọn ẹ̀dá ìtàn márùn-ún ti a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò wọn lábẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Àjàdí, Àdìká, Ayọ̀bámi, Akínwálé àti Adégún.

**Àjàdí**
Àjàdí ni olú ẹ̀dá ìtàn *Ọ̀bàyéjẹ́*. Àjàdí jẹ́ ẹni tí ó rí jájẹ ní ìgbà kan rí ṣùgbọ́n nípa ìwà àtẹnujẹ àti àfọwọ́fà, ó padà di olòsì bẹ́ẹ̀ ni, àìlówó lọ́wọ́ Àjàdí ló sọ ọ́ di igbá ìwẹ̀wọ̀ fún ìyàwó rẹ̀. Èyí náà ni kò sì jẹ́ kí ó ni ẹnu ọ̀rọ̀ lórí ọmọ rẹ̀ Ayọ̀bámi. Bí ó tilẹ̀ jẹ pé Àjàdí kì í ṣe ọ̀lẹ, ṣùgbọ́n alágbára ma mèrò ẹ̀dá ni. mímúra ti Àjàdí múra sí iṣẹ́ ní Ọ̀kọ́ ló mú un kúrò ni aṣánko tí ó sì di ìránṣẹ́ ni ọ́fíìsì Kínyọ̀. Lẹ́yìn ọdún díẹ̀ tí Àjàdí ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìránṣẹ́, ó gba ìwé ìfẹ̀yìntì, bẹ́ẹ̀ ni owó ìfẹ̀yìntì yìí ni Àjàdí fi bẹ̀rẹ̀ òwò iṣu ní Ọ̀kọ́, Àjàdí kọ̀ láti padà sí Ìlọfẹ̀ torí ìwà burúkú tí Àdìká ìyàwó rẹ̀ n hù sí í. Nínú ọ̀kan nínú àwọn ìrìnàjò rẹ̀ lọ sí ìlú Àbújá ni Àjàdí ti dágbére fáyé. Orí iṣẹ́ ni ago Àjàdí kú lé kò jẹ èrè iṣẹ́ tó ṣe.

**Àdìká**
Ìyàwó Àjàdí ni Àdìká jẹ́, Arẹwà àti alágbára obìnrin ni. Nínú abúlé Ìlọfẹ̀, Àdìká ni obìnrin tí ó rẹwà jùlọ ṣùgbọ́n kò fi ìwà kún ẹwà. Onípákáleke ẹ̀dá ni Àdìká, ìṣe rẹ̀ nínú ilé kò sì tẹ́ ọkọ rẹ̀ Àjàdí lọ́rùn. Àjàdí kò ni iṣẹ́ lọ́wọ́ ṣùgbọ́n Ọlọ́run ṣínà ire fún Àdìká ìyàwó rẹ̀, ó n ri ṣe ó sì n rí èrè gọbọi ní ibi iyọ̀ tó n tà, gbogbo èrè ti Àdìká n rí lórí iṣẹ́ tó n ṣe yìí kò fí mọ ọkọ rẹ̀. Kí ó tó lè fún ọkọ rẹ̀ lówó, ó gbọdọ̀ bá a ru iyọ̀ lọ sì ìlú kejì. Àdìká jẹ́ àpẹẹrẹ àwọn ìyàwó burúkú tí ó máa ń jẹ gàba lórí ọkọ wọn. Bákan náà, Àdìká jẹ́ àpẹẹrẹ ìyá burúkú. Kíkọ̀ ti Àdìká kọ̀ kí Àjàdí bá Ayọ̀bámi wí láti kékeré ló sọ ọ́ di aláìgbọràn àti olè. Àdíká jèrè gbogbo ìwà tí ó hù sí ọkọ rẹ torí lọ́jọ́ alẹ̀ rẹ kò ni ìfọ̀kànbalẹ̀. Ọlọ́run lò ko Akínwálé yọ lọ́wọ́ àwọn ìkà ènìyàn tó fẹ́ dá ẹ̀mí rẹ̀ légbodò ṣùgbọ́n Ayọ̀bámi lọ sí ẹ̀wọ̀n gbére, Àdìká sì kábàámọ̀ ìwà burúkú rẹ̀ gbogbo.

**Ayọ̀bámi**
Àkọ́bí ni Ayọ̀bámi jẹ́ fún Àjàdí àti Àyọ̀ká. Arẹwà ọkùnrin ni Ayọ̀bámi. Ẹwà rẹ̀ ló si jẹ́ kí àwọn obìnrin ilé máa pè é ni orí fààrí. Gbogbo àwọn olùkọ́ Ayọ̀ ló fẹ́ràn rẹ̀ nígbà tó wà ni ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, nítorí kò sí ẹni tí í bá a du ipò kínní. Àìlówó lọ́wọ́ Àjàdí ni Àdìká kò fi gbà á láàyè láti máa bá Ayọ̀ wí. Àìlólùbáwí Ayọ̀ ni kò jẹ kí o lè tẹsíwájú nínú ẹ̀kọ́ rẹ lẹ́yin tí ó ti parí ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Àjàdí lọ sí ìlú Ọ̀kọ́ kò sì janpata mọ́ lórí ọ̀rọ̀ Ayọ̀bámi. Ayọ̀ di alábàárù ní ìdíkọ̀, kò sì pẹ́ tí ó fi darapọ̀ mọ́ àwọn Ọ̀bàyéjẹ́ àti olè lọ́nà àti lówó kíákíá. Ayọ̀ wà lára àwọn tó dá àbúrò rẹ̀ Akínwálé lọ́nà, nígbà tí ọwọ́ àwọn ọlọ́pàá sì tẹ Ayọ̀ àti àwọn ìgárá ọlọ́sà ẹgbẹ́ rẹ̀ wọn fojú wọn ba ilé ẹjọ́, adájọ́ sì fi Ayọ̀bámi sí ẹ̀wọn gbére. Ojúkòkòrò àti ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́ ló kó wàhálà ba Ayọ̀. Yorùbá bọ̀ wọ́n ni "ẹgbẹ́ búburú ba ìwà rere jẹ́".

**Akínwálé**
Ọmọ Àjàdí àti Àdìká ni Akínwálé jẹ́, Akínwálé jẹ́ olórí pípé ọmọ tí kì í fi ẹ̀kọ́ ṣeré. Lẹ́yìn ọdún kan tí Àjàdí ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ni Ọ̀kọ́ ni Akínwálé lọ bá bàbá rẹ̀. Gbígbe ti Akínwálé gbé pọ̀ pẹ̀lú ẹbí Adégún ní ipa rere nínú ìgbésí ayé rẹ̀, o mọ̀ orísìírísìí ẹ̀kọ́ ilé bẹ́ẹ̀ ni ìbẹ̀rù Ọlọ́run gbilẹ̀ sí í lọ́kàn rẹ̀. Yiyege tí Akínwálé yege nínú ìdánwò tí àwọn ìlú ṣe fún àwọn ọmọ wọn ló fún un ni àǹfààní láti lọ kọ́ Ẹ̀kọ́ nípa ìsirò owó ní òkè òkun lẹ́yìn tí Akínwálé padà dé láti òkè òkun, ó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí olórí akọ̀wé owó àti ètò ìsúná ìlú, àwọn Ọ̀bàyéjẹ́ gbìyànjú láti dá ẹ̀mí Akínwálé légbodò ṣùgbọ́n orí kó o yọ. Akínwálé jẹ́ ọmọ ìdùnnú fún àwọn òbí rẹ̀, ìbẹ̀rù Ọlọ́run àti ìwà rere rẹ̀ ni kò jẹ́ kí ìràwọ̀ rẹ̀ wọ òòkùn láìpé ọjọ́.

**Adégún**
Ìbátan Àjàdí ní ìdí ìyá ni Adégún. Ìlú Ọ̀kọ́ ni Adégún ń gbé, bẹ́ẹ̀ ni ó sì ri tajé ṣe. Ẹ̀kọ̀ọ̀kan ni Adégún máa n wá sí ìlú Ìlọfẹ̀. Ní irú àkókò yìí, Adégún máa ń ṣe fàájì ni ilé ẹmu ṣùgbọ́n ọtí fàájì ni Adégún máa n mu kì í ṣe alámupara. Ọ̀kan nínú àwọn ọ̀rẹ́ Àjàdí tó jẹ ọ̀mùtí ló fi ọ̀rọ̀ Àjàdí dápàárá nídìí ẹmu, ọ̀rọ̀ tí ọ̀mùtí yìí sọ mú Adégún lọ́kan tó bẹ́ẹ̀ tí ó fi bá Àjàdí wá iṣẹ́ aṣánko sí ìlú Ọ̀kọ́. Onínúrere ẹ̀dá ni Adégún, ó máa n fún Àjàdí lówó. Iṣẹ́ tó bá Àjàdí wá ló gbà á kalẹ̀ lọ́wọ́ ọ̀rọ̀ kòbákùngbé tí Àdìká ìyàwó rẹ̀ n fi ojoojúmọ́ sọ sí i. Adégún jẹ́ onígbàgbọ́ tòótọ́ òun ló ba Àjàdí sọ̀rọ̀ nípa ilé Ọlọ́run lílọ, Àjàdí bẹ̀rẹ̀ sọ́ọ̀sì lílọ o sì darapọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ oore-ọ̀fẹ́. Ilé aláyọ̀ ní ilé Adégún, ìrẹ́pọ̀ nlá ló sì wà láàrin Adégún, ìyàwó rẹ̀, Moróyèdé àti àwọn ọmọ rẹ̀ Adéolú àti Ìbùkún. Ọ̀rẹ́ tòótọ́ àti ìbátan pàtàkì ni Adégún jẹ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Àjàdí ti di olóògbé síbẹ̀ Adégún kò pa ọdọ Àdìká tì, gbogbo ọ̀rọ̀ ìbínú tí Àdìká sì máa ń sọ sí i ló máa n fi ṣe osùn pa ara. Ènìyàn rere àti ọlọ́kan titẹ́ ni Adégún.

**Ìlò Èdè**
Ọ̀nà ti Olújìnmí gbà lo èdè nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́* jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé òǹkọ̀wé tí ó pegedé nínú èdè Yorùbá tí ó sì mọ àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ ni.
Àwọn ìlò-èdè tí a ó máa gbéyẹ̀wò bí Olújìnmí ṣe ṣàmúlò wọn ni Àfiwé, àwítúnwí, àsọrégèé, òwe, ọfọ̀, oríkì àti orin.

**Àfiwé tààrà**
Olújìnmí máa ń ṣe àmúlò àfiwé tààrà nínú *Ọ̀bàyéjẹ́* nígbà tí ó bá ń ṣe àpèjúwe bí nǹkan ṣe rí. Fún àpẹẹrẹ:
Níbi tí ó jókòó sí lójú kan náà
<u>Ni ó ń wami lójú bíi egbére (o.i 3)</u>
Omi tí ó ń jáde lójú Àjàdí lẹ́yìn tí ó jẹ́ ọbẹ̀ aláta tí ìyàwó rẹ̀ ṣè tán ni Olújìnmí fi wé omi tí ó máa ń jáde ni ojú egbére.
Àwọn àpẹẹrẹ àfiwé tààrà mìíràn wà ni ojú ìwé 2,4,10,16,23,33,35,60.

**Àwítúnwí**
Àwítúnwí ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ni Olújìnmí ṣàmúlò nínú ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́*
Owó tí wọ́n n gbà gọntiọ

Ilé ọ̀fẹ́, iná ọ̀fẹ́, oúnjẹ ọ̀fẹ́
Ìwòsàn ọ̀fẹ́, ohun gbogbo ọ̀fẹ́ ni (o.i 32)

Àdìká ni iṣẹ́ wo ni, iṣẹ́ ìyà, iṣẹ́ yẹ̀yẹ́ àdánwò iṣẹ́
Tó n ṣe kálẹ̀ kiri (o.i 40)
Nínú àwọn àpẹẹrẹ méjèèjì tí ó wà lókè yìí ọ̀fẹ́ àti iṣẹ́ ní àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tí Olújìnmí ṣe àwítúnwí wọ́n, ó sì ṣe èyí fún àtẹnumọ́ ni.

**Àsọrégèé**
Nínú ìwé ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ òǹkọ̀wé ṣe àmúlò àsọrégèé nípa sísọ àsọlé ọ̀rọ̀ tàbí ṣíṣe àfikún sí bi ọ̀rọ̀ ti rí gan-an ní pàtó. Fún àpẹẹrẹ:
Ní ọjọ́ náà,, bí ó ṣe wọlé,
Orí ẹní ni ó dà lé. Ó bì, ó fẹ́rẹ̀ bi ìfun rẹ̀ jáde. (o.i 6)

Àwòrán bí Àjàdí ṣe mu ọtí yó tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í se kábakàba ni òǹkọ̀wé gbé kalẹ̀ ṣùgbọ́n òǹkọ̀wé ṣe àfikún ọ̀rọ̀ nítorí pé kò sí bí ènìyàn ṣe lè bì tó, kí ó bí ìfun rẹ̀ jáde.
Ẹni bá dáná nínú ilé rẹ̀, ajẹ́ wí pé kì í jẹ́ ẹran tàbí ó fẹ́ gbé e
Féwúrẹ́ jẹ ni. Àwọn ẹran pàápàá kọ̀, wọ́n ò jẹ oúnjẹ olówó
wọn lọ́jọ́ náà, ilé onínàwó ni wọ́n fi ìkàlẹ̀ sí (o.i 34)

Ayẹyẹ ìdágbére tí àwọn ilú Ọ̀kọ́ ṣe fún àwọn ọmọ tí wọn ń lọ sí òkè òkun ni òǹkọ̀wé gbé kalẹ̀. Òǹkọ̀wé ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ àfikún àti àsọdùn nítorí pe kò sí bí oúnjẹ ṣe le pọ̀ tó tí àwọn ènìyàn kò ní í dáná nínú ilé wọn. Bẹ́ẹ̀ ni àwọn ẹran kò lè torí pé onínàwo ń ṣe ìnawó, kọ oúnjẹ olówó wọn sílẹ̀. Gbogbo ọ̀rọ̀ tí òǹkọ̀wé sọ lókè yìí, àsọdùn ni.

**Òwe**
Òwe jẹyọ lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́*, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn òwe yìí ni òǹkọ̀wé lò bí a ti máa ń lò wọ́n lójú ayé ní ìbáámu pẹ̀lú ọ̀gangan ipò tí wọ́n ti súyọ láti gbe ọ̀rọ̀ kan tàbí èkejì lẹ́sẹ̀ nípasẹ̀ àkàwé ọ̀rọ̀ ibẹ̀.
Fún àpẹẹrẹ:
Ohun tí aláìmọ̀kan fi ń ṣe ara rẹ̀ ló pọ̀ (o.i 2)
Fífò ti Àdìká fo mọ́ ọkọ rẹ̀ lọ́rùn, tí kò jẹ́ kí ó bá Ayọ ọmọ wọn wí nígbà tí ó lo wẹ̀ lódò lásìkò òjò ni òǹkọ̀wé ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀. Àdìká sì ni aláìmọ̀kan tí ó ń ṣe ara rẹ̀ nítorí pé ó padà kábàámọ̀ lórí ọ̀rọ̀ Ayọ̀. Fún àpẹẹrẹ òwe síi, wo ojú ìwé 6,14,16,22,23,33,35,60.

**Ọfọ̀**
Olújìnmí tún ṣàmúlò ọfọ̀ tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ewì alohùn Yorùbá nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́*. Fún àpẹẹrẹ:
Ẹyẹ kì í fò, ko forí sọ igi,
Eku kì í rìn nígbo kò forí sọ igi
Ìkọ́kíkọ̀ọ́ kan kì í kọ́ ejò lẹ́sẹ̀
Ẹja kì í gbódò kígbe òtútù
Toro gínní ladìyẹ toko èèmọ̀ bọ̀… (o.i. 9)

Olóyèdè, ọ̀rẹ́ Àjàdí ló ṣe àdúrà fún un ní ìgbà tí àwọn ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ n bá a dáwọ̀ọ́ ìdùnnú pé ó ri iṣẹ́. Gbólóhùn máyẹ̀ sì ni ìpèdè náà fún Àjàdí pé àlọ àti àbọ̀ rẹ̀ kò ní léwu.
Wo ojú ìwé 31 àti 41 fún àpẹẹrẹ ọfọ̀ mìíràn.

**Oríkì**
Oríkì náà kò gbẹ̀yìn nínú ìlò èdè Olújìnmí nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́*, gbogbo àwọn oríkì tí ó jẹyọ jẹ́ oríkì orílẹ̀ ó sì wà fún àpọ́nlé àti àyẹ́sí ni.
Fún àpẹẹrẹ:
Akínwálé ọmọ ọlọ́fà mọjọ̀
Àkànó ẹ̀rú
Ọlálọmí, ọmọ abíṣujórúkọ
Ìjàkadì katákìtì lorò ọ̀fà… (o.i 35)

Àdìká ló n ki ọmọ rẹ̀ Akínwálé ni mẹ́sàn-án, mẹ́wàá nígbà tí ó n lọ kàwé ní òkè òkun, èyí sì n mu orí Akínwálé àti gbogbo èrò wú.
Wó àpẹẹrẹ oríkì sí i ní ojú ìwé 11,42,68.

**Orin**
Oríṣìíríṣìí orin ló súyọ nínú ìwé ìtàn àròsọ *Ọ̀bàyéjẹ́,* bí a ṣe ri orin ẹ̀fẹ̀ bẹ́ẹ̀ náà ni orin onígbàgbọ́ bẹ́ẹ̀ ni orin ọpẹ́ náà kò gbẹ́yìn.
Fún àpẹẹrẹ:
Fowó sin Jéèsù
Má se fowó mutí
Ògógóró kì í ṣatẹ́jẹ̀ ṣe
Fowó sin Jéésù
Má ṣe fowó muti (o.i 5)

Àwọn ọmọdé ló máa ń kọ orin òkè yìí láti fi Àjàdí ṣe yẹ̀yẹ́ nígbà tí ó bá ti mu ọtí yó tí ó sí jókòó sí ojú kan náà.
Àpẹẹrẹ orin mìíràn wà ní ojú ìwé 15,94,105.

## 4.3 Àjà Ló Lẹrù: Ọládèjọ Òkédìjí

**Kókó**

**Ìfẹ́ Ìlú**
Lápàdé ọlọ́pàá tí ó fi iṣẹ́ sílẹ̀ láti mójútó oko ti bàbá rẹ̀ fi sílẹ̀ fún un ló fi ìfẹ́ nlá hàn sí ìlú rẹ̀ nípa ìpinnu rẹ̀ láti ṣe iṣẹ́ tí àwọn ọlọ́pàá ṣe láṣetì. Ọ̀kanòjọ̀kan ìṣẹ̀lẹ̀ ìjínigbé, olè jíyá àti igbó gbíngbín ló gbá igboro ìlú Ìbàdàn àti agbègbè rẹ̀ kan. Gbogbo ìlàkàkà àwọn ọlọ́pàá láti wagbò dẹ́kun fún àwọn ọ̀daràn yìí, pàbó ló n jásí.

Lápàde pẹ̀lú alábàáṣiṣẹ́pọ̀ rẹ̀ (Tàfá Ìgìrìpá) pa itú méje tí ọdẹ ń pa láti rẹ́yìn àwọn ọ̀daràn tí ó ń da àwọn ará ìlú láàmú. Ìwà ipá ni Lápàdé àti Tàfá fi ń rí òkodoro ọ̀rọ̀ gbà lẹ́nu àwọn ọ̀daràn. Táfá Ìgìrìpá jẹ́ akin ẹ̀dá ìtàn, lọ́nà

àtile rí òkodoro ọ̀rọ̀ nípa ibi ti Angelínà wà, wọ́n yọ eyín Tíámíyù. Wọ́n tún de Táíwò, Délé, Kọ̀lá àti ìyá àgbà mọ́lẹ̀ ní Ìkèrèkú.

Nítorí ìfẹ́ ìlú àti lọ́nà àti jẹ́ kí àlàáfíà dé bá àwọn ènìyàn ìlú Lápàdé fi orí la ọ̀pọ̀lọpọ̀ ewu. Kò tilẹ̀ bìkítà nípa ẹ̀mí ara rẹ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ló ń lọ sí bùbá àwọn ọ̀daràn yìí. Ibùba àwọn agbingbó ti Lápàdé lọ ló ti ri Tọ̀lání ọmọ ọ̀dọ̀ Angẹlínà tí wọ́n jí gbé.

Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé orí ọká ni Lápàdé àti Tàfá fi n họ imu nípa wíwọ bùba àwọn ọ̀daràn lọ ṣùgbọn pẹ̀lú ìpinnu ọkàn, ìfàyàrán, àti ìfẹ́ ìlú tí wọn ní lọ́kàn Lápàdé àti Tàfá ṣe àṣeyọrí nípa fífi ojú àwọn ọ̀daràn ajọ́mọgbé àti agbingbo hàn, iṣẹ́ ti ọ̀gá ọlọ́pàá Aúdù Kàrímù àti àwọn ọlọ́pàá ẹgbẹ́ rẹ̀ ṣe láṣetì.

**Ìlara**

Aúdù Kàrímù ọ̀gá ọlọ́pàá jẹ́ onílara ènìyàn. Inú rẹ̀ kò dùn sí bi Lápàdé àti àwọn jàndùkú rẹ̀ ṣe ń ṣe àṣeyọrí nípa fífi ojú àwọn olè, ajọ́mọgbé àti agbingbó hàn. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni Aúdù Kàrímù ti gbìyànjú láti rí i pé òun fi Lápàdé hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀daràn ṣùgbọ́n Lápàdé mọ èrò ọkàn Aúdù yìí, ó sì ń kíyèsára láti rí i pé èrò Lápàdé yìí kò jọ lé òun lórí.

Aúdù lérò pé ohùn ti kò kan Lápàdé lápá lẹ́sẹ̀ ló ń tojú bọ̀. Ìdí tí ó fi rò báyìí ni pé Lápàdé ti fi iṣẹ́ ọlọ́pàá sílẹ̀. Ní èrò Aúdù kò yẹ kí Lápàdé máa gba iṣẹ́ àwọn ọlọ́pàá ṣe. Pẹ̀lú gbogbo ìlara Aúdù sí Lápàdé, o hàn gbangba pé Àjà ló lẹrù, irọ́ ni pẹpẹ Aúdù Kàrímù ń pa.

**Ìkùnà àwọn Ọlọ́pàá**

Ó hàn gbangba pé àwọn ọlọ́pàá kùnà láti kápá àwọn olè, ajọ́mọgbé àti agbingbo ni ìlú Ìbàdàn àti agbègbè rẹ̀. Ìwà àwọn ọ̀daràn wọ̀nyí kó ìjayà bá àwọn ará ìlú, èyí ló sì ń mú àwọn ìwé ìròyìn ké gbàjarè lémọlémọ sí ìjọba láti gbé ọ̀ga àwọn ọlọ́pàá Aúdù Kàrímù kúrò nítorí àwọn ará ìlú gbàgbọ́ pé kò kún ojú òṣùnwọ̀n gẹ́gẹ́ bí ọ̀gá ọlọ́pàá.

Ìkùnà àwọn ọlọ́pàá yìí láti kápá àwọn ìwà ọ̀daràn ọ̀kanòjọ̀kan tó ń ṣẹlẹ̀ ní ìlú ló mú Lápàdé pinnu láti wádìí àwọn ọ̀daràn náà. Lápàdé sì ṣe àṣeyọrí.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Orí mẹ́wàá ni Òkédìjì pín ìwé ìtàn *Àjà ló lẹrù* sí. Orí kìnní ni ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn. Ní orí yìí ni òǹkọ̀wé ti sọ ọ́ di mímọ̀ ọ̀kan-òjọ̀kan ìwà ọlẹ̀, ìjínigbé àti igbó gbíngbìn tò ń lọ ní ìlú Ìbàdàn ṣùgbọ́n tí àwọn ọlọ́pàá kùnà láti kápá ọ̀daràn wọ̀nyí. Orí kìnní yìí náà ni Aúdù Kàrímù ọ̀gá àwọn ọlọ́pàá ti ka Lápàdé sí arúfin, èyí ló sì mú kí Lápàdé pinnu láti fi ojú àwọn arúfin náà hàn kí ó le wẹ ara rẹ̀ mọ́.

Orí kejì sí ìkeje ni àárin àhunpọ̀ ìtàn. Orí kẹta ni Tàfá ti gbé Táíwò lọ sí ọ̀dọ̀ Jàmpàkò. Ní ilé Jàmpàkò ni Táíwò ti sálọ mọ Lápàdé àti Tàfá lọ́wọ́.

Sàlámì Kemberú àti Kàrímù Alákòóbá wá owó Táíwò ti Lápàdé hú lọ̀nà oko wá ṣùgbọ́n gbogbo akitiyan àwọn olè méjèèjì yìí pàbó ló jásí nínú orí kẹrin. Nínú orí karùn-ún ni Angẹlínà ti wá bẹ Lápàdé láti bá a wá Tọ̀lání ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ tí ó sọnù. Lápàdé sì ṣe ìlérí fún Angẹlínà pé òun yóò sapá òun láti jẹ́ kí ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ náà di rírí.

Tàfá Ìgìrìpa gba Lápàdé ni ìmọ̀ràn pé kí wọ́n wa Tọ̀lání tí ó sọnù lọ sí ọ̀dọ̀ Tìámíyù Alápámáṣiṣẹ́ bẹ́ẹ̀ ni nínú orí kẹfà ìjà n lá si bẹ́ sílẹ̀. Délé, ọ̀kan lára àwọn ọ̀daràn yìí ló sọ fún Lápàdé pé Ìkèrèkú ni wọ́n gbé Tọ̀lání ọmọ ọ̀dọ̀ Angẹ́línà tó sọnù lọ. Orí kejì ni Lápàdé àti Tàfá ti lọ sí Ìkèrèkú, wọ́n sì rí i pé ọ̀ọ̀tọ̀ ni ọ̀rọ̀ ti Délé sọ.

Orí keje sí ìkẹwàá ní òpin àhunpọ̀ ìtàn. Láti orí kẹjọ ni ìtàn náà ti n sáré títí tí ó fi dé òpin. Tìámíyù àti àwọn ọ̀daràn ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù fi ìyà jẹ Délé fún jíjúwe tó júwe abà Gbékúbà fún Lápàdé àti Ìgìripá. Wọ́n dàámú nígbà ti ìyá àgbà sọ fún wọn pé àlejò wà lábà, àpèjúwe àwọn àlejò yìí ti ìyá àgbà ṣe ló jẹ́ kí wọ́n mọ̀ pé Lápàdé àti Tàfá ló wá sí abà. Délé ní tirẹ̀ ráyè sálọ̀ nígbà tí àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ n wá Lápàdé. Orí kẹsàn-án ni àwọn agbingbó ti pinnu láti lọ́ tú gbogbo igbó tí wọ́n gbìn dànù kí àwọn ọlọ́pàá tó dé, èyí ló fún Lápàdé àti Tàfá ní àǹfààní láti padà sí abà Gbékúbà. Lápàdé de ìyá àgbà mọ́lẹ̀, ó fún Tọ̀lání ní oúnjẹ, ó sì ko owó kọ́rẹ́nsì tí ó wà nínú agolo nínú apẹ̀rẹ̀ igbó. Lẹ́yìn èyí ni ó mú Sẹ̀lía, àti Tọ̀lání lọ pẹ̀lú rẹ̀.

**Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn**

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni Òkédìjí lò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn àròsọ *Àjà ló lẹrù*. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìtàn àròsọ *Àjà ló lẹrù* jẹ́ ìtàn àròsọ, ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá amárabùmásọ èyí tí ó dá lé ṣíṣe ìwádìí àwọn ọ̀daràn nípa lílo àwọn jàndùkú. Ọ̀nà tí Òkédìjí gbà ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn àròsọ yìí kẹ́sẹjárí. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí ó ṣàmúlò wà ní ìbámu pẹ̀lú irúfẹ́ ìtàn tí ó sọ. Ìtàn àròsọ *Àjà Ló Lẹrù* kún fún onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ tó yára kankan, asọtán kò fi àkókò àwọn òǹkàwé sòfò rárá.

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde yìí tún fi ààyè sílẹ̀ fún àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn mìíràn bíi àpèjúwe (o.i. 1,5,7,61,79). Ọ̀rọ̀ àdásọ (o.i 12, 43), ìgbékalẹ̀ ajẹmọ́ ìran (o.i 22,23, 37,65) ìwé ìròyìn (o.i 13, 57, 142) rédíò (o.i 41, 55, 65, 93, 141), ìtàn nínú ìtàn (o.i 133).

**Ìfiwàwẹ̀dá**

Ní abẹ́ ìsọ̀rí yìí àwọn ẹ̀dá ìtàn mẹ́fà pàtàkì ni a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò wọn. Àwọn ẹ̀dá ìtàn yìí ni Lápàdé, Tàfá Ìgbìrìpá, Aúdù Kàrímù, Tíámíyù Alápámáṣiṣẹ́, Gbékútà àti Ṣẹ̀lí.

**Lápàdé**

Olú ẹ̀dá ìtàn Àjà Ló Lẹrù ni Lápàdé jẹ́, Ọlọ́pàá tí ó ti fi iṣẹ́ sílẹ̀ ni Lápàdé. Kíkú ti baba Lápàpé kú ló jẹ́ kí o fi iṣẹ́ ọlọ́pàá sílẹ̀ láti lè mójútó oko ti bàbá rẹ̀ fi sílẹ̀ fún un. Oríṣìíríṣìí ìwà ọ̀daràn tí ó gba ìlú Ìbàdàn kan tí àwọn

ọlọ́pàá kò lè kápá ló mú Lápàdé pinnu láti wádìí àwọn ọ̀ràn náà kò sì kó wọ́n lé ọlọ́pàá lọ́wọ́.

Lápàdé jẹ́ ẹ̀dá ìtàn tí ó ni ìfẹ́ ìlú rẹ̀ lọ́kàn. Àwọn àbùdá pàtàkì tí Lápàdé ní ni agbára, ìforítì, ìpamọ́ra, bẹ́ẹ̀ ni ò mọ oríṣìíríṣìí ọgbọ́n àti ète tí àwọn ọ̀daràn máa ń lò. Àwọn ohun tí ó mú Lápàdé ṣe àṣeyọrí níbi tí àwọn ọlọ́pàá ti kùnà ni ìgboyà tí ó ní, agbára rẹ̀ àti ọgbọ́n orí rẹ̀. Lápàdé jẹ́ aláròjinlẹ̀ ẹ̀dá, ipá tí Tàfá Ìgìrìpá kó nínú àṣeyọrí Lápàdé náà kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn.

**Aúdù Kàrímù**
Ọ̀gá àwọn ọlọ́pàá ní ìlú Ìbàdàn ni Aúdù jẹ́. Alábàáṣiṣẹ́pọ̀ ni Aúdù jẹ́ pẹ̀lú Lápàdé nígbà tí Lápàdé sì wà lẹ́nú iṣẹ́ ọlọ́pàá. Onílara ènìyàn ni Aúdù jẹ́, inú rẹ̀ kò dún sí Lápàdé lórí ọ̀rọ̀ àwọn ọ̀daràn tí ó ń tojúbọ. Gbogbo ìgbà ni Aúdù ń wá ọ̀nà láti fojú Lápàdé hàn gẹ́gẹ́ bí arúfin. Ṣùgbọ́n gbogbo ìlàkàkà yìí, pàbó ló jásí.

Aúdù kùnà gẹ́gẹ́ bí ọ̀gá ọlọ́pàá nítorí pé lásìkò tí ó jẹ́ ọ̀gá àwọn ọlọ́pàá ní ìlú Ìbàdàn ìwà ipá àti ọ̀daràn ń gbilẹ̀ sí i ni. Èyi ló mú àwọn ará ìlú ké gbàjarè sí ìjọba pé kí wọ́n ni kí Aúdù máa lọ, èyí ló sì mú Aúdù kórìíra Lápàdé tí ó sì rí i gẹ́gẹ́ bí ọ̀tá rẹ̀.

**Tàfá Ìgìrìpá**
Jàndùkú àti ẹlẹ́wọ̀n tí ó ti gba òmìnira ni Tàfá Ìgìrìpá jẹ́, láti ìgbà tí Lápàdé ti wà nínú iṣẹ́ ọlọ́pàá ló ti mọ Tàfá gẹ́gẹ́ bí ọ̀daràn àti jàndùkú, ní kété tí Lápàdé pinnu láti wádìí àwọn ọ̀daràn tó n da Ìbàdàn láàmú, ó ránṣẹ́ pé kí Tàfá wá ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú rẹ̀. Tàfá jẹ́ ẹ̀dá ìtàn olóòótọ́, pẹ̀lú gbogbo ọ̀kán, ẹ̀mí àti agbára tí ó ní ló fi ṣiṣẹ́ fún Lápàdé. Aláforítì ènìyàn ni Tàfá, gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀daràn nígbà kan, ó mọ oríṣìíríṣìí ọgbọ́n tí àwọn ọ̀daràn yìí máa ń lò, bẹ́ẹ̀ ni ó mọ ibùba àwọn ọ̀daràn yìí pẹ̀lú. Òtítọ́ inú ti Tàfá fi ṣiṣẹ́ pẹ̀lú Lápàdé ló jẹ́ ki iṣẹ́ náà rọrùn fún Lápàdé bẹ́ẹ̀ ni Tàfá kó ipa pàtàkì nínú àṣeyọrí Lápàdé.

**Tìámíyù Alápámáṣiṣẹ́**
Tìámíyù jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀daràn tó ń da ìlú Ìbàdàn láàmú, ọ̀dọ̀ Tíàmíyù ni àwọn ọ̀daràn ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù kọ́kọ́ máa ń gbé ẹnìkẹ́ni tí wọn bá jígbé wá fún ìpamọ́. Tàfá ló gbá Lápàdé ni ìmọ̀ràn pé kí wọ́n wá Tọ̀lání ọmọ ọ̀dọ̀ Angẹlínà tó sonú lọ sí ọ̀dọ̀ Tìámíyù, ẹnu Délé ni Tàfá àti Lápàdé ti gbọ́ pe Ìkèrèkú ni wọ́n gbé Tọ̀lání lọ.

Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, ọ̀lẹ, olè àti alápámáṣiṣẹ́ ẹ̀dá ni Tìámíyù, ó wà pẹ̀lú àwọn ọ̀daràn ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù tí wọ́n ń tu igbó tí wọn gbin dànù nígbà tí Lápàdé yìnbọn fún un, àwọn ọlọ́pàá sì fi ojú rẹ̀ wi iná òfin.

**Gbékútà**
Ọ̀gá àwọn agbingbó ni Gbékútà. Ó ni oko igbó tí ó dá tí ó sì ń tà fún àwọn ará ìlú. Alábàáṣiṣẹ́pọ̀ ni Gbékútà, Tíàmíyù, Táíwò, Kọ̀lá àti Délé jẹ́.

Gbékútà pinnu láti pa Délé nígbà tí wọ́n gbọ́ pé òun lo júwe abà wọ́n ni Ìkèrèkú fún Lápàdé.

Gbékútà jẹ́ ìkà àti òsónú ẹ̀dá, òun ló dábàá pé kí wọn pa Sẹ̀lí ṣùgbọ́n Táíwó kọ̀ jálẹ̀ pé ìyàwó òun ni Sẹ̀lí. Gbékútà náà bo sọ́wọ́ sìnkún àwọn ọlọ́pàá ni oko igbó, ojú rẹ̀ sì rí màbo.

**Ṣẹ̀lí**
Arẹwà ọmọbìnrin ni Sẹ̀lí, owó ti bàbá rẹ̀ yá lọ́wọ́ Táíwò ti kò sì rí dá padà ló sọ ọ́ di èrò Ìkèrèkú, Sẹ̀lí jẹ aláàánú ẹ̀dá àti ẹni tí ọkàn rẹ̀ gbòòrò. Àánú Lápàdé àti Tàfá tí ó ṣe Sẹ̀lí ló jẹ́ kí ó tú àṣírí gbogbo ohun tí o ń lọ fún Lápàdé. Ọlọ́gbọ́n ènìyàn ni Sẹ̀lí, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, kò ní lè rí ààyè bá Lápàdé sọ gbogbo ohun tí ó bá a sọ. Ìrànwọ̀ ti Sẹ̀lí ṣe fún Lápàdé àti Tàfá ní oko igbó ló jẹ́ kí Lápàdé ṣe àṣeyọrí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Lápàdé ti sọ fún Sẹ̀lí pé kí ó máa mú Tọ̀lání lọ́ sí Ìbàdàn, síbẹ̀ ó fara pamọ́ láti mọ ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ sí Lápàdé àti Tàfá. Ìrànwọ̀ ti Sẹ̀lí ṣe yìí bọ́ sí àkókò, èyí si fi Sẹ̀lí hàn gẹ́gẹ́ bí akin obìnrin.

**Ìlò Èdè**
Àwọn ọ̀nà ti Òkédìjì gbà lo èdè nínú ìtàn àròsọ amárabùmásọ Àjà ló lẹrù fi hàn gẹ́gẹ́ bi òǹkọ̀wé tí ó gbọ́ èdè, tó tún mọ bi a ṣe ń gbé èdè kalẹ̀. Àwọn ìlò èdè tí a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò wọn ni: àfiwé, ìfọ̀rọ̀dárà, ìbádọ́gba gbólóhùn, èdè àdùgbò, òwe, oríkì àti orin.

**Àfiwé**
Òkédìjì lo ọ̀pọ̀lọpọ̀ àfiwé nínú ìtàn àròsọ Àjà ló lẹrù. Àwọn àfiwé tí Lápàdé ṣàmúlò yìí jẹ́ kí ohun tí ó ń sọ yéni sí i. Fún àpẹẹrẹ:
Ó dàbí adití tí ń wòran, tó ń rí
Ohun tó n ṣẹlẹ̀, tí kò gbọ́ nnkankan,
Tàbí bí ìgbà tí ènìyàn bá n wo sinimọ́ tí kìí sọ̀rọ̀ (o.i 44)
Sàlámì Kemberú wá si ilé Lápàdé lóru láti wá gbé owó tó hú lọ́sàn-án ọjọ́ náà lọ. Lápàdé kò sùn, ó n wo olè náà bí ó ṣe wọlé láìsọ̀rọ̀. Bí Lápàdé ṣe dákẹ́ láìsọ̀rọ̀ yìí ni Òkédìjí ṣe fi Lápàdé wé adití àti ẹni tí n wo sinimá.
Túbọ̀mu ẹnu rẹ̀ nìyí yàwúyàwú bíi tí ológbò yìí,
tí àgbọ̀n rẹ̀ sì n dán Sàn-án bi igbá báàrà (o.i 8)

Lápàdé ṣe alábàápàdé Aúdù ọ̀gá ọlọ́pàá lẹ́yìn ọjọ́ pípẹ́ tí Lápàdé ti kúrò nínú iṣẹ ọlọ́pàá. Túbọ̀mu Aúdù ni Lápàdé fi wé ti ológbòó tí ó sì fi àgbọ̀n rẹ̀ tí ó n dán wé igbá báárà.

**Ìfọ̀rọ̀dárà**
Láti lè tàbùkù ọ̀gá àwọn ọlọ́pàá àti láti fi àìjáfáfá àwọn ọlọ́pàá hàn ni Lápàdé se fi orúkọ Aúdù Kàrímù dárà.
Kí ló tilẹ̀ n dù tó n rí mú gan-an?
Kò lè dá adìẹ mú, ká tóó sọ pé àwọn tagbótagbó (o.i 3)

**Ìbádọ́gba**
Gẹ́gẹ́ bí akéwì, Òkédìjí máa ń lo ìbádọ́gba gbólóhùn láti fi ìdí àwọn ọ̀rọ̀ rẹ̀ múlẹ̀. Lápàpé bèèrè lọ́wọ́ Tàfá bóyá ó ṣetán láti yọ eyín Tìámíyù méjì, Tàfá dáhùn láti fi ìmúratán rẹ̀ hàn.
Kí ni ààké n ṣe tí ò lè lagi
Kí làbíkú ń ṣe tí ò le pàyá ẹ̀ lẹ́kún
Kí làgbàrá òjò ń ṣe tí ò le gbọ́mọdìẹ? (o.i 87)

Àwọn gbólóhùn mẹ́tà òkè yìí ló bá ara wọn dọ́gba, tí ó si múni lọ́kàn bí èdè ewì.

**Èdè àdúgbò**
Òkédìjí jẹ́ òǹkọ̀wé tkí ó gbọ́ onírúurú èdè àti èdè àdúgbò. Ó máa n jẹ́ kí ọ̀kan lára àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ sọ èdè àdúgbò kan ní ilẹ̀ Yorùbá nígbà tí ó bá yẹ. Fún àpẹẹrẹ:
Sàlámì Kemberú sọ èdè Ìjẹ̀ṣà nígbà tí ọwọ́ tẹ̀ ẹ́ ni ilé Lápàdé
Olè máa dáhùn, ó ní, Ẹ sọ́ni rán mi áà
Emi tika ni gùnkè. Mé rìíun jẹ, mé dẹ léó. Mé di rí̩ṣẹ́.
Iún mú mi jáde lúlé lèinì. Wé a méó dìẹ̀ kò mí ọ̀gá?
Mé ṣàdédé jalè, ebi léé pa mi (o.i 45)

**Òwe**
Òwe jẹ́ bárakú fún Òkédìjí nínú ìwé ìtàn àròsọ Àjà ló lẹrù. Òkèdìjí fi ìgbàgbọ́ rẹ̀ nínú òwé hàn pé òwe Yorùbá jẹ́ irinṣẹ́ pàtàkì fún ìbánisọ̀rọ̀ ọ̀nà ti Òkédìjí gbà lo òwe nínú Àjà ló lẹrù. Nígbà tí ó to àwọn òwe kan bí a ṣe n lò wọ́n lójú ayé, ó ṣe àtúnṣe sí àwọn kan nígbà tí ó sì fi àwọn òwe kan ṣe àlàyé.

Fún àpẹẹrẹ nígbà ti Lápàdé n bọ̀ láti ọ̀nà oko lórí kẹ̀kẹ́ rẹ̀, ó gun òkè náà jà bí idan, kò ronú àtiko bíréèkì, kẹ̀kẹ́ rẹ̀ sáá n gbé e lọ nítorí ó fẹ́ tètè dé ilé.
Ẹṣin kì í kọ aré àsárelé (o.i 6)

Òkédìjí ṣe àtúnṣe òwe yìí torí ọ̀tọ̀ ni bi àwọn Yorùbá ṣe máa ń pa á. Wọ́n á ni "Bó ti wu ni làá sèmọ̀le ẹni".

Bákan náà nígbà ti Lápàdé wà lórí kẹ̀kẹ́ rẹ̀ tí ó n bọ̀ láti ọ̀nà oko ó gbọ́ ìró kan nínú igbó, torí ìwà àti ìfura ọlọ́pàá tí ó ní, ó mọ̀ pé ìró náà mú ìfura dání. Eléyìí dá Lápàdé lójú èyí lo mu Òkédìjí lo òwe kan láti fi ìdí èyí múlẹ̀.
Ikún ní, nkan tí ènìyàn bá mọ̀ ọ́n ṣe,
Bí <u>idan</u> ní i rí (o.i 3)

Òkédìjí mọ̀ pé òwe yìí lè má yeé ọ̀pọ̀ àwọn òǹkàwé dáadáa, nítorí ìdí èyí ó ṣe àlàyé òwe náà. O ní bí òun bá n lọ nínú oko ẹ̀pa ni tòun, òun kì í mọ́

ìgbà ti ẹ̀pa fi máa n dé ẹnu òun. Òun kàn máa ń bá ẹ̀pà lẹ́nu òun ni. Òkédìjí ṣàlàyé pé ìwà ọlọ́pàá kò fi Lápàdé sílẹ̀, ó jẹ́ ẹni tí ó ní ìfura púpọ̀.

**Oríkì**

Oríkì tún jẹyọ púpò nínú ìtàn Àjà ló lẹrù. Tàfá Ìgìrìpá tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀dá ìtàn Àjà Ló lẹrù tilẹ̀ fẹ́ràn láti máa ki ara rẹ láìmọye ìgbà, oríkì rẹ̀ yìí sì fi hàn gẹ́gẹ́ bí jàǹdùkú àti ìpánle ẹ̀dá.

Èmi Tàfá Ìgìrìpá ọmọ Láwálé,<br>
Èmi Àjàó àró fúnra mi, abojúúbọmọlẹ́rù<br>
Èmi abẹkún-ún-pọmọ-lẹ́rìn-ín pọmọ lẹ́kún,<br>
Olójúu-bá-mi dẹ́rù-bọmọ-mi, èmi àyà-jinmọ-gìrìgìrì (o.i 57)

Fún àwọn àpẹẹrẹ oríkì mìíràn wo ojú ìwé 22, 23, 40, 46, 82, 83, 56, 130 àti 134.

**Orin**

Nínú Àjà ló lẹrù Òkédìjí lo orin àlọ̀ kan èyí tí o ní ìtumọ̀ pàtàkì, Lápàdé kọ orin yìí fún ìgbà àkọ́kọ́ láti fi àìbalẹ̀ ọkàn àwọn olùwádìí, ọ̀daràn àti àwọn ọlọ́pàá hàn.

Àwòdì òkè, ó rò p’ẹ́nìkan ò rí un<br>
Àwòdì òkè, fìfò tó fò, gìga t’ó ga<br>
Àwòdì òkè, ó rò p’ẹ́nìkan ò rí un<br>
Àwòdì òkè (o.i. 17)

Ní gẹ́rẹ́ ti Lápàdé kọ orin yìí tán ó bẹ̀rẹ̀ sí í ní ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ lọ́kàn rẹ̀. Ó fi ara rẹ̀ wé àwòdì òkè tí ó rò pé ẹnìkan kò rí òun fún owó tí ó hú lọ́nà oko àti Táíwò tí ó dè mọ́ igi. Ó rántí pé Aúdù ọ̀gá ọlọ́pàá rí òun nígbà tí ó ń lọ sí Àkánràn, bẹ́ẹ̀ abiyamọ kan náà rí òun. Ìgbàkúgbà tí Lápàdé bá ti fura sí ìṣẹ̀lẹ̀ kan ló máa ń kọ orin àwòdì òkè.

Fún àpẹẹrẹ orin mìírán wo ojú ìwé 31, 16, 84.

## 4.4 Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́: I.B Thomas

**Kókó**

**Èrè Àgbèrè**-Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún ọkọ Láyé tí ó jẹ́ ọmọ oníbìí níran àti arẹwà obìnrin fi ojúkòkòrò àti àgbèrè ba ayé ara rẹ̀ jẹ́ nítorí ẹwà ti Ẹlẹ́dàá fi jínkí rẹ̀. Sẹ̀gilọlá lọ̀ sílé babaláwo láti ṣe aájó àtimáa ri owó gbà dáadáa lọ́wọ́ àwọn àlè rẹ̀ ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé babaláwo ló gba ògo wúndíá Sẹ̀gi, èyí si fa wàhálà ńlá láàrin Sẹ̀gilọlá àti Bánkọ́lé ọkọ alárédè rẹ̀. Ṣẹ̀gilọlá ba ọkùnrin àlè rẹ̀ kan sálọ sí Sẹkondí, ibẹ̀ ló sì wà tí ìyá rẹ̀ ṣe jẹ́ aláìsí. Ṣẹ̀gilọlá ṣe òkú ìyá rẹ̀, ayé gbọ́, ọ̀run sì mọ̀. Lẹ́yìn ìsìnkú ìyá rẹ̀ ni Sẹ̀gilọlá yan àgbèrè ṣíṣe ni ìbáádà. Bí ó ti n gbé dúdú, ló ń gbé pupa. Kò pẹ́, kò jìnnà, àìsàn ńlá kọlu Sẹ̀gilọlá èyí tí ó mú kí àwọn ọkùnrin máa sá fún un. Ṣẹ̀gilọlá kò ní ọmọ kankan láyé mọ́ bẹ́ẹ̀ ni àtijẹ di ìṣòro fún un. Ìgbà yí padà fún Ṣẹ̀gilọlá, kò ni ọmọ kankan láyé mọ́ bẹ́ẹ̀ ni àtijẹ di ìṣòro fún un. Ìgbà yí padà fún Ṣẹ̀gilọlá, èyí ló mú un kọ ìtàn ìgbésí ayé

rẹ̀ fún àwọn ènìyàn láti kẹ́kọ̀ọ́ pe àṣegbé kan kò sí, àti pé àṣepamọ́ ló wà. Pẹ̀lú imi ẹ̀dùn, àbámọ̀ àti ìpohùnréré ẹkún ni Ṣẹ̀gilọlá ń sọ ìtàn ìgbésí ayé àgbèrè tí ó gbé.

**Àhunpọ̀ Ìtàn**

Apá ọgbọn ni Thomas pin ìwé ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ sí àhunpọ̀ ìtàn àròsọ ṣẹ̀gilọlá jẹ́ èyí tí ó bani lọ́kàn jẹ́ láti ìbẹ̀rẹ̀. Apá kìnní ni ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn, ibẹ̀ sì ni Ṣẹ̀gilọlá ti bẹ̀rẹ̀ ìmí ẹ̀dùn rẹ̀ tí ó sì ń kábámọ̀ gbogbo àwọn ìgbésí ayé tí ó ti gbé sẹ́yìn. Ọ̀nà tí ìwé ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá gbà bẹ̀rẹ̀ jẹ́ èyí tí ó múni lọ́kàn tí òǹkàwé sì ń fẹ́ láti mọ ohun tó ṣẹlẹ̀ nípa kíka ìwé náà parí. Apá kejì sí ìkọkàndínlọ́gbọ̀n ni Ṣẹ̀gilọlá ti ṣípayá gbogbo ìgbésí ayé àgbèrè tí ó gbé sẹ́yìn. Apá ọgbọ̀n tí ó jẹ òpin àhunpọ̀ ìtàn ni Ṣẹ̀gilọlá tí sọ ilé ìyá rẹ̀ tó kú di ilé aṣẹ́wó lẹ́yìn tí ó sin òkú ìyá rẹ̀ tán. Láìròtẹ́lẹ̀, àìsàn ńlá kan kọlu Ṣẹ̀gilọlá èyí ló sì sọ ọ́ di àwòmọ́jú fún àwọn ọkùnrin. Pẹ̀lú oríṣìíríṣìí ọ̀rọ̀ àanú àti ìkẹ́dùn ti Thomas ń sọ́ lóòrèkóòrè nínú ìwé ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá, ó mú ìmọ̀sílára àti ìfẹ́ àwọn òǹkọ̀wé dúró títí dé òpin..

**Ibùdó Ìtàn**

Ibùdó ìtàn gbogbogbòò fún ìtàn Èmi Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́, Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé ni ilẹ̀ Yorùbá ní ìlú Èkó. Àwọn ibùdó ìtàn pàtó sí ni, Ilé ìyá Ṣẹ̀gilọlá, ilé Àyọ̀ká, Ilé Abíọ́lá, Sọ́ọ̀sì Alágogo Ẹ̀yìngbẹ̀tì, Ilé Bánkọ́lé àti Sẹkọndi.

**Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn**

Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-ṣe ni Thomas lò fún kíkọ ìwé ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ torí Sẹ̀gilọlá ti ìtàn náà ṣẹlẹ̀ sí ni ó fi ẹnu ara rẹ̀ sọ ìtàn ìgbésí ayé rẹ̀ fún aráyé gbọ́. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn mìíràn tí ó tún jẹyọ ní ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà, lásìkò tí Ṣẹ̀gilọlá ń kọ lẹ́tà sí òǹkọ̀wé yìí, ọgbọ́n ìsọ̀tàn onílẹ́tà jẹ́ tuntun sí àwọn òǹkàwé èdè Yorùbá. Eléyìí jẹ́ kí ìwé náà ṣe ìtẹ́wọ́gbà nítorí ó jẹ́ ìtàn àsírí ìgbésí ayé ẹ̀dá kan. Ọgbọ́n pé ki ẹ̀dá kan máa sọ àṣírí ìtàn ayé rẹ̀ nípa lẹ́tà kíkọ jẹ́ kí àwọn òǹkàwé fẹ́ láti ka ìwé náà àti láti mọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀. Ọgbọ́n lẹ́tà yìí jẹ́ kí ìtàn Ṣẹ̀gilọlá jẹ mọ ìtàn ìjẹ́wọ́ ẹ̀sẹ̀ tòótọ́, èyí si mú ìbàjẹ́ dání. Àwọn ọgbọ́n ìsọ̀tàn mìíràn tí ó tún jẹyọ ni ọgbọ́n pípadàsẹ́yìn àti ìgbénilọ́kàn sókè.

**Ìfiwàwẹ̀dá**

Àwọn ẹ̀dá ìtàn mẹ́fà ni a o máa ṣe àgbéyẹ̀wò wọn nínú ìwé ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé. Àwọn ẹ̀dá ìtàn náà ni Ṣẹ̀gilọlá, Àyọ̀ká, Sànyà, Lábọ̀dé, Bánkọ́lé àti Àsàbí.

**Ṣẹ̀gilọlá**

Arẹwà obìnrin ni Ṣẹ̀gilọlá jẹ, ọmọ oníbìíníran ni pẹ̀lú. Ṣẹ̀gi ni àbíkẹ́yìn nínú ọmọ mẹ́fà tí ìyá rẹ̀ bí ṣùgbọ́n gbogbo àwọn tí ó ṣaáájú Sẹ̀gilọlá máràárùn ti jẹ ipè Olódùmarè láti kékeré wọn. Bàbá Sẹ̀gilọlá jáde láyé nígbà tí Sẹ̀gi di ọmọ ọdún kan àti ọ̀sẹ̀ kan àbọ̀. Ìyá Ṣẹ̀gilọlá gbìyànjú púpọ̀ láti tọ́ ọmọ rẹ̀ sọ́nà rere bẹ́ẹ̀ ni kò fi ohun kan jẹ ẹ́ níyà, gbogbo ìlàkàkà àti

akitiyan màmá Sẹ̀gilọlá lórí rẹ̀ pàbó ló já sí. Ẹ̀wà tí Ọlọ́run fi jínkí Sẹ̀gilọlá kó sí i lórí ó sì yan àgbèrè ṣíṣe ni ìbáádà. Oríṣìíríṣìí ọkùnrin ni Sẹ̀gilọlá bálòpọ̀ tí ó si gba owó lọ́wọ́ wọn. Olójò tí ó jẹ́ babaláwo ló gba ògo wúndíá Sẹ̀gilọlá, èyí sì dá yánpọn-yánrin sílẹ̀ nígbà tí ọkọ alárédè rẹ̀ Bánkọ́lé mọ èyí. Sẹ̀gilọlá bímọ fún Bánkọ́lé ṣùgbọ́n nítorí ìṣekúse, ọmọ náà kú lẹ́yìn oṣù méje àbọ̀ tí ó bí i. Ṣẹ̀gilọlá ba àlè rẹ kan sálọ sí Sẹkọ́ndi, ọjọ́ tó kú ọjọ́ méjì kí ó pé ọdún kan ti Sẹ̀gilọlá sá kúrò ní ìlú Èkó ni wọ́n ránṣẹ́ sí i pé ìyá rẹ̀ jẹ́ aláìsí, lẹ́yìn ìsìnkú ìyá Sẹ̀gilọlá, ó sọ̀ àgbèrè síṣe di iṣẹ́. Sẹ̀gilọlá jẹ ẹ̀dá ìtàn olójúkòkòrò àti aláìní ìtẹ́lọ́rùn, kò rántí pe tí ìdí bá bàjẹ́ tán, tí onídìí ló máa ń dà. Àìsàn ńlá kọlu ú, ó jèrè ìwà àgbèrè rẹ̀, ó sì kábámọ̀ ìwà àgbèrè rẹ̀. Ṣe Yorùbá bọ̀, wọn ni, àbámọ̀ kì í síwájú, ẹ̀yìn ọ̀rọ̀ ní í wà.

**Àyọ̀ká**

Ọ̀rẹ́ kòríkòsùn Sẹ̀gilọlá ni Àyọ̀ká jẹ́, gbogbo àwọn owó àti ẹ̀bùn tí àwọn ọkùnrin fi n ta Ṣẹ̀gilọlá lọ́rẹ, ilé Àyọ̀ká ni ó máa n kó wọn pamọ́ sí. Àyọ̀ká yìí kan náà ló mú Ṣẹ̀gilọlá lọ sí ilé babaláwo tó gba ògo wúndíá Ṣẹ̀gilọlá, gbogbo akitiyan ìyá Bánkọ́lé láti ya Ṣẹ̀gilọlá àti Àyọ̀ká kò so èso rere, lẹ́yìn ikú Àṣàbí ìyá Sẹ̀gilọlá, Àyọ̀ká ló ránṣẹ́ sí Sẹ̀gi pé ìyá rẹ̀ ti kú. Àyọ̀ká gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn jẹ́ ọ̀rẹ́ burúkú, ìmọ̀ràn ti Àyọ̀ká fún Sẹ̀gilọlá wà lára ohun tí ó jẹ́ ki Sẹ̀gilọlá sọ àgbèrè síṣe di òwò. Ìkà àti arírebánijẹ ọ̀rẹ́ ni Àyọ̀ká jẹ́.

**Sànyà**

Sànyà ni ọkùnrin àkọ́kọ́ tí ó bá Sẹ̀gilọlá sọ̀rọ̀ ìfẹ́. Sẹ̀gilọlá fẹ ki Sànyà ṣe ìgbéyàwó alárédè pẹ̀ú òun ṣùgbọ́n Sànyà sọ fún Ṣẹ̀gilọlá pe èèwọ̀ ni arédè gbígbé jẹ́ ní ìdílé àwọn. Sẹ̀gi bẹ̀rẹ̀ sí ní gba owó lọ́wọ́ Sànyà, ó sì kọ̀ láti jẹ́ kí ẹbi Sànyà wá rí ìyá rẹ̀, Sànyà fi Ṣẹ̀gilọlá sílẹ̀ ó fẹ́ ìyàwó méjì mìíràn ó sì ń se ọmọlúàbí.

**Lábọ̀dé**

Lábọ̀dé jẹ ọ̀kan lára ọ̀rẹ́kùnrin Sẹ̀gi, Ó ṣe ìlérí pé òun yóò ti òrùka arédè bọ̀ ọ́ lọ́wọ́, bí ó bá gba ìfẹ́ fún òun. Sẹ̀gi mọ̀ pé Lábọ̀dé kò le fẹ́ òun sílé gẹ́gẹ́ bí aya torí bàbá Lábọ̀dé fẹ́ rán an lọ sí ìlú òyìnbó láti lọ kọ́ iṣẹ́ Lọ́yà. àti pé àwọn òbí Lábọ̀dé ti n ṣe ọ̀nà ọ̀dọ́mọbìnrin, ọmọ olówó kan fún Lábọ̀dé láti bá a gbéyàwó. Sẹ̀gilọlá fi Lábọ̀dé sílẹ̀ lẹ́yìn tí ó ti gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó àti dúkìá lọ́wọ́ rẹ̀, gbogbo akitiyan Lábọ̀dé láti gbẹ̀san ìwà ẹ̀tàn Sẹ̀gi pẹ̀lú rẹ̀ pàbó ló jásí.

**Bánkọ́lé**

Bánkọ́lé ará Ìta-Ìkọ́ṣẹ́ ni Sẹ̀gilọlá ṣe ìgbéyàwó alárédè pẹ̀lú, ṣùgbọ́n akutupu hu lálẹ́ ọjọ́ ìgbéyàwó Sẹ̀gilọlá nígbà ti Bánkọ́lé mọ̀ pé ọkùnrin mìíràn ti gba ìbálé rẹ̀. Inú ìyá Bánkọ́lé kò dùn fún ìṣẹ̀lẹ̀ yìí, bẹ́ẹ̀ ni ìyá Sẹ̀gilọlá dùbúlẹ̀ ìbànújẹ́ fún ọ̀rọ̀ àìyege ọmọ rẹ̀, ó sì sọ pabanbarì ọ̀rọ̀ sí i. Sẹ̀gilọlá bímọ fún Bánkọ́lé ṣùgbọ́n ọmọ náà ku lẹ́yìn oṣù méje àti ààbọ̀. Pabanbarì rẹ̀ ni pé Sẹ̀gilọlá sá ba àlè lọ sí Sẹkọndì. Bánkọ́lé fẹ ìyàwó

mìíràn, ó sì bímọ. Pọ́nùn márùn ún ni Bánkọ́lé fún Sẹ̀gilọlá ní ìgbà tí ìyá rẹ̀ kú.

**Àsàbí**
Ìyá Sẹ̀gilọlá ni Àsàbí jẹ́, ọmọ mẹ́fà ni Àsàbí bí ṣùgbọ́n Sẹ̀gilọlá tí ó jẹ àbígbẹ̀yìn nìkan ni ó dúró sin iń. Gbogbo ìlàkàkà Àṣàbí láti jẹ́ ki ọmọ rẹ̀ Sẹ̀gilọlá yàn an re ló jásí pàbó. Sẹ̀gilọlá fi ìyà rẹ sílẹ̀ bá àlè sálọ sí Sẹkọndì, bẹ́ẹ̀ ni nìgbà tí ó kú ọjọ́ méjì kí ó pé ọdún kan ti Sẹ̀gilọlá ti bá àlè rẹ̀ sálọ ni wọn ránṣẹ́ sí pé ìyá rẹ̀ kú. Sẹ̀gilọlá sin ìyá rẹ̀, ayé gbọ́, ọ̀run sì mọ̀. Ìyá rere, abiyamọ tòótọ́ ni Àṣàbí ṣùgbọ́n ìrònú ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo ni ó ṣekú pa á.

**Ìlò Èdè**
Àwon ìlò èdè pàtàkì ti a ó jíròrò lé lórí nínú ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé ni àfiwé, àkànlò èdè, òwe, oríkì, Ẹsẹ bíbélì àti orin.

**Àfiwé**
Thomas ṣe àmúlò àfiwé lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá, àpẹẹrẹ àfiwé nínú ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá nìyí:
Ojú èmi Sẹ̀gilọlá ló wú <u>bí</u> èso igi
Ọlọ́bọ̀ùn boùn yìí (o.i30)
Èyí ló mú kí ọkùnrin náà máa náwó fún mí ní ìbọ̀lẹ̀ <u>bíi</u> lárìrà.
Sẹ̀gilọlá fi ojú rẹ̀ tó wú nígbà tí ó bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣe àìsàn we èso igi ọlọ́bọ̀ùnbọún. Bẹ́ẹ̀ ni ó fi bí ọkùnrin náà ṣe n náwó fún un wé árìrà.

**Àkànlò èdè**
Àkànlò èdè náà tún jẹyọ nínú ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́. Fún àpẹẹrẹ:

Lábọ̀dé sì rí i pé òun kò tí i <u>rí nǹkan mú jẹ lórí mi</u> (o.i 20)
Èyí túmọ̀ sí pé Lábọ̀dé kò tí ì ráyé bá Sẹ̀gilọlá ní àsepọ̀ tàbí ìbálòpọ̀, láti ìgbà náà ni ọkùnrin náà ti ń gbìyànjú láti fẹ́ fi <u>òbẹ ẹ̀yìn jẹ́ èmi Sẹ̀gilọlá nísu</u> (o.i 26)
Ọkùnrin náà ń gbìyànjú láti bá Sẹ̀gilọlá ni ìbálòpọ̀. Wo àpẹẹrẹ sí i ni o.i. 30, 35, 43, 50, 54,56.

**Òwe**
Ìlò òwe wọ́pọ̀ nínú ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́, Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé ojú ìwé kọ̀ọ̀kan nínú ìtàn àròsọ náà ni òwe sodo sí. Bí a ṣe máa ń pa òwe láwùjọ Yorùbá ni Thomas ṣe fi sí ẹnu àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀.
Fún àpẹẹrẹ ọ̀kan-ò-jọ̀kan òwe wo ojú ìwé 11,13,17,23,26,29,35,37,43,51.

**Oríkì**
Oríkì náà tún jẹyọ nínú ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé. Bí àpẹẹrẹ

Gbéerè ire o, ìyá mi Àṣàbí ògún (o.i. 7)
Sẹ̀gilọlá ni ó n ki ìyá rẹ bẹ́ẹ̀ lọ́nà ọ̀run ni ìgbà tí ó rántí rẹ̀
Àbẹ̀kẹ́ ọmọ mi, ọmọ àgbe-gbà lósì
Ọmọ Olúgbọ́n, ọmọ-àkin tó bí nana.

Ìyá Sẹ̀gilọlá ló n kì í ni mẹ́sàn-án mẹ́wàá ní ìgbà tí ó n lọ ilé ọkọ

**Ẹsẹ Bíbélì**
Thomas ṣàmúlò àwọn ẹsẹ Bíbélì lọ́nà tó tọ́, bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ó lo ẹsẹ Bíbélì tí ó pọ̀, Ó lò wọ́n lọ́nà tí ó yẹ, àwọn ẹsẹ Bíbélì wọ̀nyí n ṣe àfihàn ìyípadà ọkàn ìbẹ̀rù sí ọkàn ìkábámọ̀ ohun buburú, tí ó sì ṣetán láti yípadà.
Fún àpẹẹrẹ àwọn ẹsẹ Bíbélì, wo ojú ìwé 102, 103, 111.

**Orin**
Thomas lo orin lọ́pọ̀lọpọ̀ nínú ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́, bí ó ṣe ṣàmúlò orin ìdárayá bẹ́ẹ̀ ló tún lo orin òwe, àlùjó àti orin onígbàgbọ́. Fún àpẹẹrẹ, orin nínú ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́, wo ojú ìwé 5,10,11,13,18,20,21,24,33,34,39,41.

**Àgbálọgbábọ̀**
Nínú ìpín karùn-ún lábẹ́ módùlù kẹta yìí a ti ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, àwọn ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin náà ni *Ọmọ Olókùn Ẹsin* tí Adébáyọ̀ Fálétí kọ, *Ọ̀bàyéjẹ́* tí Bùnmi Olújìnmí kọ, *Àjà ló lẹrù* tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ àti ìtàn *Èmi Ṣẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjú Ẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé* tí I.B Thomas kọ. A sọ̀rọ̀ nípa kókó tí ìwé mẹ́rẹ̀ẹ̀rin dálé, àhunpọ̀ ìtàn kọ̀ọ̀kan àti ọgbọ́n ìsọ̀tàn tí a fig bé wọn kalẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni a jíròrò nípa ìlò èdè àwọn òǹkọ̀tàn ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin.

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín karùn-ún yìí a ti kékọ̀ọ́ pé:

- Adébáyọ̀ Fálétí ni ó kọ ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin
- Kókó kan pàtàkì tí ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin dálé ni omìnira
- Apá méta ni a pín ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin sí
- Ilẹ̀ Yorùbá ní agbègbè Òkè-Ògùn ni ibùdó gbogbogbòò fún ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin
- Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-se ni Fálétí fi ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin
- Àjàyí Ọmọ Olókùn Ẹsin ni olú ẹ̀dá ìtàn nínú ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin
- Ìlò èdè Fálétí nínú ìtàn àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin fi hàn gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé tí ó dáńgájíá
- Àwọn ọnà èdè ti Fálétí ṣàmúlò ni Àfiwé, èdè àtijọ́, àkànlò èdè àti òwe
- Ọládẹ̀jọ Òkédìjí ló kọ ìwé ìtàn ìtàn àròsọ Àjà ló lẹrù
- Orí mẹ́wàá ni Òkédìjí pín ìwé ìtàn àròsọ Àjà ló lẹrù sí

- Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni a fi gbé Àjà ló lẹ̀rù kalẹ̀
- Lápàdé ni olú ẹ̀dá ìtàn Àjà ló lẹ̀rù
- Àwọn ọnà èdè tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí ṣàmúlò ni àfiwé, ìfọ̀rọ̀dárà, ìbádọ́gba gbólóhùn, èdè àdúgbò, òwe, oríkì àti orin
- Bùnmi Olújìnmí ni ó kọ ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́
- Ogun ilé aye, ìbáwí òbí àti pàtàkì ẹ̀kọ́ ìwé ni ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ ń pàrokò rẹ̀
- Orí mọ́kànlá ni ìwé ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ pín sí
- Ọgbọ́n ìsọ̀tàn arínúróde ni Olújìnmí fi gbé ìtàn àròsọ Ọ̀bàyéjẹ́ kalẹ̀
- Àjàdí ni olú ẹ̀dá ìtàn Ọ̀bàyéjẹ́
- Àfiwé, àwítúnwí, àsọrégèé, òwe, ọfọ̀, oríkì àti orin ni wọ́n jẹ́ ìlò èdè Olújìnmí nínú Ọ̀bàyéjẹ́
- I.B Thomas ló kọ ìtàn àròsọ Sẹ̀gilọlá Ẹlẹ́yinjúẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé
- Apá ogbọ̀n ni Thomas pín ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá sí
- Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ojú-mi-ló-se ni a fi gbé ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá kalẹ̀
- Sẹ̀gilọlá ni olú ẹ̀dá ìtàn nínú ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá Ẹ́lẹ́yinjúẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé
- Àwọn ìlò èdè inú ìwé ìtàn àròsọ Ṣẹ̀gilọlá Ẹ́lẹ́yinjúẹgẹ́ Ẹlẹ́gbẹ̀rún Ọkọ Láyé ni àfiwé, àkànlò èdè, òwe, oríkì, ẹsẹ Bíbélì àti orin.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢẸ

1. Ṣe ìsọnísókí àwọn ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí a ti túpalẹ̀
2. Pàlà láàrin ìlò èdè àwọn òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí a túpalẹ̀
3. Ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé nípa àrokò tí àwọn òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí a gbé yẹ̀wò ń fi ìtàn àròsọ wọn pa fún àwùjọ

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Adébọ̀wálé, O. (1999). *Ọgbọ́n Òǹkọ̀wé Alátínúdá*. Lagos: The Capstone

Ìṣọ̀lá, A. (1998). *The Modern Yorùbá Novel: An Analysis of the Writer's Art*. Ìbàdán: Heinemnn Educational Books.

Ogundeji, P.A. (1991). Introduction to Yorùbá Written Literature, External Studies Programme, Department of Adult Education, University of Ibadan, Ibadan.

Ogúnsínà, B. (1992). *The Development of the Yorùbá Novel 1930 – 1975*. Ìlọ̀rin: Gospel Faith Mission Press.

Ogúnsínà, B. (2001) 'Ìdílè àti Ìdàgbàsókè Lítíreṣọ̀ Àpilẹkọ Yorùbá' nínú Ẹ̀kọ́ *Ìjìnlẹ̀ Yorùbá, Ẹ̀dà Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Bádé Àjàyí (olóòtú). Ìlọrin: University Press Ltd.

Ogunsina, B. (2002). *Ṣaájú Fágúnwà.* Ilorin: Department of Linguistics and Nigerian Langauges, University of Ilorin.